# Sisa kuro nibi aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun lọ sí inu Isilaamu.

شركاء التنفيذ:

دار الإسلام　جمعية الربوة　رواد الترجمة　المحتوى الإسلامي

يتاح طباعة هذا الإصدار ونشره بأي وسيلة مع الالتزام بالإشارة إلى المصدر وعدم التغيير في النص.

Telephone: +966114454900
ceo@rabwah.sa
P.O.BOX: 29465
RIYADH: 11557
www.islamhouse.com

Pẹlu orukọ Ọlọhun, gbogbo ẹyin tí Ọlọhun ni, ikẹ ati ọla Ọlọhun ki o maa ba ojiṣẹ Ọlọhun ati awọn ara ile rẹ ati awọn saabe rẹ ati awọn ti wọn ba tẹle e, lẹyin naa.

Tira kékeré yii: "Sisa kuro nibi aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun lọ sí inu Isilaamu"

Tira pelebe náà n tì siwaju wa alaye kan fún "bi aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun ṣe rí" ati awọn iruju rẹ, ati bi aigbagbọ ṣe tako àwọn nǹkan tí o hàn kedere nínú làákàyè àti àdánidá.

Ati pe tira kekere yii nṣe afihan awọn ẹri iṣe afirinlẹ bíbẹ Aṣẹ̀dá, mimọ fún Un.

Torípé àwa da Ọlọhun - ti O biyi ti O sì tun gbọnngbọn - mọ pẹlu làákàyè, Ọlọhun tí ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿أَمۡ خُلِقُواْ مِنۡ غَيۡرِ شَيۡءٍ أَمۡ هُمُ ٱلۡخَٰلِقُونَ ٣٥﴾ [الطور: 35]

{Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá ? Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni ? {35} Sūratu Tūr ?].

Nnkan mẹta kan nbẹ ti o ṣee ṣe ki o ṣẹlẹ̀ pẹlu làákàyè ti ko sì ìkẹrin fún wọn :

Àkọ́kọ́ : kí o jẹ wipe wọn dá wa láì sí oluda kankan (Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá ?) Eleyii ko si rọrun, torípé bawo ni wọn yíò ṣe dá wa láì sí oluda kankan ?

Ẹlẹẹkeji : ki o jẹ pe awa ni a da ara wa (Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni ?) eleyii naa o ṣee ṣe, bawo ni maa ṣe da ara mi ṣiwaju ki wọn o too da mi ?

Ti o ba ri bẹ́ẹ̀, pẹlu laakaye, o maa ṣẹku ohun kẹta ti o ṣee ṣe ki o ṣẹlẹ̀, oun si ni aaya alapọn-ọnle yii kò sọrọ nipa rẹ nitori pe oun ni nǹkan ti o kọkọ maa wa si làákàyè, oun si ni pe a ni Aṣẹ̀dá ti O da wa.

Nitori náà àwa mọ Ọlọhun pẹlu làákàyè.

Bákannáà ni a mọ Ọlọhun pẹlu adamọ.

Ati pe a mọ pẹlu adamọ wa wipe dajudaju awọn òòsà ati adamọ o ni ikapa lori dídá ayé àti lórí dídá kòkòrò àti èèyàn, wọn o si tun ni i lori ìdarí awọn iṣẹ àrà ọmọnìyàn pẹlú àwòrán yìí, wọn o si tun ní í lórí dídá ẹda dáadáa lati ori átọ̀mù bín-ín-tín dórí ìṣùpọ̀ ìràwọ̀.

Nitori naa awọn òòsà ti awọn keferi n sìn, ati adamọ ti alaigbagbọ ni igbagbọ ninu rẹ mejeeji bukaata sí Ẹnití O da a.

Àwọn ooṣa ati àdánidá ko ni ìkápá lórí nǹkan kan nínú àlámọ̀rí wọn, wọn ko ni ìkápá láti darí àwọn omi ara ìsúnniṣe-nǹkan ti o wa nínú rẹ pẹ̀lú odiwọn ti o yani lẹ́nu yii, wọn o si ni ìkápá láti ṣe agbekalẹ àkójọ òfin apilẹ̀ àbùdá, èyí tí ó jẹ ọ̀kẹ́ àìmọye ìsọfúnni nínú gbogbo sẹẹli alàáyè, wọn si tun ni ìkápá lati jẹ́ kí nǹkan maa bẹ, kódà wọn ko le mu ara wọn maa bẹ.

Nitori naa Aṣẹda àgbáyé yii pẹlu awọn èèmọ inu rẹ yìí, Oun ni Aṣẹda Ọba ti O tobi Ọba Olùmọ̀ Ọba Olukapa Ọba Ọjọgbọn, mimọ ni fún Un.

Lẹyin naa tira pelebe yii maa ṣàlàyé àwọn iruju awọn alaigbagbọ ati igbiyanju wọn lori fífi ọgbọ́n àrékérekè tako awọn ẹri bíbẹ Aṣẹda eleyi ti o jẹ ti làákàyè àti adamọ.

Nínú awọn ọgbọ́n àrékérekè wọn ti o gbajumọ jù ni gbólóhùn wípé : "Íhàn ayé yìí pẹlu eesi ni", eleyii wáyé latari àìsí agbọye wọn tabi latari aimọkan wọn nipa ìpìlẹ̀ àwọn nǹkan ti o ṣee ṣe ki o ṣẹlẹ̀ ; nítorí pé èèsì ni majẹmu meji ti wọn kò le ya a silẹ láéláé.

Mejeeji naa ni : Igba ati ààyè.

Èèsì ṣe ìgbà ti oripa rẹ yoo wáyé nínú ẹ ni májẹ̀mú

O tun ṣe ààyè ti yoo ti maa ṣe àgbéjáde nǹkan ti o ba n ṣe nínú ẹ ni májẹ̀mú.

Bawo ni a ṣe maa wa sọ pe èèsì ni ipa nibi mímú ayé maa bẹ ti ó sì jẹ pe ayé wa yii wá lati ibi àìsí-ìgbà ati àìsí-àyè.

Lẹyin naa ni tira kekere naa n ṣe àfihàn awọn ẹri afilaakaye rọ lori pipọn dandan bibẹ ẹsin, ati itumọ ẹsin, ati pipọn dandan ijupajusẹ silẹ fun Ọlọhun Ọba gbogbo ẹda. Ijupajusẹ silẹ fun Ọlọhun ati titẹle E ni paapaa ẹsin.

O maa tẹriba fun Ọlọhun, o maa jọ́sìn fun Ẹni tí Ó dá ọ ti O si n pèsè ijẹ-imu fun ọ, ti O si tun n ṣe idẹra fun ọ, ti O si n fi ọ mọ ọ̀nà.

Ijọsin jẹ iwọ Ọlọrun lori awọn ẹrusin Rẹ ; nítorí pé Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga julọ ni O da wa, O si tun jẹ ki a maa wà láàyè, O ṣe ijẹ-imu fun wa, O fi ọna mọ wa, O si tun ran awọn ojisẹ Rẹ si wa ; lati fi yẹ̀ wá wò, ati lati fi gbidanwo wa pe ewo ninu wa ni ó dára julọ ni iṣẹ́, ìjọsìn ni iwọ Ọlọhun Ọba lori wa :

﴿ٱلَّذِى خَلَقَ ٱلْمَوْتَ وَٱلْحَيَوٰةَ لِيَبْلُوَكُمْ أَيُّكُمْ أَحْسَنُ عَمَلًا ۚ وَهُوَ ٱلْعَزِيزُ ٱلْغَفُورُ ﴿٢﴾﴾ [الملك: 2]

(Ẹni tí Ó dá ikú àti ìṣẹ̀mí nítorí kí ó lè dan yín wò ; èwo nínú yín l'ó máa ṣe iṣẹ́ rere jùlọ. Òun sì ni Alágbára, Aláforíjìn. {2}} [Suuratul Mulk.].

Lẹyin naa nibi ipele ti ó kàn, tira pelebe naa mu awọn ẹri lori ìní àlàáfíà Isilaamu, ati alaye wipe dajudaju Ọlọhun ko nii tẹwọ gba ẹsin kankan lọwọ eniyan yàtọ̀ sí Isilaamu, Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ bayii pe :

﴿وَمَن يَبْتَغِ غَيْرَ ٱلْإِسْلَٰمِ دِينًا فَلَن يُقْبَلَ مِنْهُ وَهُوَ فِى ٱلْءَاخِرَةِ مِنَ ٱلْخَٰسِرِينَ ﴿٨٥﴾﴾ [آل عمران: 85]

{Ẹnikẹ́ni tí ó bá wá ẹ̀sìn kan ṣe yàtọ̀ sí 'Isla-m, A ò níí gbà á lọ́wọ́ rẹ̀. Ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn, ó sì máa wà nínú àwọn ẹni òfò. {85}.} [Suuratul Al Imran.].

Isilaamu ni ẹsin ti Ọlọhun Ọba fi ran gbogbo awọn anọbi ati ojiṣẹ Rẹ.

Àmì ipilẹ fun Isilaamu ni pe: Ìtumọ̀ ijupajusẹ silẹ fun Ọlọhun ń bẹ nibẹ ati ijọsin fun Ọlọhun Ọba nìkan ṣoṣo.

Isilaamu nikan si ni ofin tó pé julọ, to n ṣeni lojukokoro lọ sí ibi ijupajusẹ silẹ fun Ọlọhun.

Oun nikan naa si ni ẹsin kan ṣoṣo ti n pepe lọ sí ibi imu Ọlọhun Ọba ni Ọkan ṣoṣo, iyẹn ni ijọkansoso ti gbogbo awọn Anọbi mú wá.

Gbogbo awon Anobi ni wọn n bẹ lori adisọkan imu Ọlọhun Oba ni Ọkan ṣoṣo, bo ti lẹ jẹ wipe awọn ofin wọn yatọ si ara wọn.

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿وَمَآ أَرۡسَلۡنَا مِن قَبۡلِكَ مِن رَّسُولٍ إِلَّا نُوحِيٓ إِلَيۡهِ أَنَّهُۥ لَآ إِلَٰهَ إِلَّآ أَنَا۠ فَٱعۡبُدُونِ﴿٢٥﴾﴾ [الأنبياء: 25]

(A kò rán òjíṣẹ́ kan níṣẹ́ ṣíwájú rẹ àfi kí A fi ìmísí ránṣẹ́ sí i pé: "Dájúdájú kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Èmi (Alla-hu). Nítorí náà, ẹ jọ́sìn fún Mi." {25}.} [Suuratul Anbiyaa].

Ẹṣin kankan ko waa sẹku ni oni lori imu Ọlọhun Oba ni Ọkan ṣoṣo yàtọ̀ si ẹsin Isilaamu, nígbà tó ṣe pé ipin kan ninu ẹbọ ti n bẹ fun gbogbo awọn ti wọn n ṣe afiti ara wọn si awọn ofin miiran, yala ipin kekere ni tabi pupọ. Léyìn ikú àwọn anọbi léyìn tí wọ́n ti fi àwọn èèyàn silẹ lórí imọ Ọlọhun lọkan, àwọn èèyàn bẹrẹ si nii ṣe ẹbọ nígbà tí ó yá, ẹsin Isilaamu nìkan ni o ṣẹku ni òní lori imọ Ọlọhun lọkan tí ó mọ́ ti àwọn anọbi mu wa.

Lẹyin naa, a maa pari tira pelebe yii pẹlu alaye bi ọmọniyan ṣe le di Mùsùlùmí ati itumọ Isilaamu ati pipọn dandan gbigba Isilaamu.

Isilaamu ti dahun si gbogbo awọn ibeere nipa bibẹ, èyí tí gbogbo awọn ọmọniyan maa n ronú nipa rẹ: (Lati ibo ni a ti wa, kí ni o ṣẹlẹ̀ ti a fi wa sinu aye yii, nibo si ni a n lọ?

Isilaamu si ti dahun si gbogbo eyi ninu aaya kan ṣoṣo ninu Alukuraani, Ọlọhun Oba wa sọ pé:

﴿وَمَالِيَ لَآ أَعۡبُدُ ٱلَّذِي فَطَرَنِي وَإِلَيۡهِ تُرۡجَعُونَ﴾ [يس: 22]

{Kí ni ó máa mú mi tí èmi kò fi níí jọ́sìn fún Ẹni tí Ó pilẹ̀ ẹ̀dá mi? Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni wọn yóò da yín padà sí. {22}}. [Suuratu Yaasin].

Lati ibo ni mo ti wá? Ọlọhun Oba ni O da mi.

Ati pe ibo ni mo n lọ? Maa si pada lọ si ọdọ Ọlọrun lati ṣe iṣiro iṣẹ mi (وَإِلَيْهِ تُرْجَعُونَ). Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni wọn yóò da yín padà sí.

Nítorí kí ni mo fi wa si ile-aye yii? Fun jijọsin fun Ọlọhun ati ki wọn le baa dan mi wo.

Nítorí kí ni maa fi maa jọsin fun Ọlọhun? Kii ṣe àjèjì ki n maa jọsin fun Ọlọhun ti O da mi, eleyii ni bi àjọṣe láàrin ẹru ati olowo rẹ ṣe ri: oun naa ni pe ki ẹru maa jọsin fun Olowo rẹ ati Adẹdaa rẹ:

﴿ٱتَّبِعُواْ مَن لَّا يَسۡـَٔلُكُمۡ أَجۡرٗا وَهُم مُّهۡتَدُونَ ۝٢١ وَمَالِيَ لَآ أَعۡبُدُ ٱلَّذِي فَطَرَنِي وَإِلَيۡهِ تُرۡجَعُونَ ۝٢٢ ءَأَتَّخِذُ مِن دُونِهِۦٓ ءَالِهَةً إِن يُرِدۡنِ ٱلرَّحۡمَٰنُ بِضُرّٖ لَّا تُغۡنِ عَنِّي شَفَٰعَتُهُمۡ شَيۡـٔٗا وَلَا يُنقِذُونِ ۝٢٣﴾ [يس:1

[23_2

({21} Kí ni ó máa mú mi tí èmi kò fi níí jọ́sìn fún Ẹni tí Ó pilẹ̀ ẹ̀dá mi? aaya kan ti o kó esi àwọn ìbéèrè mẹta ti o pàtàkì ju sínú, eyi ti o n ko ìdààmú ba èèyàn ﴿22﴾Kí ni ó máa mú mi tí èmi kò fi níí jọ́sìn fún Ẹni tí Ó pilẹ̀ ẹ̀dá mi? Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni wọn yóò da yín padà sí. {23} [Suuratu Yaasin?].

Isilaamu ni ofin Ọlọhun fun gbogbo aye

Isilaamu n túmọ̀ si pe ki ẹru ju ẹmi rẹ silẹ fun Ọlọhun, yoo si tẹriba fun Ọlọhun, yoo si gba A ni Oludari pẹlu mimaa tẹle aṣẹ Rẹ, yoo si tẹriba fun Aṣẹda rẹ ati Ọga rẹ.

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿۞ وَمَن يُسۡلِمۡ وَجۡهَهُۥٓ إِلَى ٱللَّهِ وَهُوَ مُحۡسِنٞ فَقَدِ ٱسۡتَمۡسَكَ بِٱلۡعُرۡوَةِ ٱلۡوُثۡقَىٰۗ وَإِلَى ٱللَّهِ عَٰقِبَةُ ٱلۡأُمُورِ٢٢﴾ [لقمان: 22]

{Ẹnikẹ́ni tí ó bá jura rẹ̀ sílẹ̀ fún Alla-hu, tí ó jẹ́ olùṣe-rere, dájúdájú onítọ̀un ti dìrọ̀ mọ́ okùn t'ó fọkàn balẹ̀ jùlọ. {22}}. [Suuratu LuqmaanI.].

Silaamu n túmọ̀ si jijẹ ẹrusin fun Ọlọhun nibi gbogbo nnkan ti o kere ati eyi ti o tobi ninu isẹmi rẹ, Ọlọhun ti O ga sọ pe :

﴿قُلْ إِنَّ صَلَاتِي وَنُسُكِي وَمَحْيَايَ وَمَمَاتِي لِلَّهِ رَبِّ ٱلْعَٰلَمِينَ ١٦٢ لَا شَرِيكَ لَهُۥ وَبِذَٰلِكَ أُمِرْتُ وَأَنَا۠ أَوَّلُ ٱلْمُسْلِمِينَ ١٦٣﴾ [الأنعام: 162-163]

{Sọ pé: "Dájúdájú ìrun mi, ẹran (pípa) mi, ìṣẹ̀mí ayé mi àti ikú mi ń jẹ́ ti Alla-hu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá. {162} Kò sí akẹgbẹ́ fún Un. Ìyẹn ni Wọ́n pa láṣẹ fún mi. Èmi sì ni ẹni-àkọ́kọ́ àwọn mùsùlùmí (ní àsìkò tèmi)." {163}.}. [Suuratul An'aam].

Ìrun mi, ẹran (pípa) mi, ìṣẹ̀mí ayé mi àti ikú mi ń jẹ́ ti Allāhu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá: Gbogbo nnkan ti mo n ṣe, torí Ọlọhun ni, mo n kirun nitori Ọlọhun, mo n tẹle awọn obi mi mejeeji nitori Ọlọhun, mo n ṣe atunyẹwo ẹ̀kọ́, mo si tun n kọ ọ lati le baa fi ṣe awọn eeyan ni anfaani nitori Ọlọhun, mo si maa n sun lati le baa ni agbara lati le baa fi ṣe nnkan ti Ọlọhun pa mi laṣẹ rẹ.

Oun ni jijẹ ẹrusin fun Ọlọhun nibi gbogbo iṣẹ, eleyii si wa ninu awọn àmì ijupajusẹ silẹ fun Ọlọhun ti o pàtàkì jù lọ.

Ebi ti ìmọ̀... Fifi ebi panu lati le baa fi mọ ohun ti o pataki jù ninu ohun ti yoo ko airoju ba wa, ko si nnkan ti o le yo o ayafi Isilaamu...

Ṣùgbọ́n aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun, kò leè tó ọmọniyan tí ó mọ̀ pé wọn bí òun ki òun le kú ni.

Tira kékeré naa dà gẹ́gẹ́ bíi oúnjẹ ti ìmọ̀ ati ti làákàyè nibi ìṣòro aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun, àti àwọn itọka sí ìní àlàáfíà ẹsin Isilaamu.

Oúnjẹ náà wá ni ọna ìbéèrè ati ìdáhùn...

Ẹ jẹ́ kí á bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú ìbùkún Ọlọhun.

Kí ni itumọ “IL’HAAD”?

Esi: Il’haad naa ni: kikọ láti gbagbọ nínú èyíkéyìí agbára ti a o lè fi ojú rí

Ẹni o ba jẹ Mul’hidu maa tako bibẹ Adẹdaa ati jijẹ Anabi ati igbende.

2- Kini nkan eleyi ti ẹ n ko aleebu ba lori àìní ìgbàgbọ́ ninu Ọlọhun?”

“Àìní ìgbàgbọ́ ninu bibẹ Ọlọhun maa n bere fun igbagbọ kan to ga lọpọlọpọ ju igbagbo ti ẹsin lọ.”

Ṣùgbọ́n ìgbàgbọ́ kan ni ti a mọ lori àròsínú irokuro àti àwọn èrò èké, yàtọ̀ sí ìgbàgbọ́ ti ẹsin ti a mọ lori òtítọ́ ti o hàn kedere ti o jẹ ti àdámọ́, ati awọn nǹkan ti ó dájú ti a n fi ojú ara wa rí, ati awọn nǹkan ti o kọ́kọ́ maa n wa si làákàyè, ati awọn ẹ̀rí ti o ba òfin mu.

Lati le di alaigbagbọ ninu Ọlọhun, o ni lati fi ojú inú wo àwọn nǹkan ti o n bọ yii: A- Ko si ohun kankan darapọ mọ ko si ohun kankan, o ba di nǹkan ńlá… o di agbaye ìyàlẹ́nu ninu awọn nǹkan ti o rẹwà julọ, pẹ̀lú ìgbéléwọ̀n ti o pé gan, ati awọn ààlà ti o fún pinpin. Èèsì ni o ṣe àgbéjáde àwọn ààlà ti o fun pinpin ati awọn ohun ti ko ṣeé yí padà nínú ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ physics ti ayé mú wá, ti o si jẹ pe májẹ̀mú èèsì méjèèjì naa ni ààyè ati ìgbà, ayé ko ni ààyè ko si ni ìgbà, a jẹ́ pé ko ṣèèsì. Ki nǹkan ṣẹlẹ̀ láìmọ ìdí rẹ̀, ati àyíká ilẹ̀ àkọ́kọ́ ni o ṣe àgbéjáde iṣẹmi aye, o si dá kòkòrò àrùn àti ọmọniyan, ti ọpọlọ ẹda abara wa ni téńté agbára rẹ̀ bayii, ko ni ìkápá láti ṣe àgbéjáde ọ̀nà iṣẹmi ayé ti o rọrùn jù. Gbogbo àwọn ìlànà ìwà híhù ti a gbà pé o dára, èyí tí ọ̀pọ̀lọpọ̀ rẹ n tọ ojú òpó ti o tako nǹkan ti ayé pátápátá, àwọn ìwà ìpìlẹ̀ jẹ́ ẹrù tí ó jẹ ti ayé, o si tun jẹ́ òfò- ní ìbámu pẹ̀lú anfaani ti ayé- o wà lára ìsọfúnni nǹkan ti ayé naa ati ohun ti o jáde latara rẹ. O gbọdọ̀ ni ìgbàgbọ́ ninu awọn nǹkan ti ko rọrùn ninu làákàyè yii ki o too bẹ̀rẹ̀ si nii ṣe aigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun.

5- Ko si nnkan ti a le gbára le ti àfòyemọ̀ tàbí ti àfojúrí ninu àìní ìgbàgbọ́ nínú bibẹ Ọlọhun ti o le kọ lati ma pa àwọn ará orí ilẹ̀ pátápátá run.

Ile ayé ko mọ ohun tí kò tọ́, ko si mọ nǹkan tí o tọ́.

Ti o ba ri bẹẹ, ko si iyatọ láàrin pípa àwọn ará orí ilẹ̀ run ati dídá wọn sí ni ti aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun.

“Torí náà, a mọ aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun pa lori igbagbọ, sugbọn ìgbàgbọ́ kan ni ti ko ni oripa ninu imọ tabi ẹgbawa tabi laakaye tabi iwa. “

“Kini ẹri naa to wa lori bibẹ Ọba Adẹdaa?”

Esi: “Awọn ẹri pọ sugbọn a maa gba tito pẹlu ẹri meji:”

“1- Ẹri imu nkan maa bẹ.”

“2- Ẹri iko akolekan ati ṣíṣe nǹkan dáadáa.”

”3- Kini itumọ ẹri imu nkan maa bẹ?”

“4-Ẹri imu nkan maa bẹ n tumọ si:”

“Gbogbo nkan ti n bẹ lẹyin igba ti ko si tẹ́lẹ̀, ko si ibuyẹ ti ko fi nii ni ẹniti o n mu u bẹ. “

” Pẹlu iyẹn, nkan ti ko ni onka lo wa pẹlu wa ninu awọn ẹri lori bibẹ Ọba Adẹdaa, mimọ ni fun Un. “

” Gbogbo átọ̀mù to wa ninu aye o jẹ ẹri lori dida, nigba to ṣe pe gbogbo nkan ti n bẹ naa jẹ ẹri lori Ọba Adẹdaa ti O mu nkan maa bẹ. “

Tí o ba wo ayé yii, yóò hàn sí ọ pé nǹkan ti o ṣẹ́rí wá ti o n yí padà ni, kii ṣe nǹkan ti kò ní òpin tàbí tí ko ni ìbẹ̀rẹ̀, nípa bẹ́ẹ̀, kii ṣe nǹkan ti o le dá dúró fúnra rẹ. Eléyìí maa jẹ ki o da ọ lójú nínú làákàyè rẹ pe ó ní ẹni tí ó dá a, nípa bẹ́ẹ̀, ti o ba ti n wo ayé ni waa maa wo ẹni ti o dá ayé naa latara rẹ̀.

Fun ìdí yẹn, àwọn aaya pọ ti n ṣiju wa si ayé ati awọn nǹkan ti n bẹ ni àyíká wa, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿قُلِ ٱنظُرُواْ مَاذَا فِي ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِۚ وَمَا تُغۡنِي ٱلۡأٓيَٰتُ وَٱلنُّذُرُ عَن قَوۡمٖ لَّا يُؤۡمِنُونَ ١٠١﴾ [يونس: 101]

(Sọ pé : "Ẹ wòye sí n-ǹkan tí ń bẹ nínú sánmọ̀ àti ilẹ̀. Àwọn a-yah àti ìkìlọ̀ kò sì níí rọ ìjọ aláìgbàgbọ́ lọ́rọ̀." {101}.} [Suuratu Yûnus].

Allah tun sọ pe :

﴿أَوَلَمۡ يَتَفَكَّرُواْ فِيٓ أَنفُسِهِمۗ مَّا خَلَقَ ٱللَّهُ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضَ وَمَا بَيۡنَهُمَآ إِلَّا بِٱلۡحَقِّ وَأَجَلٖ مُّسَمّٗىۗ وَإِنَّ كَثِيرٗا مِّنَ ٱلنَّاسِ بِلِقَآيِٕ رَبِّهِمۡ لَكَٰفِرُونَ ٨﴾ [الروم: 8]

{Ṣé wọn kò ronú nípa ọ̀rọ̀ ara wọn ni ? Alla-hu kò ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀, ilẹ̀ àti n-ǹkan t'ó wà láàrin àwọn méjèèjì bí kò ṣe pẹ̀lú òdodo àti fún gbèdéke àkókò kan. Dájúdájú ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ nínú àwọn èniyàn mà ni aláìgbàgbọ́ nínú ìpàdé Olúwa wọn.} [8].} [Suuratur Rûm].

Allah tun sọ pe:

﴿أَوَلَمۡ يَنظُرُواْ فِي مَلَكُوتِ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِ وَمَا خَلَقَ ٱللَّهُ مِن شَيۡءٖ وَأَنۡ عَسَىٰٓ أَن يَكُونَ قَدِ ٱقۡتَرَبَ أَجَلُهُمۡۖ فَبِأَيِّ حَدِيثِۭ بَعۡدَهُۥ يُؤۡمِنُونَ ١٨٥﴾ [الأعراف: 185]

{ ﴿Ṣé wọn kò wo ìjọba àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ pẹ̀lú gbogbo n-ǹkan tí Alla-hu dá? {185}}. [ Suuratul A'raf?].

Gbogbo nnkan ti a dá n jẹ ẹri tààrà lórí bibẹ ẹni ti o da nnkan náà.

Kini itumọ ẹri akolekan ati ṣíṣe dáadáa

Esi: Ẹri imu nkan maa bẹ n tumọ si:"

Gbogbo nnkan ti n bẹ pata, bíi àwọn QUARK- oun naa ni nnkan tí ó ní ara ti o kéré jù tí a ṣe àkíyèsí rẹ̀ ti o jọ atomiiki- titi dé orí àwọn ìṣùpọ̀ irawọ ti o ní iṣẹ́ tí ó díjú

Ìtumọ̀ ni pe o ni iṣẹ́ kan pàtó tí ó ń ṣe.

Gbogbo iṣẹ́ ti o díjú ninu iṣẹda jẹ ipò kan ti ó ju bíbẹ lásán lọ

Bíbẹ ní ipele

Didiju ninu nnkan ti n bẹ jẹ́ ipele ti o ju bíbẹ lásán lọ

Gbogbo nnkan ti o wa ni àyíká rẹ ni a ṣẹda ni ọna kan pàtó láti maa ṣiṣẹ́ kan pato.

Ti o ba ri bẹ́ẹ̀, gbogbo nǹkan ti n bẹ ni àyíká rẹ ni o ní iṣẹ́ tí ó díjú"

Iṣẹ́ ti o diju sì jẹ́ ẹri ṣíṣe nǹkan ati mímú nǹkan maa bẹ

Ti o ba ri bẹ́ẹ̀, ẹni ti o n mú nǹkan maa bẹ náà gbọdọ̀ máa bẹ

Àpèjúwe ìyẹn ni “Àtùpà”: Eléyìí n ṣe àpèjúwe iṣẹ́ ti o díjú.

Àtùpà n kójọ latara

Òwú fitílà

Wáyà latara òjé: O maa mú iná dé ara òwú fitílà

Gaasi ti kò ṣiṣẹ́: O maa da àábò bo òwú fitílà naa ti ko si nii sí ibaṣepọ pẹ̀lú ẹ, bẹ́ẹ̀ ko si tun nii sí ibaṣepọ pẹ̀lú iná.

Ìgò: Kò nii jẹ ki atẹ́gùn wọlé tabi ki gaasi ti ko ṣiṣẹ́ jáde, bibẹẹkọ òwú fitílà náà kì bá jóná.

Ìsàlẹ̀ àtùpà: O maa so àtùpà papọ mọ DIWAAYAH, o maa wa jẹ ọ̀nà fun iná mọnamọna

Àtùpà yii jẹ ètò kan tí ó díjú tí kò rọrùn láti jẹ kí ó má díjú, ti o bá rí bẹ́ẹ̀, ẹ̀rí làákàyè àkọ́kọ́ wà nibẹ ti o n ṣe anfaani iṣẹ́ tí wọ́n ṣe dáadáa

Eeyan ti o ba n tako iṣẹ́ ti wọn ṣe dáadáa yii nipa àtùpà, tabi o n lérò o ṣèèṣì hàn ni, òun ni a maa ni ki ó ẹ̀rí wá lórí ìyẹn

Ẹni ti o ṣe àtùpà mọ itumọ iná ati awọn ọ̀nà rẹ, ati àǹfàání àtùpà, àti pàtàkì fìtílà, fun ìdí yẹn, bibẹ àtùpà jẹ ẹri tààrà lórí pe ó ní ẹni ti o ṣe é dáadáa, kii kan ṣe pe o kan ṣàdédé wà torí pé àwọn àtùpà n bẹ tí wọ́n yàtọ̀ sí i gedegbe nibi ìrísí rẹ.

Pẹ̀lú irú ipò mímú ẹri làákàyè wa yii, a maa ri i pe nǹkan ti iṣẹ́ rẹ bá díjú gẹ́gẹ́ bíi ọmọniyan, o ní ẹni tí o n mú u bẹ tí ó sì ṣe é

Àtùpà maa n kójọ latara ẹ̀yà márùn-ún

Nígbà tí ọmọniyan sì kojọ latara biliọnu mẹẹrin ẹ̀yà nínú gbogbo sẹẹli kọọkan nínú àwọn sẹẹli rẹ

Ẹ̀yà biliọnu mẹẹrin “lẹta” ni wọn ya àwòrán àwọn iṣẹ́ ẹda alàáyè, òun ni a n pe ni: Koodu, DNA yii tabi jiini yii, tabi awọn lẹta yii maa n fara pamọ́ sínú átọ̀mù sẹẹli kọọkan nínú àwọn sẹẹli rẹ.

Ti o ba lero pe awọn ẹ̀yà maraarun ti wọn jé ti àtùpà ni ẹniti o ṣe wọn, ti iwọ ko si ni ẹniti o ṣe ọ, wahala tirẹ ni eleyii jẹ.:

﴿أَمۡ خُلِقُواْ مِنۡ غَيۡرِ شَيۡءٍ أَمۡ هُمُ ٱلۡخَٰلِقُونَ ٣٥﴾ [الطور: 35]

{Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá ? Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni ? {35}} [Sūratu Tūr ?].

Gbogbo nnkan ti n bẹ ni àyíká rẹ ni ó díjú, ko si nǹkan kan nínú àdánidá tabi átọ̀mù, tabi nínú òpópónà róbótó ti sánmà tabi nínú ara rẹ láìsí iṣẹ́ dídíjú kankan nínú ẹ rárá

Iṣẹ́ dídíjú ati iṣẹ ti n bẹ fún gbogbo átọ̀mù kọ̀ọ̀kan ati gbogbo nǹkan ti o ba ti ni ara kékeré naa ni àwọn nǹkan ti n bẹ nínú gbogbo nǹkan nínú ayé

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe :

﴿ٱلَّذِينَ ءَاتَيْنَٰهُمُ ٱلْكِتَٰبَ يَعْرِفُونَهُۥ كَمَا يَعْرِفُونَ أَبْنَآءَهُمْ ۖ وَإِنَّ فَرِيقًا مِّنْهُمْ لَيَكْتُمُونَ ٱلْحَقَّ وَهُمْ يَعْلَمُونَ ١٤٦﴾ [البقرة: 146]

{ Dájúdájú àwọn àmì wà nínú ìṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀, ìtẹ̀léntẹ̀lé àti ìyàtọ̀ òru àti ọ̀sán, àti àwọn ọkọ̀ ojú-omi t'ó ń rìn lórí omi pẹ̀lú (ríru) ohun t'ó ń ṣe àwọn ènìyàn ní àǹfààní, àti ohun tí Allahu ń sọ̀kalẹ̀ ní omi òjò láti sánmọ̀, tí Ó sì ń fi sọ ilẹ̀ di àyè lẹ́yìn tí ó ti kú, àti (bí) Ó ṣe fọ́n gbogbo ẹranko ká sí orí ilẹ̀, àti ìyípadà atẹ́gùn àti ẹ̀ṣújò tí A tẹ̀ba láààrin sánmọ̀ àti ilẹ̀; (àmì wà nínú wọn) fún ìjọ t'ó ń ṣe làákàyè. {164}}. [Suuratul Baqarah].

Awọn aaya lori rẹ si pọ gan

Ko si ẹniti o le maa ranti rẹ ayafi ẹniti ba maa n lo laakaye rẹ:

﴿هُوَ ٱلَّذِيٓ أَنزَلَ عَلَيۡكَ ٱلۡكِتَٰبَ مِنۡهُ ءَايَٰتٞ مُّحۡكَمَٰتٌ هُنَّ أُمُّ ٱلۡكِتَٰبِ وَأُخَرُ مُتَشَٰبِهَٰتٞۖ فَأَمَّا ٱلَّذِينَ فِي قُلُوبِهِمۡ زَيۡغٞ فَيَتَّبِعُونَ مَا تَشَٰبَهَ مِنۡهُ ٱبۡتِغَآءَ ٱلۡفِتۡنَةِ وَٱبۡتِغَآءَ تَأۡوِيلِهِۦۖ وَمَا يَعۡلَمُ تَأۡوِيلَهُۥٓ إِلَّا ٱللَّهُۗ وَٱلرَّٰسِخُونَ فِي ٱلۡعِلۡمِ يَقُولُونَ ءَامَنَّا بِهِۦ كُلّٞ مِّنۡ عِندِ رَبِّنَاۗ وَمَا يَذَّكَّرُ إِلَّآ أُوْلُواْ ٱلۡأَلۡبَٰبِ٧﴾ [آل عمران: 7]

{Kò sí ẹni t'ó ń lo ìrántí àyàfi àwọn onílàákàyè. {7}.}. [Suuratul Al Imran].

Ẹniti o ba lo laakaye rẹ, ti o si woye si aye (ẹri mimu nnkan bẹ) ti o si tun woye si ìdarí ati iṣẹ àwọn nǹkan ti n bẹ (itọka nini akolekan ati ṣíṣe nǹkan dáadáa) yoo maa sọ pẹ̀lú amọdaju pe itọka ẹni tí n mu nǹkan maa bẹ bá làákàyè mu.

Ki ni o de ti ìpìlẹ̀ ọmọniyan ati nǹkan ti o yatọ si i nínú àwọn ẹ̀dá alàáyè kò fi lè jẹ àwọn nǹkan àkọ́kọ́ ti o kọkọ n bẹ ti wọn ò díjú rárá

Esi: Awọn nnkan iruju meji n bẹ nibi yii:

Nnkan iruju akọkọ naa ni: ko si ẹri kankan ti a le rí lori kikuro iran kan ninu awọn nnkan ti nbẹ laaye ninu aye lọ si iran miran, ki a ma i tii sọ nípa ìlọsókè ti àròsínú ti n dẹru bani yii pé ọmọniyan wá latara àwọn ohun abẹmi tin-n-tin àkọ́kọ́

Báwo ni alaigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun ṣe maa ni igbagbọ nínú àròsínú ti ko ní ẹ̀rí tàárà yii, tí ó sì ń takò wá lórí ẹ̀rí ti o ba làákàyè àti ẹ̀sìn mu?

Nnkan iruju ẹlẹẹkeji: Ni ìbámu sí àbá-èrò-orí apilẹ̀ àbùdá ti o kéré jù, kò rọrùn kí ẹda alàáyè kankan- bi o ti wu ki o rọrùn tó- o kéré ju 200 apilẹ̀ àbùdá lọ.

Apilẹ̀ àbùdá ti o kéré jù náà ni odiwọn ti o kéré jù nínú apilẹ̀ àbùdá ti ẹ̀dá alàáyè kankan kò leè ṣẹ̀mí láìsí i

Ẹda alaaye kankan o le maa bẹ ti o ba jẹ pe onka jiini rẹ ba kere si aala jiini ti o kéré jù tii ṣe odiwọn jiini kan

JIINI ni téèpù ti o jẹ ti ìsọfúnni ti o kó ọ̀pọ̀lọpọ̀ àkójọ òfin apilẹ̀ àbùdá sínú, èyí tí n fi ìsọfúnni pàrokò

Ààlà ti o kéré jù n bẹ fun àwọn jiini ti o jẹ kòṣeémánìí fun iṣẹmi, ni ọna ti o ṣe pe àkójọ àwọn jiini kan maa fi agbára pàrokò; torí pé ko si iṣẹmi fun ẹ̀dá alààyè kankan láìsí agbára, àkójọ àwọn jiini mìíràn si maa fi oúnjẹ pàrokò, ti àwọn mìíràn maa fi lilekun si i pàrokò, ti àwọn mìíràn maa fi àwọn iṣẹ́ ìpìlẹ̀ fun iṣẹmi pàrokò, báyìí ni o ṣe maa rí lọ

Àwọn onímímọ̀ ṣe ìṣirò ààlà ti o kere jù ninu awọn apilẹ̀ àbùdá ti wọn jẹ kòṣeémànì fun isẹmi, wọn wa pinnu pe ko rọrùn ki o kéré sí ọgọ́rùn-ún méjì apilẹ àbùdá.

Àjọ Craig Venter gbà pe ààlà ti o kéré jù nínú àwọn apilẹ̀ àbùdá kò le kéré si ọgọ́rùn-ún mẹta ati méjì lé ní ọgọrin apilẹ àbùdá. [1]

Àwọn onímọ̀ sáyẹ́ǹsì ti rí I pé Mycoplasma, tó jẹ́ ẹ̀dá alààyè tó wẹ́ jù lọ tó ti wà lórí ilẹ̀ ayé rí, ó ní àwọn apilẹ̀ àbùdá 468

Ti ọ̀rọ̀ náà bá jẹ́ ohun èlò nikan, ti agbaye sì jẹ́ eto ti ara nikan, a nilo lati bẹrẹ lati apilẹ àbùdá òdo, ti a ba fẹ lati kọja lati hydrogen si eniyan!

Ṣugbọn imọ-jinlẹ sọ fun wa pe ko si nkan to n jẹ Jiini òdo, tabi jiini ẹyọkan, tabi ọgọ́rùn-ún, imọ-jinlẹ sọ pe: O kéré jù, a nilo akojọpọ alaye nla kan, bibẹẹkọ ẹda alààyè kì bá tí farahan lati ibẹrẹ.

Ko si ohun àtijọ́ ni ìṣẹ̀dá, ṣugbọn gbogbo eto kọọkan bẹrẹ pẹlu èèmọ̀ tí ó dá dúró lọ́tọ̀!

Èèmọ̀ náà yoo maa wà ninu eto àlàyé ti o fi koodu si awọn nǹkan ti n bẹ ṣaaju ki wọn o tó hàn. Èèmọ̀ yìí yóò máa jẹ́ òkúta ìkọ̀sẹ̀ nígbà gbogbo

[1] J. Craig Venter Institute (JCVI) ṣe iwadii kan lati wa gbogbo awọn apilẹ àbùdá pataki ti M. genitalium nipasẹ transposon mutagenesis agbaye. Abajade wọn rii pe 382 ninu 482 awọn ìṣètò apilẹ àbùdá amuaradagba jẹ pataki. “

ní ojú àìgbàgbọ́-nínú-wíwà-Ọlọ́run, òkúta ìkọ̀sẹ̀ ní ojú àwọn tí wọ́n tako ìṣẹ̀dá àtọ̀runwá!

O ni awọn ìsọfúnni biliọnu mẹrin, àwọn ìsọfúnni yẹn ti o wa ninu átọ̀mù sẹẹli kọọkan- nínú àwọn sẹẹli rẹ- lati ṣe awọn iṣẹ pataki to peye.

Alaigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun naa n ronu pe awọn ẹda wa ti o bẹrẹ lati jiini òdo, ṣugbọn ẹkọ ti awọn Jiini ti o kere julọ wa lati pa àlá yii rẹ́.

Àwọn ẹ̀dá alàáyè hàn lẹniti iṣẹ́ wọn díjú láti ìgbà àkọ́kọ́, bibẹẹkọ wọn kò bá tí hàn rárá.

7- Kini àwọn àpèjúwe fún ẹri akolekan àti ṣíṣe dáadáa?

Esi: Àwọn àpèjúwe náà kò ní onka.

kódà àwọn ìwé orí ilẹ̀ ko lè gbà wọn tan:

﴿وَلَوۡ أَنَّمَا فِي ٱلۡأَرۡضِ مِن شَجَرَةٍ أَقۡلَٰمٞ وَٱلۡبَحۡرُ يَمُدُّهُۥ مِنۢ بَعۡدِهِۦ سَبۡعَةُ أَبۡحُرٖ مَّا نَفِدَتۡ كَلِمَٰتُ ٱللَّهِۚ إِنَّ ٱللَّهَ عَزِيزٌ حَكِيمٞ ﴿٢٧﴾﴾ [لقمان: 27]

{Tí ó bá jẹ́ pé kìkìdá ohun t'ó ń bẹ lórí ilẹ̀ ní igi ni gègé ìkọ̀wé, kí agbami odò jẹ́ tàdáà rẹ̀, agbami odò méje (tún wà) lẹ́yìn rẹ̀ (t'ó máa kún un), àwọn ọ̀rọ̀ Alla-hu kò níí tán (lẹ́yìn tí àwọn n-ǹkan ìkọ̀wé wọ̀nyí bá tán nílẹ̀). Dájúdájú Alla-hu ni Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. {27}.} [Suuratu Luqmaan].

Gbogbo átọ̀mù ti n bẹ ni àgbáyé n tọ́ka si akolekan, a mọ̀ ni òní, tàbí a ṣi maa mọ òtítọ́ yìí ní ọ̀la.

1- Insulin- omi ara ìsúnniṣe-nǹkan ti a fi n jẹ kí gúlúkóòsì ó dà- pancreas ni o maa n mú u jáde ní odiwọn ṣuga tí o bá jẹ.

2- Agbára ọkàn láti máa tu ẹ̀jẹ̀ jáde maa ṣe déédéé pẹ̀lú agbára ti àwọn iṣan n bùkátà si ni ìbámu si igbiyanju ti a gbà

3- Àwọn ìdérí ikùn rẹ ki oúnjẹ ma baa padà sí ẹnu rẹ ki o ma baa kó sùtá kàn ọ́

4- Àwọn túùbù ìgbé-nǹkan-jáde ki sùtá ma baa ṣe àwọn aṣọ rẹ ni gbogbo ìgbà.

5- Àwọn egungun agbárí rẹ kìí dàpọ̀ títí tí waa fi jáde kúrò nínú ìyá rẹ ni àlàáfíà àti ní irọrun ; torí pé ti wọn bá dàpọ̀ ni, oò bá tí jáde kuro ninu ìyá rẹ àyàfi ti àwọn egungun naa bá tó rún, idagbasoke rẹ̀ ko si le parí títí ti idagbasoke ọpọlọ rẹ yóò fi parí.

6- Gbogbo òpó iṣan rẹ ti n gbe àmì ti iná mànàmáná tí a bò pẹ̀lú ìpele tí ó máa n gba ooru sára- gẹ́gẹ́ bí a ṣe n ṣe nsinyii pẹ̀lú àwọn wáyà iná- ki awọn àmì ti mànàmáná ma baa fọ́nká, tàbí ráre, tàbí ki o fa ìdíwọ́ fún ọ

7- Electron maa n yí ní ẹgbẹẹgbẹ nucleus pẹ̀lú ìyára ti ẹgbẹ̀rún kìlómítà fún iṣẹju àáyá kan, bibẹẹkọ ìbá jábọ́ sínú nucleus pẹ̀lú agbára ìfàmọ́ra ti n bẹ fún positive nucleus, ayé gan ìbá ti wó ṣáájú ki ó tó bẹ̀rẹ̀, èyí ni ìyára ti o dára jùlọ láti di átọ̀mù.

8- Nígbà tí átọ̀mù ti hydrogen méjì bá dàpọ̀, 0.007% ninu ìṣùpọ̀ hydrogen máa yí padà sí agbára. Ti ìṣùpọ̀ yii ba jẹ 0.006% rọ́pò 0.007%, dájúdájú proton ko lè dàpọ̀ mọ́ neutron, ayé kì bá kàn wà ní hydrogen nìkan. Àwọn èròjà tí ó kù kì bá tí hàn, ti iṣupọ ti o di agbára naa ba jẹ 0.008% rọ́pò 0.007% ìdàpọ̀ náà ìbá di nǹkan tí ó yára gan, èyí ti o maa mu ki hydrogen kúrò ní àgbáyé lẹsẹkẹsẹ, tí ayé kò sì nii ṣe é gbé pẹ̀lú ẹ. Nọmba naa gbọdọ wa laarin 0.006% ati 0.008%.

9- Isupọ electron ko 0.2% ninu isupọ neutron, eleyii ni isupọ ti ipò rẹ ga julọ fún kíkó átọ̀mù jọ".

10- Lẹhin ti irúgbìn ba ti wù jade, awọn ìrudi náà a maa lọ taara si orisun imọlẹ ti awọn gbongbo o sí máa lọ si isalẹ, ni ibi tí awọn ìrudi naa

ti maa kọ imọlẹ, ati pe gbogbo ìsọfúnni ti wọn nilo lati ṣe iṣẹ wọn ni o n bẹ ninu irugbin bí ẹnà, ati pe awọn omi ìsúnniṣe-nǹkan wa ti o n ṣakoso igberu lókè ati ní ẹgbẹ fún irúgbìn, ti o si tun n ṣàkóso idajukọ awọn gbongbo, gbogbo rẹ bakanna wọn ti koodu wọn sínú irugbin naa. "

11- Laarin igba ti o ba n jẹ èso tí ó dun lẹyin naa ti o wa ju koro ti o gbẹ ti ko ni itọwo sọnu, iwọ n jẹ ki eso yẹn gbe àwọn apilẹ̀ àbùdá rẹ kọjá lọ si ibi ti eso naa ti maa fun ẹ ni itọwo didùn ni akoko ti o n fi awọn apilẹ̀ àbùdá rẹ pamọ - ipilẹṣẹ igbesi aye rẹ - si àárín kóró gbígbẹ ti n dán ti kò wù ọ́, kí lo ju kóró yii silẹ sí, ti àyíká ipò tí ó yẹ ba ti wà, yio bẹrẹ si nii máa di igi èso pẹlu awọn nkan ti o wa lara rẹ bi ẹka ati gbongbo, gbogbo eleyii n ṣẹlẹ sí àwọn irúgbìn ti ko mọ nkankan.

12- Tani o darí ìsọfúnni naa fun eso ti ko le sọ ti ko sì gbọ, ti o tun darí iwọn ṣuga ti o wa ninu rẹ lọ́nà tí yíò fi wù ọ́ ?

Lẹyin naa : Ta ni ó sọ irúgbìn náà di aláìtẹ́wọ́gbà tí kò sì lọ lẹ́nu rẹ, ti o fi kọ̀ ọ́ sílẹ̀ tí ó sì sọ ọ́ nù ?

Lẹyin naa : Ta ni ẹnití o jẹ ki kóró kún fún ìsọfúnni ti apilẹ àbùdá ti o tó lati ṣẹda irúgbìn titun pẹlu gbogbo awọn alaye rẹ ati awọn iṣẹ rẹ ?

13- O hàn sí wa ni igbẹhin pé dajudaju : Ìmẹ́lẹ́ ati dídúró sójú kan ti n ṣe wá, okùnfà rẹ ni ìṣùpọ̀ ayé lódindi.

Kí ní ìtumọ : Al-Qusūru adhāti ?

Ka ni pe o n wa ọkọ, lojiji ni ọkọ ba dúró, ki ni nkan ti yíò ṣẹlẹ ?

Wa a lọ sí iwájú ! Àbí bẹẹ kọ ?

Eleyii ni wọn n pé ni Al-atālah tabi al-Qusūru adhāti (dídúró sójú kan).

Ka ni wipe Al-Qusūru adhāti (ai le ṣe nkankan fúnra ẹni) ninu àgbáyé wa ba kere ju bi o ṣe wa nsinyi lọ ni, atẹgun to kere jù kò bá kapa lati gbé

àpáta, atipe ninu àgbáyé ti o da bii eleyii a o maa ri ikọlu gbogbo awọn orísịrísị nkan ni gbogbo ìgbà.

Atipe ka ni Atālah (ai le ṣe nkankan) ba tobi ju bi o ṣe wa lọ ni, ao ba ti ni ìkápá gbigbe awọn ọmọnika wa.[2]

Atipe Qusūru adhāti tabi Atālah (ai le ṣe nkankan tabi ai le yi pada) dúró lori kutlah (isupọ - mass).

Ati pe àlámọrí ti o ya awọn oni ìmọ̀ fisiksi lẹnu ni pé isupọ irawọ milky way, irawọ ti o kó oòrùn sínú kii ko ipa nibi didari Atālah (ai le ṣe nkankan) ayaafi pẹlu odiwọn 0.1 ninu miliọnu, nigbati ìṣùpọ̀ ilẹ naa kii darí Atālah (ai le ṣe nkankan) àyàfi pẹlu odiwọn 0.001 ninu miliọnu.

Nitori naa Atālah ti o dára ti a lè wò kọ́ṣe ti a n sẹmi lori èso rẹ, ti o si jẹ wipe latari rẹ ni a fi n ṣe gbogbo awọn eto wa, oun ni abajade àpapọ̀ agbara ayé lódindi :

﴿وَمَا خَلَقۡنَا ٱلسَّمَآءَ وَٱلۡأَرۡضَ وَمَا بَيۡنَهُمَا بَٰطِلٗاۚ ذَٰلِكَ ظَنُّ ٱلَّذِينَ كَفَرُواْۚ فَوَيۡلٞ لِّلَّذِينَ كَفَرُواْ مِنَ ٱلنَّارِ ٢٧﴾ [ص: 27]

{A kò ṣẹ̀dá sánmọ̀, ilẹ̀ àti ohunkóhun t’ó wà láàrin méjèèjì pẹ̀lú irọ́. (Irọ́), iyẹn ni èrò àwọn t’ó ṣàì gbàgbọ́. Nítorí náà, ègbé ni fún àwọn t’ó ṣàì gbàgbọ́ nínú Iná. {27}.} Sūratu Sād.

Atipe gbogbo ìgbà tí imọ ba ti n fẹ'ju, awọn eemọ ọgbọn àti àwọn kúlẹ̀kúlẹ̀ dídá ẹda máa n fi ojú hàn.[3]

---

2 Ayanmọ Adamọ: Bi awọn ofin biology ṣe ṣafihan idi ti a fi wáyé, Michael Denton.

3 Mickeal Denton ṣàlàyé ọrọ yii pẹlu àlàyé to kun ninu tira rẹ : "Qadru at-Tobī‘ah, wọn tú tira naa sí èdè mìíràn, nínú atẹjade DAARUL KAATIB ni.

14- Lẹyin naa báwo wa ni ti a ba lọ sí ibi oju.

Ìyẹn ni idẹra ti a ko le ṣe odiwọn rẹ pẹlu iyekiye :

﴿أَلَمۡ نَجۡعَل لَّهُۥ عَيۡنَيۡنِ ٨﴾ [البلد: 8]

{Ṣé A kò ṣe ojú méjì fún un? {8}.}. [. Sūratul Balad].

Agbára ìgbéǹkanyọ kedere ojú ṣe déédéé: Ẹẹdẹgbẹta ati mẹfa le ni àádọ́rin mega-pixels.

Oju ko awò ti o mọ julọ sinu ninu agbaye."

Ìwọ̀n olùgba-fọ́tò nínú awọ fẹ́lẹ́fẹ́lẹ́ tí ń gba ìmọ́lẹ̀ wọlé nínú ojú, àgbègbè rẹ kò ju àbọ̀ mìlímítà níbùú lóòró lọ, a maa n ṣe ìyàtọ̀ pẹ̀lú rẹ láàárín mílíọ̀nù mẹ́wàá ipele ti àwọ̀ pẹ̀lú àwọn ìwọ̀n oríṣiríṣi rẹ, dájúdájú o jẹ nǹkan èèmọ̀ ati dídá ti Ọlọhun ti o ya ni lẹ́nu.

Ti o ba n wo nǹkan ni iwaju rẹ, ti ìmọ́lẹ̀ wa bọ́ sori awọ fẹ́lẹ́fẹ́lẹ́ ojú, ọpọlọpọ ìlànà ti kẹ́míkà ti o diju ni o maa ṣẹlẹ̀ ni àsìkò yii ti o maa mu iná mànàmáná jáde, iná mànàmáná yii maa kúrò lati awọ ojú rẹ bọ́ si ọpọlọ rẹ nípasẹ̀ àwọn wáyà iṣan, ọpọlọ ni o maa túmọ̀ iwọn ìgbì iná mànàmáná yii si ìríran bii ìgbà tí o ṣe pe ọpọlọ ni ìwé atúmọ̀ èdè odindi tẹ́lẹ̀, ti o n yí iná mànàmáná ti o ba dé ibẹ̀ sí iriran fún nǹkan to n bẹ ni iwájú rẹ

Nkan ti o ya ni lẹnu pupọ ni ti ẹ ba ronu si i!

Fi ojú inú wò ó pé: Ọpọlọ yii sapamọ sínú àpótí kan- ti o jẹ ti eegun ti o si ṣókùnkùn- àpótí ti o ṣókùnkùn naa ni agbárí

Ko si nǹkan kan ti o maa dé ọpọlọ rẹ ju iná mànàmáná lọ

Bawo wa ni ọpọlọ o ṣe túmọ̀ ẹwọ itanna yii sí pé oun naa ni iriran?

Bawo ni o ṣe fun ẹ ni iriran?"

Èèmọ̀ yii maa ṣẹlẹ ni iṣẹju àáyá pẹlu pe o kan ya oju rẹ mejeeji ti o si fi riran! “

Irú nǹkan náà ni o maa ṣẹlẹ sí ìgbọ́rọ̀ náà

Bi awọn ìgbì ohùn ṣe n wọ inu ìlù etí rẹ, ti ìlù etí si maa yi wọn pada lati awọn igbi si ìyírapadà ti ẹ̀rọ, ti ìyírapadà ti ẹ̀rọ yii si maa kúrò nipasẹ eegun kekere mẹ́ta kan ninu eti aarin lọ si eti inu, eléyìí ti yoo yi i padà si iná mànàmáná. “

Iná mànàmáná yii yoo wa kuro nsinyii lati eti inu lọ si inu ọpọlọ, lati jẹ ki ọpọlọ bẹrẹ si níí ya iná mànàmáná yii sọ́tọ̀ si awọn ohùn, ni a ba maa gbọ ohun naa! “

Gbogbo eyi maa ṣẹlẹ bakannaa láàrin nkan to kere ju ida kan ninu iṣẹju àáyá lọ:

﴿وَٱللَّهُ أَخۡرَجَكُم مِّنۢ بُطُونِ أُمَّهَٰتِكُمۡ لَا تَعۡلَمُونَ شَيۡـٔٗا وَجَعَلَ لَكُمُ ٱلسَّمۡعَ وَٱلۡأَبۡصَٰرَ وَٱلۡأَفۡـِٔدَةَ لَعَلَّكُمۡ تَشۡكُرُونَ ٧٨﴾ [النحل: 78]

{{Alla-hu l’Ó mu yín jáde láti inú ikùn àwọn ìyá yín nígbà tí ẹ̀yin kò tí ì dá n-ǹkan kan mọ̀. Ó sì ṣe ìgbọ́rọ̀, àwọn ìríran àti àwọn ọkàn fun yín nítorí kí ẹ lè dúpẹ́ (fún Un).}. [Surah An-Nahl : 78].].

Fi ojú inú wò ó pé ẹgbẹẹgbẹ̀rún àmì ti iná mànàmáná n dé inú ọpọlọ ni gbogbo iṣẹju àáyá lati ojú, àti etí, àti fífi ọwọ́ kan nǹkan, ati títọ́ nǹkan wò, ati gbigbooorun nǹkan, ati lati àwọn ẹ̀yà ara oríṣiríṣi; lati le ṣe ìyàtọ̀ fínnífínní láàárín àwọn àmì yii, lára nǹkan ti ó ṣeni ni eemọ jù ni:

﴿هَٰذَا خَلۡقُ ٱللَّهِ فَأَرُونِي مَاذَا خَلَقَ ٱلَّذِينَ مِن دُونِهِۦۚ بَلِ ٱلظَّٰلِمُونَ فِي ضَلَٰلٖ مُّبِينٖ ١١﴾ [لقمان: 11]

{Èyí ni ẹ̀dá ti Alla-hu. Nítorí náà, ẹ fi ohun tí àwọn mìíràn lẹ́yìn Rẹ̀ dá hàn mí! Rárá o! Àwọn alábòsí wà nínú ìṣìnà pọ́nnbélé ni. {11}} [Suuratu Luqmaan].

﴿وَتَرَى ٱلۡجِبَالَ تَحۡسَبُهَا جَامِدَةٗ وَهِيَ تَمُرُّ مَرَّ ٱلسَّحَابِۚ صُنۡعَ ٱللَّهِ ٱلَّذِيٓ أَتۡقَنَ كُلَّ شَيۡءٍۚ إِنَّهُۥ خَبِيرُۢ بِمَا تَفۡعَلُونَ ٨٨﴾ [النمل: 88]

{(Ìyẹn jẹ́) iṣẹ́ Alla-hu, Ẹni tí Ó ṣe gbogbo n-ǹkan ní dáadáa. Dájúdájú Ó mọ ìkọ̀kọ̀ ohun tí ẹ̀ ń ṣe níṣẹ́.} [88].} [S Suuratu Naml].

Ta wa ni ẹni yii ti o ṣe wipe o n ka idẹra kan ninu awọn idẹra Ọlọhun?"

Ronu si gbogbo ibi kọọkan ti egungun ti pàdé papọ ni ara rẹ, ati si gbogbo egungun ti o fun ọ ni àǹfààní lílọbíbọ̀ pẹ̀lú odiwọn rẹ̀! "

Ronú nípa àwọn oríkèé tó ń dán to n fun ọ ni àǹfààní lílọbíbọ̀ láìsí ìfaragbúnra tàbí jíjẹ láàárín àwọn egungun, àwọn oríkèé yii ti Ọlọhun fi si ara rẹ̀ nǹkan to n ṣàn bii ọ̀rá ti a maa n fi sára àwọn oríkèé ẹ̀rọ

Ronu si awọn idẹra Ọlọhun ni ẹniti o n ṣe ayẹwo ti o si n dupẹ fun awọn idẹra Rẹ, mimọ ni fun Un. "

Awọn idẹra Ọlọhun ko ṣeé kà:

﴿أَلَمۡ تَرَوۡاْ أَنَّ ٱللَّهَ سَخَّرَ لَكُم مَّا فِي ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَمَا فِي ٱلۡأَرۡضِ وَأَسۡبَغَ عَلَيۡكُمۡ نِعَمَهُۥ ظَٰهِرَةٗ وَبَاطِنَةٗۗ وَمِنَ ٱلنَّاسِ مَن يُجَٰدِلُ فِي ٱللَّهِ بِغَيۡرِ عِلۡمٖ وَلَا هُدٗى وَلَا كِتَٰبٖ مُّنِيرٖ ٢٠﴾ [لقمان: 20]

{Ṣé ẹ ò rí i pé dájúdájú Alla-hu rọ ohunkóhun t'ó wà nínú àwọn sánmọ̀ àti ohunkóhun t'ó wà nínú ilẹ̀ fun yín, Ó sì pé àwọn ìkẹ́ Rẹ̀ fun yín ní gban-gba àti ní kọ̀rọ̀ ? Ó sì wà nínú àwọn ènìyàn ẹni t'ó ń jiyàn nípa Alla-hu láì ní ìmọ̀ (al-Kur'a-n) àti ìmọ̀nà (nínú sunnah Ànábì s.a.w.) àti tírà (onímọ̀-ẹ̀sìn) t'ó ń tan ìmọ́lẹ̀ (sí ọ̀rọ̀ ẹ̀sìn). {20}.} [Suuratu Luqmaan].

8- Àwọn kan ninu awọn ti ko ni igbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun n bu ẹnu àtẹ́ lu itọka akolekan, wọn maa n sọ pé àwọn nnkan kan n bẹ tí kò dára gẹ́gẹ́ bii : Àwọn àìsàn ati ìmìtìtì ilẹ̀ ?

Esi : Àìsí àwọn ohun pípé ní àgbáálá ayé, gẹgẹ bi ọ̀rọ̀ aláìgbàgbọ́ nínú Ọlọhun náà, kò tako wíwà pípé

Pẹlu ìyẹn, ó ń ṣe afirinlẹ bíbẹ pípé ní àgbáyé

Tí Kò bá sí pípé rárá ni, alaigbagbọ nínú Ọlọhun yii kò bá tí mọ̀ pé àwọn nǹkan kan n bẹ tí kò pé

Báwo ni waa ṣe maa sọ̀rọ̀ nípa àléébù ti n bẹ nibi iṣẹ́ ọnà ni àgbáyé kan tí kò ní iṣẹ́ ọnà ?

Ṣùgbọ́n ohun ti wọn n sọ pe kò pé, èyí jẹ́ àìní ìmọ̀ tí ó tó, tàbí àìle gbọ agbọye ọgbọ́n ti n bẹ níbi àwọn nǹkan

Àwọn onigbagbọ òdodo kìí sọ pé àgbáyé jẹ́ nǹkan tí ó pé ti àwọn àdánwò ko nii maa ṣẹlẹ̀ nínú ẹ, ṣùgbọ́n nǹkan ti wọn n sọ ni pe : Agbaye jẹ́ nǹkan tí ó pé, nǹkan kan ko le ṣẹlẹ̀ ninu rẹ láìní ìdí.

Ìròrí alaigbagbọ ninu Ọlọhun yii jọ ti ẹni ti o sọ pe ọkọ̀ àgbéresánmà kò pé ; tori pé epo pẹtiróòlù ti o pọ wa ninu rẹ tí ó sì le mu kí ọkọ̀ àgbéresánmà naa bú gbàù ni igbakugba [4]

Wọn kò ṣe agbekalẹ ayé ki o le jẹ́ ayé ti ko ni òpin tabi tí ko ni ìbẹ̀rẹ̀, wọn ko si ṣe agbekalẹ awa naa lati di òòsà ?

Bi ko ṣe pe wọn ṣe agbekalẹ wa ki wọn o le dán wa wò pẹ̀lú oore ati aburú :

﴿كُلُّ نَفۡسٖ ذَآئِقَةُ ٱلۡمَوۡتِۗ وَنَبۡلُوكُم بِٱلشَّرِّ وَٱلۡخَيۡرِ فِتۡنَةٗۖ وَإِلَيۡنَا تُرۡجَعُونَ ٣٥﴾ [الأنبياء: 35]

{A sì máa fi aburú àti rere ṣàdánwò fun yín. Ọ̀dọ̀ Wa sì ni wọn yóò da yín padà sí. {35}.} [Suuratul Anbiyaa].

Rere ati aburu maa n yí ninu ọgbọ́n ati fífẹ́ Ọlọhun

9- Ki ni nǹkan ti o burú ninu ki okùnfà ti a le fojú rí dá ayé; àpèjúwe ìyẹn ni: Ọlaju mìíràn tabi nǹkan mìíràn, kilode ti o fi wa jẹ Ọlọhun ti ko ni ìbẹ̀rẹ̀ gan pàtó?

Esi: Ofin kan wa ti àwọn onímímọ̀ Islam ti fi ìdí rẹ múlẹ̀ lati nǹkan ti o ti le ni ẹgbẹ̀rún ọdún séyìn, ofin yii n sọ pe: Púpọ̀ àwọn ti wọn ṣe nǹkan maa n fa àìsí nǹkan ti wọn ṣe.[5]

Pupọ àwọn ti wọn ṣe nǹkan n tumọ si: Ki aṣẹda ju ẹyọkan lọ, ninu ìbéèrè yii, a ní ọlaju mìíràn tí o jẹ jáde latara ọlaju kan ti o ṣáájú rẹ, ati

---

[4] Ìṣẹ̀lẹ̀ bíbu ẹnu àtẹ́ lu ẹsin ninu ìmọ̀ filọsọfi ti òde òní, Dr. Sultan Al-Umayri, ìwé-àkọgboyèjáde fun oyè dókítà.

[5] Ìṣẹ̀lẹ̀ bíbu ẹnu àtẹ́ lu ẹsin ninu ìmọ̀ filọsọfi ti òde òní, Dr. Sultan Al-Umayri, ìwé-àkọgboyèjáde fun oyè dókítà.

ọlaju kan tí ó ṣáájú wọn ti wọn jẹ jáde latara rẹ, ati bẹẹ bẹẹ lọ, eleyii ni títẹ̀léra àwọn aṣẹda

Títẹ̀léra yìí maa n fa àìsí nǹkan ti wọn ṣe.

Àìsí nǹkan ti wọn ṣe n túmọ̀ sí: Kí ó má si awọn ẹ̀dá bii àgbáyé ati èèyàn ati awọn nǹkan ti o yatọ si wọn.

Títẹ̀léra àwọn ti wọn ṣe nǹkan maa fa àìsí àgbáyé.

Ti o ba jẹ pe ọlaju kan ko leè wà àyàfi ki ọlaju kan o ṣáájú rẹ ti o maa bí i, báyìí ni o ṣe maa lọ titi ti ko fi nii ní òpin, ọlaju yii ko leè hàn, bẹ́ẹ̀ si ni ọlaju ti o ṣáájú rẹ naa ko lee hàn, bẹ́ẹ̀ ni eyi ti o ṣáájú méjèèjì naa ko lee hàn, àgbáyé gan ko lee maa bẹ, nǹkan kan ko si le maa bẹ.

Tori pe gbogbo ọlaju ni o gbọdọ ni ọlaju ti o maa ṣáájú rẹ ti o maa bi i, ti o ba rí bẹ́ẹ̀, ọlaju kankan ko lee maa bẹ, bẹ́ẹ̀ si ni nǹkan kan ko le maa bẹ.

A gbọdọ ni aṣẹda àkọ́kọ́ tí kò ní ìbẹ̀rẹ̀ tí ó dá gbogbo nǹkan.

Ti o ba jẹ pe ọ̀wọ́ ti ko ni òpin ni, gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ kọọkan nínú ọ̀wọ́ naa maa gbára lé èyí tí ó ṣíwájú rẹ ni, ti o ba wa rí bẹ́ẹ̀, ẹ̀dá kankan ko leè sí, nǹkan kan ko si le maa bẹ; torí pé ẹni tí ó ṣe nǹkan, bibẹ rẹ maa gbára lé olùṣe kan ti o ṣíwájú rẹ, ti eyi ti o ṣíwájú rẹ naa maa gbára lé ẹni tí o ṣíwájú tiẹ̀ naa, bi o ṣe ma maa rí lọ nìyẹn, nípa bẹ́ẹ̀, nǹkan kan ko lee maa bẹ nìyẹn

Ko wa si ibuyẹ nibi pe ki ọ̀wọ́ yii koraro nibi aala kan

Nibi yii ni a o ti mọ dájú pe Adẹdaa Akọkọ n bẹ ti ko si si nǹkan kan ti o gba iwaju Rẹ!

10- A mọ awọn ofin eleyii ti n dárí ayé, a si tun mọ okunfa ìmìtìtì ilẹ̀ daadaa, ki wa lode ti a n bukaata si Adẹdaa ti a si mọ awọn ofin naa?

Esi: Alaigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun o maa lero pe awọn ofin yii o maa to fun dida aye ati hihan rẹ. Apa kan ninu awọn ti ko gbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun si ti gbára le irori kan ti a n pe ni "ofin òòfà" wọn ni o to fun hihan aye. Lai wo àìfi ẹsẹ múlẹ̀ èrò yii fúnra rẹ, ọ̀wọ́ pé èèyàn kan ronú sí ìpìlẹ̀ òfin òòfà, tabi tani o ṣe e ni ofin, tabi tani o fun un ni ìròyìn dídá sí nǹkan ati ṣíṣe àfihàn oripa?

Láìka àwọn nǹkan ti o kọkọ maa wa si làákàyè si, dájúdájú ofin oofa ko lee jẹ ki bọọlu eré bọọlu àfigigbá lori tabili maa yí kiri

Òfin naa nìkan kò lè da nǹkan kan ṣe láìsí pé nǹkan naa hàn

Ofin òòfà ko le mu bọọlu billiard jáde, ó kàn maa mi in ni ti o bá hàn tí wọ́n si fi ọ̀pá billiard gbá a

Ofin oofa kii ṣe nnkankan ti o da duro, ṣugbọn oun ni iroyin fun ìṣẹ̀lẹ̀ kan ti o jẹ ti àdánidá.

Ofin òòfà ko le jẹ ki bọọlu billiard kúrò ní ojú kan láìsí agbára kan ti o maa fòòró ọ̀pá billiard ti o si maa mì ín, ibi yii nikan ni bọọlu billiard ti maa kúrò ni ojú kan, ti oripa ofin oofa si maa hàn.

Ṣugbọn alaigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun maa lérò pé bibẹ ofin òòfà ti to fun dídá bọọlu billiard ati ọ̀pá billiard ati yíyí bọọlu naa.

Ewo ni o sunmọ laakaye julọ ki o jẹ okunfa hihan aye yii: Ṣe Adẹdaa ni abi ofin naa?

Ohun tí ó dà bíi irú rẹ̀ naa ni ofin ẹ́ńjìnnì ti o wa nínú mọ́tò, ko leè dá mọ́tò lailai.

Ti a ba ṣe afiti ofin ẹ́ńjìnnì sara mọto, mọto ko lee ṣiṣẹ́, epo gbọdọ wa ti o maa pèsè agbára. Gbígbóná naa si gbọdọ wa, mọ́tò naa si gbọdọ wà ṣíwájú ìyẹn, níbi ni ofin gbígbóná ẹ́ńjìnnì ti maa hàn ti mọto si maa ṣiṣẹ.

Ko si ninu ohun ti o ba laakaye mu lati lero pe ofin ẹ́ńjìnnì ti to fun dida mọto ati gbígbóná ẹ́ńjìnnì ati epo ati awakọ̀ ati ojú ọ̀nà.

Irori wipe ofin yii ti to fun alaye hihan aye jẹ irori kan ti ko ba laakaye mu rara

Lẹ́yìn náà, ti a ba ro èrò yii, o maa mu wa wọ inú ọ̀wọ́ àwọn olùṣe nǹkan ti a ṣàlàyé nibi ìdáhùn sí ìbéèrè ti o ṣáájú, tani o da òfin yii. Ti wọn ba lero pe ofin mìíràn ni, a maa kó sínú ọ̀wọ́ àwọn olùṣe nǹkan ti yoo jẹ ki a mọ pe ko si ofin kankan, nǹkan kan ko si bẹ

11- Ki ni o burú ninu ki ìpìlẹ̀ ayé jẹ èèsì?

Èsì: Ọrọ ṣiṣeesi yii, ṣiṣe aimọkan ni pẹlu awọn ipilẹ lilero nnkan; nitori pe ṣiṣeesi ni majẹmu meji ti wọn ko le ya a.

Awọn mejeeji naa ni: igba ati àsìkò

Èèsì ṣe ìgbà ti oripa rẹ yoo wáyé nínú ẹ ni májẹ̀mú

O tun ṣe ààyè ti yoo ti maa ṣe àgbéjáde nǹkan ti o ba n ṣe nínú ẹ ni májẹ̀mú.

Bawo ni a ṣe maa wa sọ pe èèsì ni ipa nibi mímú ayé maa bẹ ti ó sì jẹ pe ayé wa yii wá lati ibi àìsí-ìgbà ati àìsí-àyè.

Bawo ni oripa ṣiṣeesi ṣe fẹ han lai jẹ si pe ṣiṣeesi gan foju han funra rẹ?

Bawo ni o ṣe maa fun ṣiṣeesi ni oripa kan siwaju bibẹ rẹ ti bibẹ igba ati aaye si jẹ majẹmu ipilẹ fun ṣiṣeesi?

12- Bawo ni a o ṣe da adapada èsì fun keferi ti o sọ wipe ko si ìbẹ̀rẹ̀ fun ayé?

Esi: Ní ìbámu sí ofin keji tamodìnámíìkì, ko rọrun ki ibẹẹrẹ o wa fun bibẹ

Fun ifọsiwẹwẹ alaye fun ofin yii, a maa fi àpèjúwe yii lélẹ̀ fun alaye rẹ: Ti o ba ni kọ́ọ̀bù omi gbigbona kan ninu yàrá, dajudaju ooru yoo maa jade lati inu omi gbígbóná yii si inu yàrá títí tí ooru inu yàrá yoo fi to ooru inu kọọbu yii, eleyii ni ofin ẹlẹẹkeji fun tamodìnámíìkì gbigbona, lọna to ṣe wípé agbára yoo maa wa lati oke si isalẹ fún gbogbo asiko.

Òfin yii maa n ṣẹlẹ̀ nínú gbogbo nǹkan nínú ayé ni gbogbo iṣẹju lati ìgbà ti ayé ti n bẹ, títí tí ooru gbogbo nǹkan ninu ayé fi máa dọ́gba. Nígbà tí ooru gbogbo nǹkan nínú ayé ba wa dọ́gba, nǹkan ti a mọ̀ sí "IKÚ OORU" maa ṣẹlẹ̀ nínú ayé. Ti o ba jẹ pe ayé ní ìbẹ̀rẹ̀ ni, o yẹ kí ayé ti dúró báyìí (ikú ooru). Ṣùgbọ́n, ká sòótọ́, báyìí, ayé n bẹ ni ipò kan tí ó kéré ju Entropy ti ó pọ̀ julọ, ṣùgbọ́n koi tii tó ikú ooru, torí náà kii ṣe nǹkan ti ko ni ìbẹ̀rẹ̀, bi ko ṣe pé ó ní ìbẹ̀rẹ̀ tí ó rinlẹ tí ìgbà àti ààyè hàn pẹ̀lú ẹ.

O si ti fi ẹsẹ rinlẹ, ni ìbámu si ofin naa, wipe ayé bẹ̀rẹ̀ lati ibi aala ti o kéré jù nínú entropy, eleyii n tumọ si pe bibẹ rẹ waye laisi afiwe kankan siwaju.

Eleyii ni ofin ti imọ ni abala kan, ti aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun naa si wa ni abala mìíràn patapata.

Ki ni ó dé ti wọn ko fi maa lo ofin okunfa fun Ọlọhun Adẹdaa? Tabi pẹlu gbolohun miiran: Tani ẹniti o da Ọba Adẹdaa?

Esi: Akọkọ: Wọn kii lo ofin ẹda fún Ọba Adẹdaa, eleyii jẹ ohun ti ko ruju rara.

Aijẹ bẹẹ a ko ba sọ pé: Tani ẹniti o se alásè?

Tani ó kun kunlékunlé?

Lai ruju rara, Ọlọhun Adẹdaa ni O mu asiko ati aaye maa bẹ, nitori idi eyi, a ko gbọdọ maa lo awọn ofin le E lori, Oun ni O mu wọn maa bẹ, mimọ ni fun Un.

Ẹlẹẹkeji: Gbogbo ohun to ba n bẹ a maa ni ẹni ti o n mu un bẹ, ootọ ni eyi, ṣugbọn Ọlọrun Adẹdaa:

﴿فَاطِرُ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِۚ جَعَلَ لَكُم مِّنۡ أَنفُسِكُمۡ أَزۡوَٰجٗا وَمِنَ ٱلۡأَنۡعَٰمِ أَزۡوَٰجٗا يَذۡرَؤُكُمۡ فِيهِۚ لَيۡسَ كَمِثۡلِهِۦ شَيۡءٞۖ وَهُوَ ٱلسَّمِيعُ ٱلۡبَصِيرُ ١١﴾ [الشورى: 11]

{(Kòsí kiní kan bí irú Rẹ) {11}}. [Suuratu Shura]

Ẹlẹẹkẹta: Ko si ìbèrè fun Ọba Adẹdaa, bawo waa ni a ṣe maa sọ pe tani o da A?

Ẹlẹẹkẹrin: Ko si bi ìbèrè ṣe le wa fun Ọlọhun Adẹdaa, bibẹẹkọ a o ba wọ inu wahala “títèléra àwọn òṣìṣẹ́ ti o maa n saaba já sí aiwaye iṣẹ́”. Eleyii ni ohun ti a ṣàlàyé laipẹ siwaju nifosiwẹwẹ, ko si ibuyẹ bi Ọlọhun Adẹdaa ko ṣe nii maa bẹ, ṣugbọn ko si ìbèrè fun Un.”

Ayé tobi gan, pẹlu ìwọ̀n wa ti o kéré yii, bawo waa ni a ṣe maa jẹ ẹda ti o pàtàkì jù nínú ayé ńlá yìí?

Èsì: Alaigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun n gbe èrò kan tí ó ń tako ara wọn kalẹ, o n sọ pé: Pèlú bi ayé ṣe tóbi, ọmọniyan ko leè jẹ ohun ti o pàtàkì jù nínú ayé yìí.

Wọ́n mọ èrò yìí lórí ọ̀rọ̀ itisiwaju kan pe: Pèlú bi oko ṣe fẹ̀, ti ìwọ̀n ẹni ti ó ni i sì kéré gan ní ìbámu sí i, ti o bá rí bẹ́ẹ̀: Òun kọ́ ni ó ni i.

Àlámọ̀rí náà kii ṣe pèlú ìwọ̀n rárá.

Awọn iwa ti ko ni odiwọn ti a lè fi ojú ri ni ọ̀pá ìdíwọ̀n ti o tóbi julọ níbi ìfiwéra láàrin èèyàn ti o tobi jù ati èèyàn tí ó yẹpẹrẹ jù.

Wọn yoo maa wọn òṣùwọ̀n awọn èèyàn pèlú iwa wọn

Ọrọ nipa ìwọ̀n kii ṣe ọ̀pá ìdíwọ̀n.

Ẹ jẹ ki a fi àkàwé yìí lélẹ̀: Ti a ba ni ọba kan, ti ọba yii wa sọ àwọn àsọtẹ́lẹ̀ kan fun ọmọ rẹ, ti o si kọ ìwé kan fun un nipa ìyẹn. Njẹ o rọrùn ki alátakò kan o wa ki o wa sọ pé: Báwo ni ọba ti o ni ọ̀kẹ́ àìmọye eékà ati ilẹ̀ ti o fẹ̀ ki o ni akolekan ọmọ rẹ tí ìwọ̀n rẹ kò tó ẹyọkan nínú ọ̀kẹ́ àìmọye nǹkan tí ó ní nínú àwọn ilẹ̀?

Ọlọhun ni O ni àkàwé tí ó ga julọ

Ǹjẹ́ àtakò yii wulẹ̀ bá làákàyè mu?

Ọ̀rọ̀ naa kii ṣe pẹ̀lú ìwọ̀n tàbí òṣùwọ̀n

Lẹ́yìn naa, ǹjẹ́ ààyè ti o kéré ju orí abẹ́rẹ́ lọ ní ọ̀kẹ́ àìmọye ìgbà kọ́ ni àgbáyé yìí ti bẹ̀rẹ̀ ni gẹ́gẹ́ bi gbogbo onímọ̀ físíìsì àgbáyé ṣe fi ìdí rẹ múlẹ̀?

Ti o ba ri bẹ́ẹ̀, ìwọ̀n naa jẹ nǹkan tí ó nii ṣe pẹlu nǹkan ti a ba ṣe àfitì rẹ sí

Kini ìnira ti o maa ba alaigbagbọ nínú Ọlọhun ki Ọlọhun dá nǹkan ti o wù Ú pẹ̀lú ọ̀nà ti o gbà wù Ú?

Ǹjẹ́ ohun èlò ti Ọlọhun nílò ni kò tó ni tí yóò fi máa ná odiwọn ti O ba bùkátà si?

Ọlọhun ju ìyẹn lọ

Ṣùgbọ́n ǹjẹ́ àwa ni ọkàn ayé yìí ní òtítọ́?

Bẹẹni ìwọ ọmọniyan ni ọkàn ayé yìí pẹ̀lú iṣẹ́ atọrunwa

Iṣẹ́ atọrunwa naa ni: Ẹsin.

Ẹsin ni àgbàfipamọ́ ti o gbé, òun si ni idanwo ti o tobi ju ti o nílò lati ṣe

Ìwọ ọmọniyan nilo lati jẹ ẹrú fún Ọlọhun, pẹ̀lú èyí waa jẹ́ ọkàn ayé yìí, ọkàn ayé yìí ni ẹ́, kii ṣe pẹ̀lú iwọn rẹ tàbí agbára rẹ tàbí ìkápá rẹ, bi ko ṣe pe pẹ̀lú iṣẹ́ atọrunwa ni

Ìwọ ni o kápá láti ṣe rere ati lati fi aburu silẹ... ìwọ ni o kápá láti ni ìgbàgbọ́ ati lati ṣe aigbagbọ

Gbogbo wa ni a mọ pe wọn bẹ̀ wá ní iṣẹ́, a fẹ́ o, a kọ̀ o.

Alaigbagbọ ati Onigbagbọ ati ẹni ti ko mọ eyi ti yoo ṣe, gbogbo èèyàn pata ni o mọ pe wọn bẹ oun ni iṣẹ́ láti jẹ́, ti o si n ni imọlara iṣẹ́ atọrunwa, ti ẹ̀rí ọkàn si maa n jẹ́ ẹ, ti o si mọ̀ pe “ṣe” àti “má ṣe” n bẹ nínú òun... ṣe rere, ma ṣe aburu, ẹni kọọkan wa ni o mọ ninu ẹ̀mí ara rẹ pe wọn ni ki òun ṣe nǹkan.

Awa ni a wa ninu ọkàn ayé yii ni ti iṣẹ́ ti wọn ni ki a ṣe

Bakannaa ni a jẹ ọkan ayé yii ni ti òye ati ìmọ̀, a n ni òye, a si n gbọ nǹkan yé, a si n mọ pàápàá bibẹ wa, ati pàápàá àgbáyé ni àyíká wa, a si n gbọ agbọye itumọ bibẹ wa dáadáa.

Àwa ni wọn bẹ ní iṣẹ́, awa ni wọn maa bá wí, awa ni wọn la iṣẹ́ bọ̀ lọ́rùn, awa ni a maa ṣe ìṣirò.

Awa ni ẹda ti o mọ ẹwà pípèsè nǹkan pẹ̀lú akolekan, awa ni ẹda ti o mọ ki nǹkan pé, awa ni ẹda ti o kápá lati ṣe nǹkan ti wọn là bọ̀ wa lọrun tabi ki a ma ṣe e, a kapa lati ṣẹ̀sà, a kapa lati gbagbọ ati lati ṣe aigbagbọ.

Awa ni a wa ninu ọkàn ayé yii:

﴿إِنَّا عَرَضۡنَا ٱلۡأَمَانَةَ عَلَى ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِ وَٱلۡجِبَالِ فَأَبَيۡنَ أَن يَحۡمِلۡنَهَا وَأَشۡفَقۡنَ مِنۡهَا وَحَمَلَهَا ٱلۡإِنسَٰنُۖ إِنَّهُۥ كَانَ ظَلُومٗا جَهُولٗا ٧٢﴾ [الأحزاب: 72]

{Dájúdájú Àwa fi iṣẹ́ láádá lọ àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ àti àpáta. Wọ́n kọ̀ láti gbé e ; wọ́n páyà rẹ̀. Èniyàn sì gbé e. Dájúdájú (èniyàn) jẹ́ alábòsí, aláìmọ̀kan. {72}}. [Suuratul Ah'zaab].

15- Àwọn kan ninu awọn ti ko ni igbagbọ pe Ọlọhun n bẹ maa n sọ pe : Ọpọlọpọ irawọ ni o n bẹ, lábẹ́ bẹ́ẹ̀, pẹ̀lú àbá èrò orí "o ṣeé ṣe", kii ṣe ohun àjèjì ki irawọ kan wa ki o dára fun iṣẹmi. ǹjẹ́ ẹ̀rí yii ni àlàáfíà bi?

Esi : Kini aṣepọ bibẹ àwọn irawọ ti o pọ pẹ̀lú bíbu ẹnu àtẹ́ lu itọka pípé?

Ọrọ naa kii ṣe ohun èlò tí wọ́n fẹ́ fi ṣiṣẹ́

Ki i ṣe pe mo wa ninu igbo kan ti o kun fun gbogbo ewebẹ ati eso ati awọn ẹranko, ko ki n ṣe itumọ yẹn ni pe ki igba ounjẹ ti a se to ladun yọ si iwaju mi lójijì ni aarin igbo naa ; ọrọ naa kìí ṣe ti awọn ohun elo ti wọn fẹ fi ṣiṣẹ́ !"

Bákan náà, kii ṣe itumọ ki iyanrìn wà ni arọwọto nínú aginjù ayé ni pé maa rí àwọn kọnputa onídíjítà àti àwọn sîìmù ti kọnputa ti wọn ṣe latara iyanrìn ni àyíká mi ni gbogbo ààyè nínú aginjù

ọrọ naa kìí ṣe ti awọn ohun elo ti wọn fẹ fi ṣiṣẹ́, bi ko ṣe pe ọrọ naa jẹ́ ṣíṣe nǹkan ati ṣíṣe dáadáa.

Bíbẹ apapọ awọn irawọ lasan kò tó láti jẹ ki irawọ kan bíi ilẹ̀ pẹ̀lú bi o ṣe dára tó yii, ki o hàn laarin wa.

Ọrọ naa, ṣiṣe nkan daadaa ni ati dídá nǹkan, ati ṣíṣe nǹkan :

﴿وَتَرَى ٱلۡجِبَالَ تَحۡسَبُهَا جَامِدَةٗ وَهِيَ تَمُرُّ مَرَّ ٱلسَّحَابِۚ صُنۡعَ ٱللَّهِ ٱلَّذِيٓ أَتۡقَنَ كُلَّ شَيۡءٍۚ إِنَّهُۥ خَبِيرُۢ بِمَا تَفۡعَلُونَ ٨٨﴾ [النمل: 88]

{(Ìyẹn jẹ́) iṣẹ́ Alla-hu, Ẹni tí Ó ṣe gbogbo n-ǹkan ní dáadáa} [88] "} [ Suuratun Naml].

Bíbẹ̀ àwọn irawọ mìíràn ti o pọ ko lè jẹ́ àwíjàre láéláé fún bibẹ iṣẹmi kan lórí irawọ ilẹ̀.

Bíbẹ̀ àwọn irawọ mìíràn ko ṣe ìdáláre fún koodu jiini ti o wà nínú rẹ, láti áràfí biliọnu mẹ́rin ti n ṣe àkóso gbogbo àwọn iṣẹ́ rẹ ati awọn oríkèé rẹ ati awọn omi ara ìsúnniṣe nǹkan, pẹ̀lú ìṣàkóso ti o ya ni lẹ́nu ṣíwájú ki ìwọ gan ó tó máa bẹ fúnra rẹ.

Isẹmi jẹ nǹkan ti a mọ̀, kii ṣe ohun èlò.

Ti èmi àti ọ̀kan ninu awọn ti ko ni igbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun ba gun ọ̀kan nínú àwọn irawọ lọ, ti a wá ṣe àwárí ohun èlò kan ti ó díjú ti o n ṣiṣẹ pẹ̀lú ìṣàkóso ti o ya ni lẹ́nu, kódà ki a mai tii gbọ́ iṣẹ́ rẹ yé, ǹjẹ́ o rọrùn ki a tako pe ẹnìkan ni o ṣe e bí ní ọ̀wọ́ọ bí iwọn irawọ ti a wa lori rẹ ṣe tóbi tó ?

Láìsí àní-àní, ti èmi àti alaigbagbọ ninu Ọlọhun naa bá rí ohun èlò yii, a maa sọ pe ẹnìkan ti o lágbára ni o n mú un máa bẹ.

Ẹni ti o ba n tako nǹkan ti ó hàn kedere yii ni o maa mu ẹ̀rí wá, kìí ṣe ẹni tí ó fi rinlẹ.

Alaigbagbọ nínú ayé ti o ya ni lẹ́nu ti o rẹwà yii ni o maa mu ẹ̀rí wa, kii ṣe olugbagbọ.

Nigba kan ri, alaigbọlọhungbọ ti o gba pe Ọlọhun ko ṣeé mọ̀ ti o n jẹ Carl Sagan kọ ìwé ìtàn arosọ kan to n jẹ “KÀN SÍ”, o n sọ nibẹ bi àwọn onímímọ̀ ìjìnlẹ̀ ṣe n ṣe ìwádìí nípa ọgbọ́n lẹ́yìn òde ilẹ̀ ayé.

Ninu ìwé ìtàn arosọ naa, àwọn onímímọ̀ ìjìnlẹ̀ ṣe àwárí ọ̀pọ̀ rẹpẹtẹ nínú àwọn nọ́mbà àkọ́kọ́ to n bọ láti gbangba ojúde òfuurufú ; torí pé titẹlera àkọ́kọ́ yii n jẹ ki a mọ pàtàkì ìmọ̀ ìṣirò kan pàtó, eyi ti o n tọka si ìran kan

ninu ìṣàkóso, eleyii jẹ ẹri ti ọpọlọ ti o tó láti mọ̀ dájú pé ifiranṣẹ yii n bọ̀ lati ọlaju mìíràn ti o n gbìyànjú láti kàn sí wa.

Ohun ti ó ń pani lẹ́ẹ̀rín ni pe Carl Sagan yii jẹ ẹni ti o gbagbọ pe Ọlọhun ko ṣeé mọ̀ ti ó gbajúgbajà, ṣùgbọ́n làákàyè rẹ gbà pé dídíjú àti ètò nínú ifiranṣẹ kékeré kan, o n tọka si ẹ̀rí mímú nǹkan bẹ ati ṣíṣe nǹkan dáadáa

Ọ̀wọ̀ọ́ ọ̀pọ̀ rẹpẹtẹ nínú àwọn nọ́mbà àkọ́kọ́ lásán, wàá gbà dájú pe ọlaju ńlá kan n bẹ, bawo wa ni waa ṣe ṣe afiti biliọnu mẹ́rin lẹta ninu sẹẹli kọ̀ọ̀kan nínú àwọn sẹẹli ara rẹ, eyi ti o ṣe pe ti lẹta kan ninu rẹ ba bajẹ, ajalu ńlá le ṣẹlẹ̀, báwo ni waa ṣe wa ṣe afiti gbogbo nǹkan tí wọ́n ṣe ni pípé yii sára ẹ̀tàn àwọn alaigbọlọhungbọ ti ko ba làákàyè mu.

Kò bá làákàyè mu rárá ki a lo ète láti má túmọ̀ ìṣẹ̀lẹ̀ ìyàlẹ́nu naa ni nǹkan tí o n tọka si Adẹdaa :

﴿قُلِ ٱنظُرُواْ مَاذَا فِي ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِۚ وَمَا تُغۡنِي ٱلۡأٓيَٰتُ وَٱلنُّذُرُ عَن قَوۡمٖ لَّا يُؤۡمِنُونَ ١٠١﴾ [يونس: 101]

{Sọ pé : "Ẹ wòye sí n-ǹkan tí ń bẹ nínú sánmọ̀ àti ilẹ̀. Àwọn a-yah àti ìkìlọ̀ kò sì níí rọ ìjọ aláìgbàgbọ́ lọ́rọ̀." {101}.} [Suuratu Yûnus].

Ki ni o de ti ko fi nii si Adẹdaa ti ko ni ibẹrẹ ti o ju ẹyọkan lọ ?

Esi : Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe :

﴿لَوۡ كَانَ فِيهِمَآ ءَالِهَةٌ إِلَّا ٱللَّهُ لَفَسَدَتَاۚ فَسُبۡحَٰنَ ٱللَّهِ رَبِّ ٱلۡعَرۡشِ عَمَّا يَصِفُونَ ٢٢﴾ [الأنبياء: 22]

{Tí ó bá jẹ́ pé àwọn ọlọ́hun kan wà nínú sánmọ̀ àti ilẹ̀ lẹ́yìn Alla-hu, sánmọ̀ àti ilẹ̀ ìbá ti bàjẹ́. [22]]. [Suuratul Anbiyaa].

Ki ọlọhun mìíràn wà pẹ̀lú Ọlọhun n tọ́ka si pupọ, ki nǹkan si pọ̀ nìyí maa sọ ìní bùkátà si ara ẹni di dandan.

Ki Aṣẹ̀dá si ni bùkátà sí ẹlòmíràn- ki Ọlọhun ma jẹ- maa sọ àìsí ifayabalẹ agbaye di dandan, ó sì le wó… o maa ṣe okunfa ki ayé bajẹ.

Ko sì ifọwọsọya fun ṣiṣẹku àgbáyé pẹ̀lú Ọlọhun ti n bùkátà si ẹlomiran!

﴿لَوۡ كَانَ فِيهِمَآ ءَالِهَةٌ إِلَّا ٱللَّهُ لَفَسَدَتَاۚ فَسُبۡحَٰنَ ٱللَّهِ رَبِّ ٱلۡعَرۡشِ عَمَّا يَصِفُونَ٢٢﴾ [الأنبياء: 22]

{Tí ó bá jẹ́ pé àwọn ọlọ́hun kan wà nínú sánmọ̀ àti ilẹ̀ lẹ́yìn Alla-hu, sánmọ̀ àti ilẹ̀ ìbá ti bàjẹ́. Mímọ́ ni fún Alla-hu, Olúwa Ìtẹ́–ọlá, tayọ ohun tí wọ́n ń fi ròyìn (Rẹ̀). {22}} [. Suuratul Anbiyaa].

Ọlọhun mọ kúrò nibi ìní bukata si ẹlomiran, Ọlọ́rọ̀ Alámòjúútó-ẹ̀dá ni.

Ni afikun si nǹkan ti a sọ ṣáájú: Tí Ọlọhun meji tabi ju bẹẹ lọ ba wa nibẹ ni, nǹkan ti o sunmọ làákàyè ju ni ki aigbọra-ẹni ye maa ṣẹlẹ̀ Tori ki Ọlọhun ju ẹyọkan lọ n túmọ̀ si ki fífẹ́ ati erongba ju ẹyọkan lọ, ki erongba pọ si n túmọ̀ ìní bukata si ẹlomiran, èyí si maa sọ bibajẹ sánmà ati ilẹ̀ di dandan.

Adamọ ọmọniyan gba pe ọ̀kan ni Ọlọhun láìsí iyèméjì, ti onímọ̀ fisiisi tabi ẹlòmíràn yàtọ̀ si i bá wo ayé, ko le lérò pé ẹni ti o dá a ju ẹnikan lọ, eyi ni adamọ.

17- Ki ni o de ti o fi jẹ̀ ẹ̀sìn?

Esi: Alaigbagbọ ninu Ọlọhun ti o buru jù gbagbọ pé òdodo ní ọlá ju irọ́ lọ, ṣe bẹ́ẹ̀ kọ ni o ri ni?

Esi: Alaigbagbọ ninu Ọlọhun ti o buru jù gbagbọ pé òtítọ́ ní ọlá ju ìjàmbá lọ, ṣe bẹ́ẹ̀ kọ ni o ri ni?

Àwọn gbólóhùn yii kii ṣe nínú àgbáyé yii, ko si si ninu àgbáyé àwa èèyàn nǹkan ti o maa dá Ìtumọ̀ rẹ tabi nǹkan ti o n tọka si láre

Kini itumọ òdodo?

Kini itumọ agbafipamọ?

Tí a bá ṣe ìtúpalẹ̀ ìjìnlẹ̀ átọ̀mù náà, ṣé a máa rí àwọn ìtumọ̀ bíi: òtítọ́ tàbí irọ́?

Ti a ba ṣe àkíyèsí fisiisi àwọn ìṣùpọ̀ irawọ tabi kẹmisiri omi ara ìsúnniṣe-nǹkan, ṣe a maa ri: Iṣotitọ tabi ìjàmbá.

Àwọn gbólóhùn yii kii ṣe ti àgbáyé awa èèyàn

Ṣùgbọ́n gbólóhùn gidi ni wọn

Bi ko ṣe pe wọn wa ninu awọn àlámọ̀rí ti o tóbi jù

Pàtàkì ọmọniyan, pẹ̀lú àwọn ìwà rẹ ni, kii ṣe pẹ̀lú iwọn rẹ ti a fi ojú rí tabi onka átọ̀mù rẹ, tabi ibi tí agbára sẹẹli rẹ de

Pataki ọmọniyan, pẹ̀lú mímú iṣẹ atọrunwa ni ọ̀kúnkúndùn ni.

Pataki yii, ko si nǹkan kan ninu àgbáyé yii ti o le kópa pẹ̀lú ọmọniyan ninu ẹ.

A ni èèyàn rere ati èèyàn burúkú

ṣùgbọ́n ko si òkè rere àti òkè burúkú.

A o si nii ri irawọ ti o ṣeé fi ọkan tán ati irawọ onijamba

Ọmọniyan ni a gba lero pẹlu ijẹpataki, oun naa ni a gba lero pẹ̀lú erongba, oun naa ni a gbà lérò pẹ̀lú bíbẹ.

Èèyàn ati alujannu nìkan ni wọ́n ni agbọye pe ẹni ti a la iṣẹ bọ lọrun ni àwọn

Mímọ itumọ ìwà lára jẹ apakan ninu adamọ iṣẹ amutọrunwa ninu ọkọọkan wa

Ẹsin jẹ dandan fun agbọye ọmọniyan

Ẹsin nikan ni o le dá itumọ ìwà láre, kini o dé tí ó fi wà, kilode ti a fi n ni imọlara ijẹdandan híhu ìwà náà

Nǹkan kan ṣoṣo ti o le fun ìwà ni àwòrán bi o ṣe yẹ ki o ri naa ni ẹsin

Ko rọrùn ki a gbọ ìwà ye ayafi ni ìbámu si iṣẹ atọrunwa

Ko si rọrùn ki a mọ ìdí tí ó fi jẹ adamọ ẹda ayafi lati ipasẹ ẹsin

Nípasẹ̀ ẹsin ni a fi maa mọ nǹkan ti a tori rẹ dá ayé, a si tun maa mọ pe àwọn ìwà ti a n ni imọlara pe o yẹ ki a maa hù, kódà ki a ma hù ú, jẹ apakan ninu iṣẹ atọrunwa

Ẹsin jẹ ko ṣeé má ṣe fún ọmọniyan

Nípasẹ̀ ẹsin ni a tun fi maa mọ kini ìdí ti a fi wà níbí?

A tun maa mọ kini nǹkan ti o n kan lẹyin ikú?

A tun maa mọ itumọ ayé

A tun maa mọ kini nǹkan ti wọn ni ki a ṣe ni ayé yii?

Ẹsin jẹ dandan lati mọ nǹkan ti o pàtàkì jù ti o maa n ko airoju ba ọmọniyan.

Tori náà, láìsí ẹsin, gbogbo ayé maa di ẹ̀ṣújò ati àìní ìgbàgbọ́ nínú ohunkóhun

Ibnul Qayyim- ki Ọlọhun kẹ ẹ- sọ pe: “Ko si ọna ìdùnnú ati èrè ni ayé ati ọ̀run àyàfi nípasẹ̀ àwọn ojiṣẹ Ko si si ọna lati mọ nǹkan ti o dara ati

nǹkan ti ko dara ayafi nípasẹ̀ wọn, eeyan ko si le ri iyọnu Ọlọhun ayafi nípasẹ̀ wọn”[6]

Ayé ṣókùnkùn, wọn si ti fi gé ègún, àyàfi ohun ti òòrùn ẹsin ati iṣẹ́ rírán bá yọ lé lórí, gẹgẹ bi Sheikhul Islaam Ibnu Taymiyya ṣe sọ, ki Ọlọhun kẹ ẹ. [7]

Láìsí ẹsin, a o le mọ nǹkan ti wọn tori rẹ da ayé, a o si nii mọ itumọ rere ati pàtàkì rẹ̀

Laisi rírán ojiṣẹ, ayé maa di asán ti yoo maa dẹ́rù bani

Tí ẹsin bá sapamọ, ti ọmọniyan sì tako ìjẹ́ anọbi, nígbà náà ọmọniyan maa di ìdọ̀tí irawọ gẹ́gẹ́ bi Carl Sagan ṣe sọ, àti kòkòrò gẹ́gẹ́ bí Sartre ṣe sọ [8]

Ní tòótọ́, ọmọniyan maa di idọti ti kẹ́míkà gẹ́gẹ́ bí Stephen Hawking ṣe sọ[9]

Ìjẹ́ anọbi nikan ni ìlùkìkì ọkàn ayé, láìsí ijẹ anọbi, àwọn èyí ti o rẹwà ju ninu awọn nǹkan ti a hùmọ̀ ati awọn nǹkan adùn ti a n gbádùn jù, gbogbo ẹ ni o maa yí padà di ẹ̀rù.

---

6 Zaadul Ma’haad 1-68

7 Majmuu’hul Fataawa 19/93,94

8 “[8] Video Source: The Shores of the Cosmic Ocean [Episode 1] Some part of our being knows this is where we came from. We long to return. And we can. Because the cosmos is also within us. We’re made of star-stuff. We are a way for the cosmos to know itself. 06 min 04 sec. Àmọ́ nípa ki ọmọniyan jẹ kòkòrò, Sartre ni o sọ bẹẹ ninu ìwé ìtàn àròsọ rẹ ti o n jẹ ÈÉBÌ

9 From an interview with Ken Campbell on Reality on the Rocks : Beyond Our Ken, 1995 “

Láìsí ẹsin, ayé, pẹ̀lú gbogbo ẹwà rẹ, maa yi pada di iwin ti n dẹ́rù bani

Ti o ba bi èyíkéyìí ninu awọn alaigbagbọ ninu Ọlọhun ni ìbéèrè ti o jẹ mọ́ ayé, gẹgẹ bii: Kilode ti a fi wa ni ayé yii tabi kini o maa ṣẹlẹ̀ lẹ́yìn ikú?

Ninu ki o fi ọgbọ́n àrékérekè dáhùn ìbéèrè rẹ, tabi ki ó dákẹ́

Ti o ba ri bẹ́ẹ̀, ẹsin ni ohun ti a béèrè fun láìsí àní-àní fun agbọye ọmọniyan, ati agbọye ijẹdandan ìwà rere, dandan ni o jẹ lati mọ itumọ ayé ati nǹkan ti wọn tori rẹ da ayé, ati mímú ijẹ ẹru fun Ọlọhun wa si ìmúṣẹ, ijẹ ẹru yẹn naa ni okùnfà ọlà.

18- Ki ni nǹkan ti o buru ninu ki awọn ìwà yii jẹ́ esi àbájáde ọpọlọ tabi àwùjọ?

Esi: Ọpọlọ kójọ latara irú àwọn ẹ̀yà ti a le fi ojú rí, eyi ti irú rẹ gẹ́lẹ́ n bẹ ninu àgbáyé awa èèyàn

Bi o tilẹ̀ wù ki ọpọlọ díjú tó, tabi ki ẹ̀yà rẹ ti a fojú rí díjú tó, akojọpọ òdo, òdo naa ni o maa bí jáde.

Ti ohun èlò ti ara ko ba mọ rere tabi aburú, a jẹ pe bẹ́ẹ̀ náà ni ọpọlọ ṣe ri.

Nibi, a maa bi alaigbagbọ ninu Ọlọhun léèrè pe: Báwo ni agbọye oore ati aburu ṣe han ti àgbáyé àwọn èèyàn pátá ba dúró ni ìdúró àìdásí-tọ̀túntòsì nipa ìwà, ti ko mọ rere ati aburu?

Ìbéèrè kejì: Kini nǹkan ti o kọ̀ fún ọpọlọ lati ma pa àwọn ti n bẹ lórí ilẹ̀ pátápátá run?

Kini nǹkan ti o kọ fun ọpọlọ lati ma mu ìran èèyàn ti o rẹlẹ̀ jù wọ inú àgò ẹranko?

Kini nǹkan ti o kọ fun ọpọlọ lati ma pa àwọn aláìsàn run, ati awọn abirùn, ati awọn arúgbó, àti àwọn ìran ti wọn rẹlẹ̀ ju, gẹgẹ bi o ṣe ṣẹlẹ̀ ninu iṣẹ àkànṣe yíyàn ti adayeba ti Nazi ṣe- iṣẹ́ àkànṣe ACTION T4?[10]

Àwọn ìbéèrè yii, ọpọlọ ẹda ko lee ni èsì fun wọn boya wọn ko tọ̀nà ni o abi wọn tọ̀nà.

Ọpọlọ da dúró gedegbe ni nipa ìwà; tori pe àti ara irú àwọn átọ̀mù ilẹ̀ ni o ti kójọ

Ko si asopọ láàrin ọpọlọ ati iwa bi tii wù bi tii mọ

Ṣùgbọ́n ìròrí pe àwùjọ ni ibi ti ìwà ti jáde, eleyii jẹ ìròrí àjèjì; tori pe èèyàn ni ìwà kàn gẹ́gẹ́ bí eeyan, kii ṣe àwùjọ gẹ́gẹ́ bí àwùjọ.

Lẹ́yìn naa, àwùjọ wa latara irú ẹ̀yà ohun èlò ti ara, ti o ba ri bẹẹ, akojọpọ àwọn òdo, lẹẹkan si, ko lee mu jade àyàfi odo, bawo wa ni àwùjọ ṣe mu iwa jáde, ti ko si wulẹ̀ si lára àgbáyé àwọn eeyan gan tẹ́lẹ̀?

Lẹ́yìn naa, ti o ba jẹ pe ọrọ yii tọ̀nà ni, ti a si gba pe ìwà jáde latara àwùjọ, a jẹ pe nǹkan ti Nazi sọ tọna nìyẹn nipa pípa nǹkan ti o ba yatọ si i run; tori pe àwùjọ fara mọ ọn.

Nigba ti gbogbo ayé pinnu lati gbe Nazi lọ si ilé-ẹjọ́, ipinnu yii wáyé ni ìbámu si pe ìwà jẹ nǹkan ti a tú silẹ, kii ṣe pe àwùjọ ni o bi i, bibẹẹkọ ko ba ti rọrùn fun wọn lati gbe Nazi lọ si ilé-ẹjọ́, wọn kò bá tí gbọ́ ọ yé gan pe o ṣe àṣìṣe gan.

Àwọn ìwà dá dúró kúrò lára àwùjọ ni, nǹkan ti o ba tọ̀nà, ohun ti o tọna naa ni lọdọ àwùjọ rere ati àwùjọ burúkú.

Ohun tí kò bá tọ̀nà, ko le tọna lọdọ àwùjọ rere ati àwùjọ burúkú.

10 https://en.wikipedia.org/wiki/Aktion_T4 “

Ìwà ni itumọ ti o kọjá ọpọlọ ati àwùjọ

19- Ọlọhun ju ẹyọkan lọ ninu awọn ọlaju orí ilẹ̀, kilode ti a fi wa ni ki a gba Allahu nikan gbọ́ ni pàtó?

Esi: Ko si ẹni ti a le maa jọ́sìn fun ni gbogbo ẹsin orí ilẹ̀ ayafi Allāhu

Iyapa wa pẹ̀lú àwọn ẹsin ti o ṣẹku ni pe wọn n sin àwọn ọlọhun kéékèèké mọ Ọlọhun Allāhu, gẹgẹ bii Jesu ati ẹ̀mí mímọ́ ninu ẹsin Kristẹni, ati Vishnu, Shiva àti Brahma ninu ẹsin Hindu... àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Gbogbo ẹsin pata ni wọn ni ìgbàgbọ́ ninu Ọlọhun kan ṣoṣo, Oun si ni O da ayé ní ọ̀dọ̀ wọn

Ṣugbọn wọn tun mu àwọn ọlọ́run mìíràn papọ mọ Ọlọhun Allaah, ko ju bẹẹ lọ.

Titi de orí oosa àwọn ẹlẹbọ, wọn ko mu àwọn gangan ni ọlọhun, bi ko ṣe pe wọn gba pe Ọlọhun ni Aṣẹda, ṣùgbọ́n wọn n fi wọ́n ṣe alárinà fun Ọlọhun ni:

﴿وَلَئِن سَأَلۡتَهُم مَّنۡ خَلَقَ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضَ وَسَخَّرَ ٱلشَّمۡسَ وَٱلۡقَمَرَ لَيَقُولُنَّ ٱللَّهُۖ فَأَنَّىٰ يُؤۡفَكُونَ٦١﴾ [العنكبوت: 61]

{Tí o bá bi wọ́n léèrè pé: "Ta ni Ó dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀, tí Ó sì rọ òòrùn àti òṣùpá?", dájúdájú wọ́n á wí pé: "Alla-hu ni." Nítorí náà, báwo ni wọ́n ṣe ń ṣẹ́rí wọn kúrò níbi òdodo? {61}} [ Suuratul Ankabuut.]

Sheikhul Islam Ibnu Taymiyyah sọ pe: Ẹni tí o ba lérò pé àwọn ti wọn n jọ́sìn fún àwọn òrìṣà ni adisọkan pe àwọn òrìṣà yẹn ni wọn da ayé, tabi pe àwọn ni wọn n rọ ojo[11]

[11] Majmuu'hul Fataawaa, volume 1, oju-iwe 359

Will Durant pinnu pé ìpilẹ̀ṣẹ̀ ẹ̀sìn Híńdù kèfèrí n pàpà ṣẹ́rí lọ síbi ìgbàgbọ́ nínú Ọlọ́run Kan ṣoṣo náà ni, ó sì sọ nípa àwọn ọlọ́run Híńdù pé: "Àwọn òrìṣà ẹgbẹẹgbẹ̀rún wọ̀nyí dà bí ohun tí àwọn ṣọ́ọ̀ṣì Kristẹni ń ṣe láti sọ ẹgbẹẹgbẹ̀rún àwọn ẹni mímọ́ di mímọ́. Kí ó má ṣe rú wúyẹ́ ni ọkàn ẹlẹ́sìn hindu bi tii wù bi tii mọ pe àwọn òrìṣà ti ko ni onka yii ni aṣáájú ti o ga jù. [12]

Ìròyìn tí wọ́n fi ránṣẹ́ sí ìjọba ilẹ̀ Gẹ̀ẹ́sì ní Íńdíà nígbà tí àwọn Gẹ̀ẹ́sì gba ìlú Íńdíà sọ pé: "Àbájáde gbogbogboo tí ìgbìmọ̀ náà dé nínú ìwádìí náà ni pé ọ̀pọ̀ jù lọ àwọn ará Íńdíà ní ìgbàgbọ́ tó fìdí múlẹ̀ nínú Ọlọ́run Gíga Jù Lọ kan[13].

Ẹyọkan ni Ọlọhun ninu gbogbo ẹsin orí ilẹ̀:

﴿۞ وَلَا تُجَٰدِلُوٓاْ أَهۡلَ ٱلۡكِتَٰبِ إِلَّا بِٱلَّتِي هِيَ أَحۡسَنُ إِلَّا ٱلَّذِينَ ظَلَمُواْ مِنۡهُمۡۖ وَقُولُوٓاْ ءَامَنَّا بِٱلَّذِيٓ أُنزِلَ إِلَيۡنَا وَأُنزِلَ إِلَيۡكُمۡ وَإِلَٰهُنَا وَإِلَٰهُكُمۡ وَٰحِدٞ وَنَحۡنُ لَهُۥ مُسۡلِمُونَ ٤٦﴾ [العنكبوت: 46]

{Ọlọ́hun yín, Ọlọ́hun Ọ̀kan ṣoṣo ni {46}.} [[46] Suuraa al-ankabuut.]

Àwọn òrìṣà ati awọn ọlọhun abara ko jẹ nkan kan ayafi alárinà Kèfèrí fun Ọlọhun:

﴿أَلَا لِلَّهِ ٱلدِّينُ ٱلۡخَالِصُۚ وَٱلَّذِينَ ٱتَّخَذُواْ مِن دُونِهِۦٓ أَوۡلِيَآءَ مَا نَعۡبُدُهُمۡ إِلَّا لِيُقَرِّبُونَآ إِلَى ٱللَّهِ زُلۡفَىٰٓ إِنَّ ٱللَّهَ يَحۡكُمُ بَيۡنَهُمۡ فِي مَا هُمۡ فِيهِ يَخۡتَلِفُونَۗ إِنَّ ٱللَّهَ لَا يَهۡدِي مَنۡ هُوَ كَٰذِبٞ كَفَّارٞ ٣﴾ [الزمر: 3]

---

12 Ìtàn ọlaju, Will Durant, ìdì 3, oju-iwe 209

13 Ìwé ìwádìí ti o ṣáájú

{Àwọn tí wọ́n sì mú àwọn aláfẹ̀yìntì kan yàtọ̀ sí Alla-hu, (wọ́n wí pé) : "A ò jọ́sìn fún wọn bí kò ṣe pé nítorí kí wọ́n lè mú wa súnmọ́ Alla-hu pẹ́kípẹ́kí ni} {3}.} [Suuratu Zumar].

20- Ti ọmọniyan ba ṣe nǹkan ti ko ni bùkátà si, eleyii ko ni anfaani, Ọlọhun ko ni bùkátà si wa, kilode ti O fi wa da wa ?

Esi : Ìròrí pé bùkátà ṣe rẹ́gí pẹ̀lú ìranù, èyí ko bá ọgbọ́n mu.

Ọgbọ́n ni o ṣe régí pẹ̀lú bukata, kii ṣe ìranù.

Dókítà ti o jẹ ọlọ́rọ̀ ti o ní òkìkí rere, irú rẹ lè wo àwọn èèyàn sàn láìní bukata si nǹkan kan lọ́dọ̀ wọn, yoo kan wo wọn sàn fun anfaani wọn, nibi, a o nii sọ pé iranu ni nǹkan ti o ṣe !

Ọgbọ́n ati erongba ńlá ti a fi n ṣe nǹkan, ko nii ṣe pẹlu bùkátà/iranu

Ọkan ninu awọn omuwẹ lè la ọmọ kekere kan lati fi ṣaanu rẹ, ki o si fi i silẹ lẹyin igba naa, ti o si maa lọ lai reti pe ki awọn eeyan ọmọ kekere yii o yin in. Ibi yii, nǹkan ti o ṣe yii, kii ṣe pe ṣe e tori bukaata abi iranu kan, ṣugbọn iṣesi alapọnle ati erongba ti o dara ati iwa gidi ni.

Ko si asopọ láàrin bibukaata si nǹkan ati iranu [14]

O n bẹ ninu Saheeh-Muslim nibi Hadeesi Qud'sii ti Ọlọhun ti O ga ti sọ pe:Ẹyin ẹrusin mi, ti o ba jẹ pe awọn akọkọda ati igbẹyin inu yin, eeyan inu yin ati alijannu inu yin, ki wọn o wa lori ọkan ọkunrin kan ti o bẹru Ọlọhun ju ninu yin, ko le nkankan kun ninu ọla mi, Ẹyin ẹrusin mi, ti o ba jẹ pe awọn akọkọda ati igbẹyin inu yin, eeyan inu yin ati alijannu inu yin, ki wọn o wa lori ọkan ọkunrin kan ti o ṣẹ Ọlọhun ju ninu yin, ko din nkankan kun ninu ọla mi, ẹyin ẹrusin mi, eleyii ni awọn iṣẹ yin ti maa ṣe akọsilẹ rẹ fun ti maa si pe ẹsan rẹ fun yin, ẹniti o ba ri daadaa, ki o yaa

[14] Ìṣẹ̀lẹ̀ bíbu ẹnu àtẹ̀ lu ẹsin ninu ìmọ̀ filọsọfi ti òde òní, Dr. Sultan Al-Umayri, ìwé-àkọgboyèjáde fun oyè dókítà.

dupẹ fun Ọlọhun, eniti o ba si ri ohun ti o yatọ si i, ki o ma bu ẹni kankan ayafi ẹmi ara rẹ[15].

Ọlọhun rọrọ kuro lọdọ gbogbo aye.

Kirakita wa, igbiyanju wa ati iṣẹ wa, torí ara wa náà ni :

﴿وَمَن جَٰهَدَ فَإِنَّمَا يُجَٰهِدُ لِنَفۡسِهِۦٓۚ إِنَّ ٱللَّهَ لَغَنِيٌّ عَنِ ٱلۡعَٰلَمِينَ ٦﴾ [العنكبوت: 6]

[Ẹnikẹ́ni tí ó bá gbìyànjú, ó ń gbìyànjú fún ẹ̀mí ara rẹ̀ ni. Dájúdájú Alla-hu ni Ọlọ́rọ̀ tí kò bùkátà sí gbogbo ẹ̀dá. {6}}. [Suuratul Ankabuut]

Awa si mọ pe ọgbọn kan n bẹ fun Ọlọhun nibi dida ẹda Rẹ koda ki awa ma mọ ọn, àìní ìmọ̀ alaisan nípa ọgbọn dokita kò túmọ̀ si pe iranu ni ìpinnu dókítà.

Imọ nípa ọgbọn Ọlọhun, ko jẹ dandan fún un ki o ni agbọye gbogbo nnkan ti o rọ̀ mọ́ ọgbọ́n naa, nini agbọye díẹ̀ nipa rẹ ti tó

O to ki a lọ mọ pe a jẹ ẹniti wọn la ijọsin fun Ọlọhun bọ lọrun, bakannaa ki a si lọ mọ pe ọgbọn Ọlọhun n bẹ, eleyii yoo ma to wa ni àpapọ̀, lai jẹ bẹẹ, awa naa o da bii ẹniti o ṣe keferi si gbogbo nnkan ti ko gbọye :

﴿بَلۡ كَذَّبُواْ بِمَا لَمۡ يُحِيطُواْ بِعِلۡمِهِۦ وَلَمَّا يَأۡتِهِمۡ تَأۡوِيلُهُۥۚ كَذَٰلِكَ كَذَّبَ ٱلَّذِينَ مِن قَبۡلِهِمۡۖ فَٱنظُرۡ كَيۡفَ كَانَ عَٰقِبَةُ ٱلظَّٰلِمِينَ ٣٩﴾ [يونس: 39]

{Kò rí bẹ́ẹ̀, wọ́n pe ohun tí wọn kò ní ìmọ̀ rẹ̀ nírọ́ ni. Àti pé ìmúṣẹ ọ̀rọ̀ Rẹ̀ kò tí ì dé bá wọn (ni wọ́n fi pè é nírọ́}.". {Suuratu Yuunus : 39}

Ọba Ọjọgbọn ni Ọlọhun, O si da wa nitori ọgbọ́n kan ni.

[15] Saheeh-Muslim Ha:2577

Ọlọhun nikan ni O ni ẹtọ ki a maa jọsin fun Un.

Ijọsin ko ni ẹtọ si ẹnikan kan ayafi Ọlọhun, tori pe Oun ni Adẹdaa ti O mu wa bẹ latara aisi, Ọba ti O mọ sọ pe :

﴿يَـٰٓأَيُّهَا ٱلنَّاسُ ٱعۡبُدُواْ رَبَّكُمُ ٱلَّذِي خَلَقَكُمۡ وَٱلَّذِينَ مِن قَبۡلِكُمۡ لَعَلَّكُمۡ تَتَّقُونَ ٢١﴾ [البقرة: 21]

{Ẹ̀yin èniyàn, ẹ jọ́sìn fún Olúwa yín, Ẹni tí Ó da ẹ̀yin àti àwọn t'ó ṣíwájú yín, nítorí kí ẹ lè ṣọ́ra (fún ìyà Iná). {21} [Suuratul Baqarah].

Oun ni O tọ wa sọna, Oun ni O si tun gbe ofin kalẹ, ti O si pebubu kadara, O si tun paṣẹ, O si tun kọ. :

﴿إِنَّ رَبَّكُمُ ٱللَّهُ ٱلَّذِي خَلَقَ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضَ فِي سِتَّةِ أَيَّامٖ ثُمَّ ٱسۡتَوَىٰ عَلَى ٱلۡعَرۡشِۖ يُغۡشِي ٱلَّيۡلَ ٱلنَّهَارَ يَطۡلُبُهُۥ حَثِيثٗا وَٱلشَّمۡسَ وَٱلۡقَمَرَ وَٱلنُّجُومَ مُسَخَّرَٰتِۭ بِأَمۡرِهِۦٓۗ أَلَا لَهُ ٱلۡخَلۡقُ وَٱلۡأَمۡرُۗ تَبَارَكَ ٱللَّهُ رَبُّ ٱلۡعَٰلَمِينَ ٥٤﴾ [الأعراف: 54]

{TiRẹ̀ ni ẹ̀dá àti àṣẹ. Ìbùkún ni fún Alla-hu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá. {54} [Suuratul A'raf.].

Kii ṣe dida nikan ni n bẹ fun Ọlọhun, ṣugbọn aṣẹ tun n bẹ fun Un, awa o si maa tẹle aṣẹ Rẹ

Iwọ Ọlọhun ni ìjọsìn lori ẹrusin Rẹ, Oun ni O da wa ti O si tun mu wa wa laaye, O si n pese jijẹ-mimu fun wa, O si tun fi wa mọ ọna ododo, O si ran awọn ojiṣẹ Rẹ si wa lati wa fun wa ni iro ati lati dan wa wo, tani o maa ṣe iṣẹ́ rere julọ nínú wa, ìjọsìn si ni ẹtọ Ọlọhun le wa lori:

﴿ٱلَّذِي خَلَقَ ٱلۡمَوۡتَ وَٱلۡحَيَوٰةَ لِيَبۡلُوَكُمۡ أَيُّكُمۡ أَحۡسَنُ عَمَلٗاۚ وَهُوَ ٱلۡعَزِيزُ ٱلۡغَفُورُ ٢﴾ [الملك: 2]

(Ẹni tí Ó dá ikú àti ìṣẹ̀mí nítorí kí ó lè dan yín wò; èwo nínú yín l'ó máa ṣe iṣẹ́ rere jùlọ. Òun sì ni Alágbára, Aláforíjìn. {2} [[2]. Suuratul MulkIle].

aye wa ati ọrun wa o le duro deede afi pẹlu ijọsin, awọn iwa wa naa o le da afi pẹlu ẹ, ijọsin maa n kọ fúnni kuro nibi iwa ibajẹ ati awọn aburu, atipe pẹlu ijọsin ni igbesi aye awọn eeyan o fi daa, Ọlọhun wa ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿ٱتۡلُ مَآ أُوحِيَ إِلَيۡكَ مِنَ ٱلۡكِتَٰبِ وَأَقِمِ ٱلصَّلَوٰةَۖ إِنَّ ٱلصَّلَوٰةَ تَنۡهَىٰ عَنِ ٱلۡفَحۡشَآءِ وَٱلۡمُنكَرِۗ وَلَذِكۡرُ ٱللَّهِ أَكۡبَرُۗ وَٱللَّهُ يَعۡلَمُ مَا تَصۡنَعُونَ ٤٥﴾ [العنكبوت: 45]

{Dájúdájú ìrun kíkí ń kọ ìwà ìbàjẹ́ àti aburú}[45].} [Suuratul Ankabuut]

A kò le jere pẹlu alijanna afi pẹlu ijọsin, oun náà ni igbala ni ọjọ ikẹyin ati irọrun ni ile aye."

Ijọsin wa fun wa ati fun daadaa wa, o jẹ dandan le wa lori sí Ọlọhun ti O tobi ti O gbọnngbọn; nítorí pé Òun ni O da wa, àti pé anfaani rẹ maa ṣeri pada wa ba wa nikan, ìkùdíẹ̀-káàtó nibẹ naa si maa ṣeri pada wa ba wa nikan. "

Alujanna jẹ nkan to wọn, ẹniti o ba fẹ alujanna yoo ṣiṣe fun un ni, awa ni a si n bukaata si Ọlọhun, ti a n bukaata si ijọsin fun Un, Oun ni Ọba ti O rọrọ kuro lọdọ wa ati kuro lọdọ gbogbo ẹda Rẹ. "

21- Bawo ni a ṣe maa da Ọlọhun mọ?"

Esi: A maa da Ọlọhun mọ pẹlu ọna to pọ gan, sugbọn a maa darukọ awọn ọna mẹrin nibi"

Ọna àkọ́kọ́: A maa da Ọlọhun mọ nipasẹ adamọ to ni àlàáfíà."

Ọmọniyan pẹlu adamọ rẹ o mọ pe dajudaju Adẹdaa kan n bẹ fun un, waa mọ pẹ̀lú adamọ pe Adẹdaa kan n bẹ fun ẹ ti O da ẹ bi o ṣe ri yii, ati pẹlu awọn ẹya yii, ati adamọ yii ati iṣẹ yii ati ṣíṣe nǹkan daadaa ti o yani lẹnu. “

Bakannaa ọmọniyan, pẹlu adamọ rẹ, o mọ pe oun ni bukaata si jijọsin fun Adẹdaa rẹ, yoo si tun mọ bakanna pẹlu adamọ rẹ pe oun n bukaata si Adẹdaa rẹ ni gbogbo ìgbà. Níní bukaata si Ọlọhun yii yoo maa lekun ni asiko ilekoko.

Adamọ dida Ọlọhun mọ, wọn da a mọ gbogbo ẹda ni, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿فَأَقِمۡ وَجۡهَكَ لِلدِّينِ حَنِيفٗاۚ فِطۡرَتَ ٱللَّهِ ٱلَّتِي فَطَرَ ٱلنَّاسَ عَلَيۡهَاۚ لَا تَبۡدِيلَ لِخَلۡقِ ٱللَّهِۚ ذَٰلِكَ ٱلدِّينُ ٱلۡقَيِّمُ وَلَٰكِنَّ أَكۡثَرَ ٱلنَّاسِ لَا يَعۡلَمُونَ ٣٠﴾ [الروم: 30]

{Nítorí náà, dojú rẹ kọ ẹ̀sìn náà, (kí o jẹ́) olùdúró-déédé-nínú-ẹ̀sìn, ẹ̀sìn àdámọ̀ Alla-hu èyí tí Ó dá mọ́ àwọn ènìyàn. Kò sì sí ìyípadà fún ẹ̀dá Alla-hu. Ìyẹn ni ẹ̀sìn t'ó fẹsẹ̀rinlẹ̀, ṣùgbọ́n ọ̀pọ̀lọ́pọ̀ àwọn ènìyàn kò mọ̀. {30}} [(30) Suuratu Rûm].

Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe :

﴿وَإِذۡ أَخَذَ رَبُّكَ مِنۢ بَنِيٓ ءَادَمَ مِن ظُهُورِهِمۡ ذُرِّيَّتَهُمۡ وَأَشۡهَدَهُمۡ عَلَىٰٓ أَنفُسِهِمۡ أَلَسۡتُ بِرَبِّكُمۡۖ قَالُواْ بَلَىٰ شَهِدۡنَآۚ أَن تَقُولُواْ يَوۡمَ ٱلۡقِيَٰمَةِ إِنَّا كُنَّا عَنۡ هَٰذَا غَٰفِلِينَ ١٧٢﴾ [الأعراف: 172]

{Rántí) nígbà tí Olúwa rẹ gba àdéhùn lọ́wọ́ àwọn ọmọ A-dam, Ó fa àrọ́mọdọ́mọ wọn jáde láti (ìbàdí ní) ẹ̀yìn (bàbá ńlá) wọn, Ó sì fi wọ́n ṣe ẹlẹ́rìí lórí ara wọn pé: "Ṣé Èmi kọ́ ni Olúwa yín ni?" Wọ́n sọ pé: "Rárá – (Ìwọ ni Olúwa wa) – a jẹ́rìí sí i." Nítorí kí ẹ má baà sọ ní Ọjọ́ Àjíǹdé pé: "Dájúdájú àwa jẹ́ aláìmọ̀ nípa èyí." {172} [Suuratul A'raf].

Siwaju ki wọn o to da wa ni wọn ti da wa lori dida Ọlọhun mọ, wọn si tun da wa lori ijẹ ẹru fun Un, mimọ ni fun Un. "( وَأَشْهَدَهُمْ عَلَىٰٓ أَنفُسِهِمْ أَلَسْتُ بِرَبِّكُمْ قَالُوا بَلَىٰ شَهِدْنَا). (Ó sì fi wọ́n ṣe ẹlẹ́rìí lórí ara wọn pé: "Ṣé Èmi kọ́ ni Olúwa yín ni?" Wọ́n sọ pé: "Rárá – (Ìwọ ni Olúwa wa) - a jẹ́rìí sí i) Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ ninu Hadiisi ti a fi ẹnu ko lori nini alaafia rẹ pe:" Kò sí eyikeyi ninu ọmọ ti wọn ba bi afi ki wọn bi i lórí adamọ "[16]

Torí náà wọn bi gbogbo wa lori oju ọna adamọ yii, oju ọna adamọ yii si to gbogbo eeyan ti o fẹ ododo lati fi ṣe itọka lori ododo ki o si gba fun ododo yii nigba to ba ti han si i. "

Oju ọna adamọ yii, koda awọn to fi n le julọ ninu awọn eeyan ni iṣe keferi o le tako o, pataki julọ ni awọn akoko to le koko, gbogbo awọn eeyan pata ni wọn maa n sa lọ si ọdọ Ọlọhun ni awọn akoko ilekoko ti wọn maa gbagbe nǹkan ti wọn mu ni orogun pọ mọ Ọlọhun:

﴿وَإِذَا مَسَّكُمُ ٱلضُّرُّ فِى ٱلْبَحْرِ ضَلَّ مَن تَدْعُونَ إِلَّآ إِيَّاهُ ۖ فَلَمَّا نَجَّىٰكُمْ إِلَى ٱلْبَرِّ أَعْرَضْتُمْ ۚ وَكَانَ ٱلْإِنسَٰنُ كَفُورًا ﴿٦٧﴾﴾ [الإسراء: 67]

[16] Saheeh-Muslim Ha:2658

{Nígbà tí ìnira bá fọwọ́ bà yín lójú omi, ẹni tí ẹ̀ ń pè yó sì dòfo (mọ yín lọ́wọ́) àfi Òun nìkan (Alla-hu). Nígbà ti Ó bá sì gbà yín là (tí ẹ) gúnlẹ̀, ẹ̀ ń gbúnrí (kúrò lọ́dọ̀ Rẹ̀). Ènìyàn sì jẹ́ aláìmoore. {67}.} [Suuratul Israa].

Ti ọmọniyan ba wa ninu ipọnju ti o le koko, ti o si n mọ iparun lara, ko nii ke pe ẹnikan kan ayafi Ọlọhun, yoo si pada gbagbe gbogbo ṣiṣe ẹbọ rẹ; nini imọkanga si Ọlọhun nibi adua ni asiko ilekoko, okùnfà rẹ̀ ni adamọ ti o ni alaafia ti nbẹ lara gbogbo eeyan.

Ọkan ninu awọn olori America tii ṣe Eisenhower - ti o jẹ olori fun ijọ awọn ọmọ ologun America nibi ogun agbaye ẹlẹẹkeji, o n sọ lẹyin igba ti o rí bi awọn ọmọ ologun ṣe n ṣeri pada si ipilẹ ti o jẹ abinibi ni asiko ti o lewu, pé: “Ko si awọn ti ko gbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun ninu awọn iho naa”[17].

Ninu iho yii ni asiko ogun, ko si ẹnikan kan ti o tako bibẹ Ọlọhun, oníkálukú n ṣeri pada si ọdọ Ọlọhun ni, eleyii ni adamọ otitọ ti gbogbo ẹda maa n jẹ́wọ́ rẹ̀ ni asiko ilekoko.

Oju ọna ẹlẹẹkeji lati fi mọ Ọlọhun naa ni laakaye: A o maa mọ Ọlọhun pẹlu laakaye.

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿أَمۡ خُلِقُواْ مِنۡ غَيۡرِ شَيۡءٍ أَمۡ هُمُ ٱلۡخَٰلِقُونَ ٣٥﴾ [الطور: 35]

17 https://en.wikipedia.org/wiki/There_are_no_atheists_in_foxholes “

{Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá ? Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni ? {35}} [Sūratu Tūr].

Pẹlu laakaye, awọn nǹkan mẹta kan n bẹ ti o ṣee ṣe ki o tìdí ẹ̀ yọ ti ko si ẹẹkẹrin fun wọn :

Àkọ́kọ́ : ki o jẹ pe wọn da wa lai ni Aṣẹ̀dá (Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá ?) eleyii ko ṣee ṣe, bawo ni wọn yoo ṣe da wa lai nii ni Aṣẹ̀dá kankan ?

Ẹlẹẹkeji : ki o jẹ pe awa ni a da ara wa (Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni ?) eleyii naa o ṣee ṣe, bawo ni maa ṣe da ara mi ṣiwaju ki wọn o too da mi ?

Ti o ba ri bẹ́ẹ̀, pẹlu laakaye, o maa ṣẹku ohun kẹta ti o ṣee ṣe ki o ṣẹlẹ̀, oun si ni aaya alapọn-ọnle yii kò sọrọ nipa rẹ nitori pe oun ni nǹkan ti o kọkọ maa wa si làákàyè, oun si ni pe a ni Aṣẹ̀dá ti O da wa.

A o maa mọ Ọlọhun pẹlu laakaye.

Ọna ẹlẹẹkẹta lati fi mọ Ọlọhun naa ni wiwoye si awọn ẹda Ọlọhun :

Wiwoye si ẹda Ọlọhun, yoo jẹ ki a mọ titobi Ọlọhun ti O tobi :

﴿قُلِ ٱنظُرُواْ مَاذَا فِي ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِۚ وَمَا تُغۡنِي ٱلۡأٓيَٰتُ وَٱلنُّذُرُ عَن قَوۡمٖ لَّا يُؤۡمِنُونَ ١٠١﴾ [يونس: 101]

{Sọ pé: "Ẹ wòye sí n-ǹkan tí ń bẹ nínú sánmọ̀ àti ilẹ̀. {101}} [(101) Suuratu Yûnus.]

Gbogbo igba ti a ba wo ẹda Ọlọhun daadaa ati eemọ bi O ṣe da wọn dáadáa, ni a o maa lekun ni imọ nípa Ọlọhun síi.

Eleyii ni ohun ti a sọrọ nipa rẹ ṣaaju nibi ẹri mimu nnkan bẹ ati ẹri ini akolekan ati ṣíṣe dáadáa.

Ọna ẹlẹẹkẹrin lati fi mọ Ọlọhun naa ni lati ipasẹ awọn ojiṣẹ:

Eleyii ni ọna ti o tobi ju lati fi mọ Ọlọhun ti O tobi, oun naa ni ki a mọ Ọlọhun nípasẹ̀ awọn ojiṣẹ Rẹ ati awọn Anabi Rẹ, Awọn ojiṣẹ ni wọn fun wa ni ìró nipa Ọlọhun, wọn si tun fun wa ni iro nipa awọn iroyin Rẹ, wọn si tun fun wa ni iro nipa paapa Rẹ (Ọba ti O mọ). Nípasẹ̀ awọn Anabi ni a fi mọ Ọlọhun pẹlu awọn orukọ Rẹ ati awọn iroyin Rẹ, a si tun mọ bi a o ṣe maa jọsin fun Ọlọhun ati bi a o ṣe maa sunmọ Ọn, a si tun mọ bi a o ṣe la ni ọjọ iṣiro kuro nibi iya Ọlọhun. Awọn ojiṣẹ pe awọn eeyan lọ si ijọsin fun Ọlọhun, tabi ki a sọ pé wọn pe awọn eeyan lati pada si àdánidá ti wọn da wọn le lórí, ki wọn si maa jọsin fun Ọlọhun bi O ṣe paṣẹ rẹ.

Awọn ojiṣẹ ni tọ awọn eeyan sọna lọ si oju ọna ododo ati ọla:

﴿رُّسُلٗا مُّبَشِّرِينَ وَمُنذِرِينَ لِئَلَّا يَكُونَ لِلنَّاسِ عَلَى ٱللَّهِ حُجَّةُۢ بَعۡدَ ٱلرُّسُلِۚ وَكَانَ ٱللَّهُ عَزِيزًا حَكِيمٗا ١٦٥﴾ [النساء: 165]

{(A ṣe wọ́n ní) Òjíṣẹ́, oníròó ìdùnnú àti olùkìlọ̀ nítorí kí àwíjàre má lè wà fún àwọn ènìyàn lọ́dọ̀ Alla-hu lẹ́yìn (tí) àwọn Òjíṣẹ́ (ti jíṣẹ́). Alla-hu sì ń jẹ́ Alágbára, Ọlọ́gbọ́n. {165}.}. [Suuratun- Nisaa']

Ìró ti àwọn anọbi ati awọn ojiṣẹ yii fun wa nípa Ọlọhun, ati ìkún wọn lọ́wọ́ pẹ̀lú iṣẹ́ ìyanu, ko nii jẹ ki ẹni kankan ni àwíjàre lórí Ọlọhun ni ọjọ́ igbende.

Ọlọhun fun ọ ni adamọ ti waa fi da Aṣẹda rẹ mọ, O si fun ọ ni làákàyè ati ìwòye sí àwọn ẹ̀dá Rẹ, O si ran àwọn ojiṣẹ si ẹ, o o bukata si nǹkan kan mọ lọ́dọ̀ Ọlọhun.

22- Àwọn ẹsin pọ, kilode ti o fi jẹ Islam?

Esi: Islam kii ṣe ẹsin kan láàárín àwọn ẹsin

Adisọkan Islam ba adisọkan gbogbo àwọn anọbi Májẹ̀mú lailai mu

Islam ni àtúnṣe fun ọ̀nà àwọn ẹsin yókù ti wọn ti ṣìnà, ati dídá adisọkan àwọn anọbi májẹ̀mú lailai

Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿۞ شَرَعَ لَكُم مِّنَ ٱلدِّينِ مَا وَصَّىٰ بِهِۦ نُوحًا وَٱلَّذِيٓ أَوۡحَيۡنَآ إِلَيۡكَ وَمَا وَصَّيۡنَا بِهِۦٓ إِبۡرَٰهِيمَ وَمُوسَىٰ وَعِيسَىٰٓۖ أَنۡ أَقِيمُواْ ٱلدِّينَ وَلَا تَتَفَرَّقُواْ فِيهِۚ كَبُرَ عَلَى ٱلۡمُشۡرِكِينَ مَا تَدۡعُوهُمۡ إِلَيۡهِۚ ٱللَّهُ يَجۡتَبِيٓ إِلَيۡهِ مَن يَشَآءُ وَيَهۡدِيٓ إِلَيۡهِ مَن يُنِيبُ ١٣﴾ [الشورى: 13]

(Alla-hu) ṣe ní òfin fun yín nínú ẹ̀sìn (’Isla-m) ohun tí Ó pa ní àṣẹ fún (Ànábì) Nu-h àti èyí tí Ó fi ránṣẹ́ sí ọ, àti ohun tí A pa láṣẹ fún (Ànábì) ’Ibrọ̄hi-m, (Ànábì) Mu-sa- àti (Ànábì) ‘I-sa- pé kí ẹ gbé ẹ̀sìn náà dúró. Kí ẹ sì má ṣe pín sí ìjọ ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ nínú rẹ̀. Wàhálà l’ó jẹ́ fún àwọn ọ̀ṣẹbọ nípa n̄ǹkan tí ò ń pè wọ́n sí (níbi mímú Alla-hu ní ọ̀kan ṣoṣo). Alla-hu l’Ó ń ṣẹ̀ṣà ẹni tí Ó bá fẹ́ sínú ẹ̀sìn Rẹ̀ (tí ò ń pè wọ́n sí). Ó sì ń fi ọ̀nà mọ ẹni tí ó bá ń ṣẹ́rí padà sí ọ̀dọ̀ Rẹ̀ (nípasẹ̀ ìronúpìwàdà). {13} “Suuratu Shuura.

Islam ko da bii àwọn ẹsin to ṣẹku, bi ko ṣe pe oun gan ni ìpìlẹ̀ àwọn ẹsin

Ki ni a n pe ni Islam?

Esi: Islam ni: Jíjupá-jusẹ̀ sílẹ̀ àti ìtẹríba fun Ọlọhun

Ọlọhun ti O ga sọ pe:

﴿وَمَنۡ أَحۡسَنُ دِينٗا مِّمَّنۡ أَسۡلَمَ وَجۡهَهُۥ لِلَّهِ وَهُوَ مُحۡسِنٞ وَٱتَّبَعَ مِلَّةَ إِبۡرَٰهِيمَ حَنِيفٗاۗ وَٱتَّخَذَ ٱللَّهُ إِبۡرَٰهِيمَ خَلِيلٗا ١٢٥﴾ [النساء: 125]

{Ta l’ó dára ní ẹ̀sìn ju ẹni tí ó jura rẹ̀ sílẹ̀ fún Alla-hu, olùṣe-rere sì tún ni, ó tún tẹ̀lé ẹ̀sìn (Ànábì) ’Ibrọ̄hi-m, olùdúró-déédé-nínú-’Isla-m? Alla-hu sì mú (Ànábì) ’Ibrọ̄hi-m ní àyànfẹ́. {125} [Suuratun- Nisaa']

Ìtumọ̀ “AS’LAMA WAJ’HAHUU LILLAAH” ni pe: O Jíjupá-jusẹ̀ sílẹ̀ fun Ọlọhun, o si tẹriba fun un, eyi ni èèyàn ti ẹsin rẹ dara jù.

Allah tun sọ pe:

﴿وَلِكُلِّ أُمَّةٖ جَعَلۡنَا مَنسَكٗا لِّيَذۡكُرُواْ ٱسۡمَ ٱللَّهِ عَلَىٰ مَا رَزَقَهُم مِّنۢ بَهِيمَةِ ٱلۡأَنۡعَٰمِۗ فَإِلَٰهُكُمۡ إِلَٰهٞ وَٰحِدٞ فَلَهُۥٓ أَسۡلِمُواْۗ وَبَشِّرِ ٱلۡمُخۡبِتِينَ ٣٤﴾ [الحج: 34]

{Ọlọ́hun yín, Ọlọ́hun Ọ̀kan ṣoṣo ni. Òun ni kí ẹ jẹ́ mùsùlùmí fún. Kí o sì fún àwọn ọlọ́kàn ìrẹ̀lẹ̀, àwọn olùfọkànbalẹ̀ sọ́dọ̀ Alla-hu ní ìró ìdùnnú. {34}} [34] Suuratul Hajj

Ìtumọ̀ “FALAHUU AS’LIMUU” ni pe: Ẹ jupá-jusẹ̀ sílẹ̀ fún ìdájọ́ Rẹ.

Àwọn aaya yii n ṣe anfaani pe itumọ Islam gan ni jijupa-jusẹ silẹ pátápátá fun Ọlọhun, ati titẹriba fun Un, ati titẹle òfin Rẹ ati ìlànà Rẹ pẹ̀lú iyọnu ati itẹwọgba, eyi gan ni pàápàá Islam.

Islam ni jijupa-jusẹ silẹ fun Ọlọhun nibi idajọ Rẹ ati òfin Rẹ.

Islam ni ẹsin Ọlọhun fun gbogbo ẹ̀dá abara, Ọlọhun ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿إِنَّ ٱلدِّينَ عِندَ ٱللَّهِ ٱلۡإِسۡلَٰمُۗ وَمَا ٱخۡتَلَفَ ٱلَّذِينَ أُوتُواْ ٱلۡكِتَٰبَ إِلَّا مِنۢ بَعۡدِ مَا جَآءَهُمُ ٱلۡعِلۡمُ بَغۡيَۢا بَيۡنَهُمۡۗ وَمَن يَكۡفُرۡ بِـَٔايَٰتِ ٱللَّهِ فَإِنَّ ٱللَّهَ سَرِيعُ ٱلۡحِسَابِ ١٩﴾ [آل عمران: 19]

{{Dájúdájú ẹ̀sìn t'ó wà lọ́dọ̀ Alla-hu ni 'Isla-m} {19}} [[19] Suuratul Al Imran].

Islam ni ẹsin ti Ọlọhun ko nii gba ẹsin mìíràn yatọ sii.

﴿وَمَن يَبۡتَغِ غَيۡرَ ٱلۡإِسۡلَٰمِ دِينٗا فَلَن يُقۡبَلَ مِنۡهُ وَهُوَ فِي ٱلۡأٓخِرَةِ مِنَ ٱلۡخَٰسِرِينَ ٨٥﴾ [آل عمران: 85]

{Ẹnikẹ́ni tí ó bá wá ẹ̀sìn kan ṣe yàtọ̀ sí 'Isla-m, A ò níí gbà á lọ́wọ́ rẹ̀. Ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn, ó sì máa wà nínú àwọn ẹni òfò. {85}}. [[85]. Suuratu Al Imran].

Islam ni ẹsin ti Ọlọhun fi ran gbogbo àwọn anọbi ati awọn ojiṣẹ, ọ̀kan ni ẹsin àwọn anọbi, oun naa ni Islam, gbogbo àwọn anọbi ni wọn mu imọ Ọlọhun lọkan wa, àwọn ofin wọn kan ni o yatọ síra.

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿وَمَآ أَرۡسَلۡنَا مِن قَبۡلِكَ مِن رَّسُولٍ إِلَّا نُوحِيٓ إِلَيۡهِ أَنَّهُۥ لَآ إِلَٰهَ إِلَّآ أَنَا۠ فَٱعۡبُدُونِ ٢٥﴾ [الأنبياء: 25]

{A kò rán òjíṣẹ́ kan níṣẹ́ ṣíwájú rẹ àfi kí A fi ìmísí ránṣẹ́ sí i pé: "Dájúdájú kò sí ọlọ́hun tí ìjọ́sìn tọ́ sí àfi Èmi (Alla-hu). Nítorí náà, ẹ jọ́sìn fún Mi." {25}} [ Suuratul Anbiyaa].

Islam nikan ni ẹsin ti o ṣẹku lori imọ Ọlọhun lọkan yii

Islam nikan ni ẹsin imọ Ọlọhun lọkan lórí ilẹ̀ lónìí

Ẹṣin kankan ko waa sẹku loni lori imu Ọlọhun Oba ni ọkanṣoṣo yato si ẹṣin isilaamu, nigbatosepe ipin kan ninu ẹbọ ti n'bẹ fun gbogbo awọn ti wọn n ṣe afiti arawọn si awọn ofin miiran, yala ipin kekere ni tabi pupọ.

24- Ǹjẹ́ èsì n bẹ ninu Islam fun àwọn ìbéèrè ti esi wọn n da làákàyè láàmú: Nibo ni a ti wá? Kilode ti a fi wa ninu ayé yii? Ibo ni a n lọ?

Esi: Isilaamu si ti dahun si gbogbo eyi ninu aaya kan soso ninu Alukuraani, Ọlọhun Oba wa sọpe:

﴿وَمَالِيَ لَآ أَعۡبُدُ ٱلَّذِي فَطَرَنِي وَإِلَيۡهِ تُرۡجَعُونَ ٢٢﴾ [يس: 22]

{Kí ni ó máa mú mi tí èmi kò fi níí jọ́sìn fún Ẹni tí Ó pilẹ̀ ẹ̀dá mi? Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni wọn yóò da yín padà sí. {22}} [Suuratu Yaasin].

Lati ibo ni motiwa? Olohun Oba ni oda mi (ẹniti oda mi)

Ibo ni mo n lọ? Maa lọ si ọdọ Ọlọhun lati lọ ṣe ìṣirò iṣẹ mi “WA ILAEHI TUR’JAHUUN”

Kilode ti o fi wa si ile-aye yii? Fun jijọsin fun Ọlọhun ati ki wọn le baa dan mi wo.

Kilode ti maa fi maa jọsin fun Ọlọhun? Ninu adamọ naa ni ki n maa jọsin fun Ọlọhun ti O da mi, eleyii ni adamọ ti o so ẹru ati olowo rẹ pọ: oun naa ni pe ki ẹru maa jọsin fun Olowo rẹ ati Adẹda rẹ:

﴿وَمَالِيَ لَآ أَعۡبُدُ ٱلَّذِي فَطَرَنِي وَإِلَيۡهِ تُرۡجَعُونَ ٢٢﴾ [يس: 22]

{Kí ni ó máa mú mi tí èmi kò fi níí jọ́sìn fún Ẹni tí Ó pilẹ̀ ẹ̀dá mi? Aaya kan ti o kó esi àwọn ìbéèrè mẹta ti o pàtàkì ju sínú, eyi ti o n ko ìdààmú ba èèyàn ﴿21﴾Kí ni ó máa mú mi tí èmi kò fi níí jọ́sìn fún Ẹni tí Ó pilẹ̀ ẹ̀dá mi? Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni wọn yóò da yín padà sí. {22}} [Suuratu Yaasin].

25- Bawo ni o ṣe mọ pe Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- jẹ́ ojiṣẹ lati ọ̀dọ̀ Ọlọhun?

Esi: Pupọ itọka iṣẹ ìyanu n jẹ ki a ni amọdaju ti o pe

Aristotle jẹ́ onímọ̀ ọgbọ́n orí nípasẹ̀ àkópọ̀ àwọn iṣẹ́ rẹ̀, kìí ṣe nípasẹ̀ gbólóhùn kan tí ó sọ tàbí ìwádìí ìmọ̀ ọgbọ́n orí tí ó ṣe.

Hippocrates jẹ dókítà pẹ̀lú apapọ iṣẹ àkànṣe ti iṣẹ iṣegun rẹ, kii ṣe pẹ̀lú iṣẹ abẹ ti o ṣe

Bẹẹ naa ni pupọ itọka iṣẹ ìyanu ti a gba wa lati ọdọ Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- n jẹ ki o da wa lójú pe anọbi ni

Ti o ba wo itan ìgbésí ayé rẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- waa ri i pe olódodo ni, o si gbajumọ pẹ̀lú ododo pẹ̀lú ẹri àwọn ọta rẹ ti o buru jù, wọn o si fi ẹsun irọ kan an ri Lẹ́yìn naa, o tun maa n sọ nipa àwọn nǹkan kọkọ ti o si maa ṣẹlẹ̀ gẹ́gẹ́ bi o ba ṣe wi, ṣáájú ìyẹn, adisọkan rẹ ti o pepe si lati ibẹrẹ ọjọ́ papọ mọ adisọkan gbogbo àwọn anọbi

Lẹ́yìn naa, kini a fẹ sọ nipa àmì ti o tobi ju ti o mu wa, oun naa ni Kuraani?

Kuraani ti Ọlọhun fi pe àwọn ti wọn dáńtọ́ níjà pe ki wọn mu irú rẹ wa tabi irú suura kan ninu rẹ, wọn ko si le mu u wa.

Ọlọhun ti O niyi ti O gbọnngbọn sọ pe:

﴿فَإِن لَّمۡ تَفۡعَلُواْ وَلَن تَفۡعَلُواْ فَٱتَّقُواْ ٱلنَّارَ ٱلَّتِي وَقُودُهَا ٱلنَّاسُ وَٱلۡحِجَارَةُۖ أُعِدَّتۡ لِلۡكَٰفِرِينَ ٢٤﴾ [البقرة: 24]

{Tí ẹ ò bá sì ṣe bẹ́ẹ̀, ẹ ò wulẹ̀ lè ṣe bẹ́ẹ̀ {24}] [Suuratul Baqarah].

Wọn ko ṣe e, wọn ko si ni ìkápá rẹ

Kuraani ṣi n pe àwọn ti wọn dáńtọ́ ninu awọn ẹlẹbọ nija, wọn ko si lè mú irú rẹ wa

Dr. Abdullah Daraaz- ki Ọlọhun kẹ ẹ- sọ pé: “Ṣe ojiṣẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ko paya pẹ̀lú ipenija yii ki o ma lọ rú ìgbónára wọn titi litireṣọ sókè?

Ti wọn yoo wa tara gìrì lati ba a fi iga gbága ti gbogbo wọn si n ṣọ́ra, kini o maa ṣe ti àwọn to dáńtọ́ ninu wọn ba fi ẹnu kò lati gbe ọrọ kan jáde ti o maa ba a fi iga gbága, kódà ki o jẹ ni àwọn àgbègbè kan

Ti ẹmi rẹ bá gbà fun un lati gbe ìdájọ́ yii jáde fun àwọn ti wọn jọ lo ìgbà, bawo ni o ṣe maa gbe e jade fun àwọn ìran to n bọ̀

Ìdáwọ́lé eléwu yii, ẹni kan ti o mọ iwọn ara rẹ̀ ko nii tẹ́rí sí i ayafi ki ọwọ́ rẹ ti kún fún didari kádàrá ati awọn nǹkan ti o n ṣẹlẹ̀ ni Sánmà Bayii ni o ṣe ju u sí ayé, kádàrá ti o ti parí ni, lati ìgbà dégbà ni gbogbo ẹni ti o fẹ mu irú rẹ wa ti n kùnà [18]

Àwọn Kèfèrí yii ti ri i pe ki awọn ko ọmọ ogun jọ lati gbogun ti ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- rọrùn ju ki wọn mu irú Kuraani wa.:

﴿وَقَالَ ٱلَّذِينَ كَفَرُواْ لَا تَسۡمَعُواْ لِهَٰذَا ٱلۡقُرۡءَانِ وَٱلۡغَوۡاْ فِيهِ لَعَلَّكُمۡ تَغۡلِبُونَ٢٦﴾ [فصلت: 26]

{Àwọn t’ó ṣàì gbàgbọ́ wí pé : "Ẹ má ṣe tẹ́tí sí al-Kur’a-n yìí. Kí ẹ sì sọ ìsọkúsọ nípa rẹ̀ kí ẹ lè borí." {26} [Suuratu Fussilat].

Gbogbo àwọn Lárúbáwá pata, ati awọn ìjọ ti wọn pe nija, wọn kò mú nǹkan ti àwọn alaigbagbọ ninu Ọlọhun le fàyà balẹ̀ sí wá.

Al-Aluusiy- ki Ọlọhun kẹ ẹ- sọ pe : “Ọkankan nínú wọn kò wí nǹkan kan titi di òní.

[18] Ìró Ńlá, Dr Abdullaah Daraaz, ki Ọlọhun kẹ ẹ, ojú-ìwé 44-45

Jubair ọmọ Mut'him sọ ki o to gba Islam pé : Mo gbọ ti Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- n ka Suuratu Tuur ni irun Magrib, nígbà tí ó dé ibi aaya yìí :

﴿أَمۡ خُلِقُواْ مِنۡ غَيۡرِ شَيۡءٍ أَمۡ هُمُ ٱلۡخَٰلِقُونَ ۝٣٥ أَمۡ خَلَقُواْ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضَۚ بَل لَّا يُوقِنُونَ ۝٣٦ أَمۡ عِندَهُمۡ خَزَآئِنُ رَبِّكَ أَمۡ هُمُ ٱلۡمُصَيۡطِرُونَ ۝٣٧﴾ [الطور: 35_37]

{Tàbí wọ́n ṣẹ̀dá wọn láì sí Aṣẹ̀dá ? Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá ara wọn ni ? {35} Tàbí àwọn ni wọ́n ṣẹ̀dá àwọn sánmọ̀ àti ilẹ̀ ? Rárá o, wọn kò màmọ̀ dájú ni. {36} Tàbí lọ́dọ̀ wọn ni àwọn àpótí ọrọ̀ Olúwa rẹ wà ? Tàbí àwọn ni olùborí ? {37}] [[37] Sūratu Tūr].

[19]O sọ pe : Ọkàn mi fẹẹ fò lọ

Àwọn àṣírí eemọ n bẹ ninu Kuraani ti o maa dé inú ẹ̀mí ọmọniyan

Ronú nípa bí àwọn obìnrin ẹlẹbọ ṣe kóra jọ ní àyíká ilé Abu Bakr nígbà tí ó ń ka Kuraani látàrí apọju fífà ọkàn wọn si i, ati lilapa rẹ lára wọn, titi ti ìyẹn fi kó àwọn ọkùnrin Kùráìṣì sínú ìfòyà. [20]

Ìdí nìyí tí àwọn aṣojú àwọn Lárúbáwá fi gbà lati jẹ ki gbólóhùn wọn ṣe ọkàn pé àwọn kò gbọ́dọ̀ gbọ́ Kuraani, àwọn ko si nii mu un deti igbọ fun awọn ẹbí wọn, èyí ni ọ̀nà kan ṣoṣo tí wọ́n fi lè wà nínú àìgbàgbọ́.

Ninu awọn eemọ Kuraani, ti eemọ rẹ ko si lee tan, naa ni nǹkan ti Dr. Abdullaah Draz- ki Ọlọhun kẹ ẹ- sọ nípa sisọkalẹ àwọn aaya Kuraani oríṣiríṣi àsìkò. Lẹ́yìn naa ni Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- maa sọ pe ki wọn fi àwọn aaya kan si awọn aaye kan pàtó laarin awọn suura, ki wọn si fi àwọn aaya miiran si aarin àwọn suura mìíràn. Lẹ́yìn naa ni suura kọọkan maa han ni igbẹyin gẹ́gẹ́ bíi ilé tí o dá dúró, o sọ- ki Ọlọhun

19 Sọhiihu ti Bukhaari: 4854

20 Sọhiihu ti Bukhaari, Haa: 3905

kẹ ẹ- pe: Ni asiko ti Kuraani n sọkalẹ, àwọn àkòrí ọ̀rọ̀ kan maa dá lékún láìfi ti àwọn àkòrí ọ̀rọ̀ mìíràn ṣe. O maa wa dá dúró díẹ̀ díẹ̀ lẹ́yìn ti àwọn aaya mìíràn ti o sọkalẹ lẹ́yìn rẹ ba ti kún un, ati ti àwọn kan ba ti kun un níbí ti àwọn mìíràn si ti wọ inú ara wọn ni aaye mìíràn, ni ìbámu sí àṣẹ ojiṣẹ- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- eyi ti oun naa n gbà lati ọdọ ẹ̀mí mímọ́.

Ti a ba woye si àwọn ìtàn ti ko ni ààlà- àwọn ìtàn sisọkalẹ àwọn aaya Kuraani Alapọn-ọnle- a maa ṣe àkíyèsí pé imisi yii sábà máa n ní ìbátan pẹ̀lú àwọn ipò àti ìṣẹ̀lẹ̀ kan pàtó. Ìyẹn maa pe wa lọ síbi bíbéèrè nípa àsìkò ti wọn to suura kọ̀ọ̀kan ti o fi dá wà.

O da bii pe wọn pin Kuraani kélekèle ti wọn si fi nọ́mbà si i lati ilé àtijọ́ kan ti wọn fẹ tún kọ́ si aaye mìíràn gẹ́gẹ́ bí ó ṣe wà tẹ́lẹ̀, bibẹẹkọ bawo ni yóò ṣe rọrùn lati ṣe alaye tito lẹsẹẹsẹ ni kíá mọ́sá ti o tún bá ìlànà mu ni akoko kan naa ti a ba n sọ nipa ọpọlọpọ awọn surah ?

ṣùgbọ́n ifọwọsọya ti ìtàn wo ni ọmọniyan le ní nígbà tí o ba n ṣe agbekalẹ irú ìlànà yii fun àwọn iṣẹlẹ ọjọ́ iwájú, ati awọn nǹkan ti o nílò lati ṣe òfin, ati awọn ọna àbáyọ fun un, ka mai tii sọ nipa èdè tí o jẹ dandan lati ṣe agbekalẹ àwọn ọ̀nà àbáyọ yii, ati bi ìlànà rẹ ṣe ba àwọn suura yii mu dípò ìyẹn?

Ṣé a o ri i pe pípé ìlànà yii, ati ifẹsẹrinlẹ rẹ bi a ṣe fẹ́, o nílò ki Aṣẹ̀dá ńlá kan dá sí i, ti o ni ikapa lati fi idi ètò ti a n fẹ́ múlẹ̀ ? [21]

Al-Qur'aani jẹ iṣẹ iyanu ti o da dúró ti o si n da lori ododo ti jijẹ Anabi rẹ (ki ike ati ọla Ọlọhun maa ba a)

Awọn iṣẹ ìyanu rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ti o ṣẹlẹ lati ọwọ rẹ pọ, ti o ju ẹgbẹẹgbẹ̀rún lọ, ati pe imọ nípa wọn sunmọ, awọn ti wọn si gba ẹgbawa nipa wọn jẹ olotitọ eeyan ati eeyan dáadáa julọ ninu ẹda.

[21] Tira "MAD'KHALUN ILAL QUR'ANIL KAREEM", ti Dr. Abdullah Draz. "

Ati pe awon olugba nnkan wa yii ti wọn gba awọn iṣẹ iyanu wọnyi wa fun wa, wọn ko le fi ọwọ si irọ pipa nipa ohun ti o wẹ́, bawo ni wọn ṣe le parọ mọ ọn ti wọn si mọ pe ẹnikẹni ti o ba mọ̀ọ́mọ̀ parọ mọ ọn, ki o wa aye ijokoo si inu ina gẹgẹ bi oun (Ki ike ati ola Olohun maa ba a) ṣe kilọ.

Diẹ ninu awọn iṣẹ iyanu rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) ni awọn ẹgbẹẹgbẹrun awọn saabe rẹ fi ojú rí, tí ọ̀pọ̀ nínú wọn si gba àwọn mìíràn wa, nitori naa bawo ni wọn ṣe le gba lati parọ ninu gbogbo eyi?

Àpẹrẹ àwọn iṣẹ́ ìyanu rẹ ti o ṣeju ọ̀pọ̀ nínú àwọn èèyàn ni hadiisi ẹ̀ránǹjẹ kùkùté igi, hadiisi ti o gbajumọ ni ti ọgọọrọ èèyàn si gba a wa, nibi ti Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ti maa n ṣe khutuba lori igi kùkùté kan nígbà tí wọ́n ba a ṣe minbari ti o wa gun orí rẹ, ti o wa bẹ̀rẹ̀ khutuba, ni kùkùté igi naa ba bẹ̀rẹ̀ si nii jẹ̀rán, o si n gbin bii ọmọdé titi ti Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- fi dì mọ́ ọn, ni o ba dakẹ.

Hadiisi yii, awọn saabe ti wọn gba a wa ni : Anas bin Malik, Jaber bin Abdullah, Abdullah bin Abbas, Abdullah bin Omar, Ubayy bin Kaab, Abi Saeed, Sahel bin Saad, Aisha bint Abi Bakr, ati Umm Salamah.

Njẹ iru awọn iye onka nọmba yii ninu awọn saabe le ko ara wọn jọ lati pa irọ lori iru ẹgbawa yii ?

Koda, awọn iṣẹ iyanu rẹ ni awọn ẹgbẹẹgbẹrun awọn saabe rí, gẹgẹ bii sisun omi jade lati aarin awọn ọmọnika ọwọ rẹ abiyi titi o fi ṣe aluwala nínú rẹ ti ẹgbẹrun le ni ọgọ́rùn-ún maarun ninu awọn saabe si mu ninu ẹ, ati pe hadisi yii jẹ ohun ti ọpọ èèyàn gba wa, ti Al-Bukhari ati Muslim gba a wa. “

Pipọsi ounjẹ ti o kere lati le fi fun awọn ọmọ ogun ti o pọ jẹ, ọpọ èèyàn ni wọn gba hadiisi yii wa lati ọdọ àwọn saabe. Bukhari nìkan sọ dárúkọ

iṣẹ ìyanu sisọ oúnjẹ di pupọ lati ọwọ Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni ọna maarun ninu sọhiihu rẹ. [22]

Tí ẹ̀rí òtítọ́ bá fẹsẹ̀ múlẹ̀, tí àwọn iṣẹ́ ìyanu sì pọ̀ lori jijẹ Anabi rẹ̀(kí ikẹ ati igẹ Ọlọhun máa bá a) báwo ni ẹni t'ó ni laakaye ṣe lè pe gbogbo eléyìí ni irọ?

Eyi ni awọn àpẹrẹ kekere mìírán ninu awọn iṣẹ iyanu rẹ (ki ikẹ ati igẹ Ọlọhun maa ba a).

Ni alẹ́ ọjọ kan, Anabi (ki ikẹ ati ọla maa ba a) sọ pe afẹfẹ nla kan yoo fẹ, o si kọ fun awon eniyan lati dide, bẹẹ ni okunrin kan dide, atẹgun si gbe e, o si ju u si aaye ti o jina si aaye rẹ tẹlẹ. [23]“

Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ fun àwọn èèyàn nipa iku An-Najaashiy ni ọjọ ti o ku, O si kirun si i lara pẹ̀lú kábàrá fun un lẹẹmẹrin. [24]. “

Anọbi- ki ike Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ fun àwọn èèyàn nipa pe Umar, Uthman, Ali, Ati Tolha ati Al-Zubayr, ki Olohun yọnu si gbogbo wọn lapapọ, pe wọn maa kú ikú ṣẹ̀ídí, wọn ko si nii ku lori ibusun wọn gẹgẹbi awọn eeyan ṣe maa n ku. "

Ojisẹ Ọlọhun- ki ike ati ola Olohun maa ba a- ti gun ori oke lọ ni ọjọ kan pẹlu Abu Bakr ati Umar ati Uthman ati Ali ati Tolha ati Al-Zubayr, ni apata naa bá mì, Ojise Olohun- ki ike Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- si sọ fun oke naa pe : Fi ara balẹ, Ko si nkankan lori ẹ afi Anọbi ati olódodo, ati ẹni ti o maa kú s'ójú ogun ẹ̀sìn.” .[25] “

---

[22] Al-Bukhari (1217), Al-Bukhari (2618), Al-Bukhari (3578), Al-Bukhari (4101), Al-Bukhari (6452). Gbogbo eyi ni orisirisi iṣẹlẹ ọtọọtọ, èyí si wa ninu Al-Bukhari nikan

[23] "[23] Sohiihu Muslim,Ha: 3319 "

[24] Sohiihu Al-Bukhari, Ha : 1333. “

[25] Sohiihu Muslim, Haa: 2417. “

O dajọ fun ara rẹ pẹlu ijẹ Anọbi, o dajọ fun Abu Bakr pẹlu ijẹ olododo, o si dajọ fun awọn yoku pẹlu pe won yoo pada jẹ ẹniti o maa ku si oju ogun, ati pe nkan ti Anọbi- ki ike ati ola Olohun maa ba a- sọ naa si ṣẹlẹ. “

Awọn Hadiisi ọgọrun-un le ni aadọta n bẹ ti Anọbi- ki ike ati ola Olohun maa ba a- ti pe Oluwa rẹ ti O si da a lóhùn lẹsẹkẹsẹ, ti awọn eniyan si wa nibẹ !”[26] .

“Ati nibi ti awọn ara Mekka ti béèrè lọwọ Ojisẹ Ọlọhun- ki ike Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- pe ki o fi ami kan han wọn, o si fi oṣupa ti o pin si abala meji han wọn, titi ti won fi ri oke Hira laarin mejeeji, Hadiisi yii jẹ eyi ti ọpọ eeyan gba wa, o n túmọ̀ si pe ipo ti o gaju lọ ninu awọn ipo ini alaafia ni o wa "

“Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- maa n ka Suratul Qamar eyi ti o ṣe pe iṣe iyanu pipin osupa n bẹ nibẹ nibi awọn ààyè akojọpọ ńlá gẹgẹbi awọn irun jimọh ati awọn irun ọdun ki awon eniyan le gbọ awon iṣe iyanu rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ti o wa ninu rẹ. O si maa n fi i ṣe ẹri lori ododo ijẹ Anọbi rẹ. "

"Lẹyin naa, Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- fun àwọn èèyàn ni iro pe Adam ni igbẹyin awon ẹ̀dá ninu awọn nkan ti a daa ti o n ṣẹmi, ati pe O da Adam leyin asiko alasari ni ọjọ Jimọh ; ni igbẹyin iṣẹda.”[27] “

“Ati pe òtítọ́ ìmọ̀ sáyẹ́ǹsì yii ti di eyi ti idi rẹ mulẹ, nitori naa bawo ni Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- ṣe mọ pe dajudaju Adam- ki ọla Ọlọhun maa ba a- ni igbẹyin ninu awọn ẹda ti a da ti o han lori ilẹ aye lẹyin ihan awọn irúgbìn ati ẹranko ? “

“Ki o woye si ọrọ Ọlọhun Ọba ti O ga ti O gbọnngbọn :

---

[26] “[26] Saheed Bn Abd al-Qadir Bashanfar ko awọn Hadiisi yii jọ, ninu iwe rẹ Dala’ilun Nubuwwah, ti iwe naa si jẹ ọkan lara awọn atẹjade Ibn Hazm. “

[27] Sohiihul Jami’, 8188.”

﴿وَجَعَلۡنَا ٱلَّيۡلَ وَٱلنَّهَارَ ءَايَتَيۡنِۖ فَمَحَوۡنَآ ءَايَةَ ٱلَّيۡلِ وَجَعَلۡنَآ ءَايَةَ ٱلنَّهَارِ مُبۡصِرَةٗ لِّتَبۡتَغُواْ فَضۡلٗا مِّن رَّبِّكُمۡ وَلِتَعۡلَمُواْ عَدَدَ ٱلسِّنِينَ وَٱلۡحِسَابَۚ وَكُلَّ شَيۡءٖ فَصَّلۡنَٰهُ تَفۡصِيلٗا ١٢﴾ [الإسراء: 12]

{{A ṣe alẹ́ àti ọ̀sán ní àmì méjì ; A pa àmì alẹ́ rẹ́, A sì ṣe àmì ọ̀sán ní ìríran 12} ".}. [Suuratul Israa].

A pa ami Alẹ rẹ : O tumọ si pe dajudaju oṣupa ni ami alẹ, o jẹ nkan ti o tan imolẹ lẹyin naa wọn pa imolẹ rẹ rẹ"

Ni paapaa eyi ni nkan ti awọn saabe fi túmọ̀ ayah Alapọnle naa, Imam Ibn Kathir gba ọrọ wa ninu iwe alaye itumọ Kuraani rẹ pe : Dajudaju Abdullah Bn Abbas- ki Ọlọhun yọnu si awọn mejeeji- sọ pe : “Oṣupa maa n tan imolẹ gẹgẹbi oorun ṣe maa n tan imolẹ, oun naa ni ami oru, wọn si pa a rẹ "

“Ohun iyalẹnu ni pe eyi ni ohun ti imọ pin si ni ode oni, ati pe NASA ti gbé jáde lori ìkànnì wẹẹbu rẹ ti gbogbogboo tẹ́wọ́gbà pé : Akoko àkọ́kọ́ ninu igbesi aye oṣupa, o jẹ nǹkan ti o n tan ìmọ́lẹ̀ yòò [28]"

Ṣiṣẹlẹ àwọn àmì ati ìsọfúnni nípa àwọn ohun ikọkọ, ati kúlẹ̀kúlẹ̀ àṣírí ilẹ̀ ati sánmà ti ko ni ààlà, ati sisọkalẹ Kuraani lati ọwọ Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- gbogbo ẹ fẹsẹ rinlẹ nípasẹ̀ ọgọọrọ èèyàn, o si mu ohun ti àwọn Anọbi ti wọn ṣíwájú rẹ wa lori rẹ wa, Ọlọhun si kun un lọ́wọ́, òfin naa si pé ṣíwájú ki o to kú.

Fifi gbogbo ẹnu sọ pe Anọbi ni, oun naa ni imọna laakaye ! "

Awọn ami ikọkọ rẹ- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- le ni ẹgbẹrun kan.

---

28 http://www.nasa.gov/mission_pages/LRO/news/vid-tour.html

https://www.youtube.com/watch?v=UIKmSQqp8wY “

Awọn ti wọn gba àwọn iṣẹ́ ìyanu naa wa naa ni àwọn saabe rẹ, àwọn ni olódodo julọ ninu awọn ẹ̀dá ti wọn si tun dára julọ.

Ohun eemọ ni pe awọn agbaagba saabe gba Isilaamu ṣiwaju ki wọn o too ri awọn iṣẹ́ ìyanu. Wọn gba Isilaamu nitori pe wọn mọ pe Anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) jẹ olododo, ko si lee parọ láéláé.

Èrò-orí awọn agbaagba saabe yii jẹ eyi ti o ba laakaye mu ti ọgbọ́n si wa nibẹ. Sisọ ootọ Anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) yii jẹ ẹ̀rí ti o to ti o si da duro lati fi ṣe ifinrinlẹ jijẹ Anabi... Eleyii si wa bẹẹ nitori pe : Ẹni ti yoo ba pe apemọra jijẹ Anabi gbọdọ jẹ ọkan ninu awọn mejeeji yii, ninu ki o jẹ : olootọ eeyan julọ nitori pe Anabi ni... Anabi ni ẹni tí o jẹ olootọ eeyan julọ.

Tabi ki o jẹ : opurọ eeyan julọ ; nitori pe o n pa irọ nibi àlámọ̀rí ti o pàtàkì julọ.

Olootọ eeyan julọ ko si le dàpọ̀ mọ opurọ eeyan julọ ayafi lójú awọn alaimọkan eeyan julọ. [29]

Ki ni o fi n rọrùn to ki onilaakaye ni ìkápá láti ṣe ìyàtọ̀ laarin olootọ eeyan julọ ati opurọ eeyan julọ.

Awọn ẹlẹbọ ti jẹwọ lati ọjọ akọkọ ti wọn ti gbe Anabi (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a) dide wipe ko parọ ri, wọn sọ fún un pé : "A o mọ̀ ọ́ mọ irọ́".[30]

Nigba ti Hercules bi Abu Suf'yaan léèrè ṣiwaju ki o to gba Isilaamu pe : "Njẹ ẹ maa n kẹfin rẹ pẹlu irọ pipa ṣiwaju ki o to maa sọ ohun ti n sọ ?"

---

[29] Ifẹṣẹrinlẹ jijẹ Anabi pẹ̀lú làákàyè ati ẹgbawa, Ibn Taymiyyah, Daaru ibnul Jaozee, ojúewé 573, pẹlu itumọ rẹ gan-an gan-an nínú ìwé kan náà ni oju ewe 318.

[30] Saheeh Bukhari, Haa:4971

Abu Suf'yan dahun pe :" Rara "

Hercules wa sọ pe : Ṣé ẹni ti kii parọ fun awọn eeyan ni yoo wa maa parọ mọ Ọlọhun.

Hercules wa pari ọrọ rẹ pẹlu sisọ ọrọ rẹ ti o gbajumọ pe : ka ni pe mo ba wa lọdọ rẹ ni, mi o ba fọ gigisẹ rẹ mejeeji[31].

Awọn keferi ti kagara láti ṣe afihan iró̩ kan ti o pa rí ni gbogbo isẹmi rẹ (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a), fun idi eleyii ni Alukurani fi tako ṣíṣe keferi wọn pẹlu pe wọn ni imọ nipa rẹ siwaju igbedide rẹ, Oluwa wa (ti O mọ) sọ pe :

﴿أَمۡ لَمۡ يَعۡرِفُواْ رَسُولَهُمۡ فَهُمۡ لَهُۥ مُنكِرُونَ ٦٩﴾ [المؤمنون: 69]

Tàbí wọn kò mọ Òjíṣẹ́ wọn mọ́ ni wọ́n fi di alátakò rẹ̀ ? {69}} Suuratul Mu'minuun.

Iṣesi Anabi ati itan rẹ si jẹ itọka kan ti o da duro lori wipe Anabi ni.

Ki Ọlọhun ṣe ikẹ ati igẹ Rẹ fun un.

Ti àwọn okùnfà òdodo ba kárí, ti wọn si ran ara wọn lọ́wọ́ lórí ijẹ Anọbi rẹ, báwo ni onilaakaye ṣe maa pe gbogbo èyí ní iró̩ ?

Bawo ni maa ṣe mọ pe mo nílò lati ni igbagbọ nínú Ọlọhun ?

Esi : Wo ara rẹ naa, oo pada maa mọ pe wọn n dan ẹ wo ni, njẹ ko si ninu rẹ ohun imọlara ti n sọ pe ṣe daadaa, ma ṣe ṣe aburu ?

Ti awọn dukia kan ba wa ni arọwọto rẹ ti ẹniti o ni i ko si lo o, imọlara kan o maa wa ba ọ pe : mu awọn dukia yii ki o si lo ninu rẹ, imọlara ti

[31] Saheeh Bukhari, Haa: 7

idakeji o si maa sọ fun ọ pe : ma ṣe nnkan yii, eewọ ni in, ọran si tun ni in.

Wọn o maa dan ẹ wo nibi gbogbo ipò isẹmi aye rẹ.

Imọlara yii - imọlara pe : ṣe e, ma ṣe e- wọn yoo ri i ninu rẹ ; nitori pe wọn n dan ẹ wo ni lododo, o o kii ṣe ẹni tí wọ́n pa tì, o o kii ṣe nnkan ti ko pàtàkì.

Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe :

﴿إِنَّا هَدَيۡنَٰهُ ٱلسَّبِيلَ إِمَّا شَاكِرٗا وَإِمَّا كَفُورًا ٣﴾ [الإنسان: 3]

{Dájúdájú A fi ọ̀nà mọ̀ ọ́n; Ó lè jẹ́ olùdúpẹ́, ó sì lè jẹ́ aláìmoore. {3}} [Suuratul In'saan].

O n bẹ nínú ọmọniyan pe "ṣe" ati "ma ṣe": Ninu ki o jẹ oludupẹ tabi ki o jẹ alaimoore ni gbogbo ipò ti o ba n wa ninu isẹmi rẹ

koda nibi igbesẹ kọọkan ninu awọn igbesẹ isẹmi ọmọniyan ni yoo ti rọrùn fun un ki o ṣe rere tabi ki o ṣe aburu, ǹjẹ́ maṣalaṣi ni o maa lọ ni abi o maa lọ ṣe iranu

Fun idi yẹn ni Ọlọhun ti O ni agbara ti O gbọnngbọn fi sọ pe:

﴿وَمَا خَلَقۡتُ ٱلۡجِنَّ وَٱلۡإِنسَ إِلَّا لِيَعۡبُدُونِ ٥٦﴾ [الذاريات: 56]

{Àti pé Èmi kò ṣẹ̀dá àlùjànnú àti ènìyàn bí kò ṣe pé kí wọ́n lè jọ́sìn fún Mi. {56}} [Suuratu Dhaariyaat : 56]

Ninu igbesẹ kọọkan waa ri ìran kan nínú ijẹ ẹrusin fun Ọlọhun tabi ìyapa àṣẹ rẹ

Ẹni ti wọn ba fi ṣe kongẹ lati ṣe nǹkan ti Ọlọhun pa a láṣẹ, onitọun ti là, ẹni ti o ba si yapa àṣẹ Ọlọhun, o ti ṣe àṣìṣe

Ìkápá láti ṣẹsa yii, ohun ti o maa ti ibẹ jáde ni ìṣirò ọmọniyan lori gbogbo nǹkan ti o ba ṣe

Nǹkan ti wọn tori rẹ da wa naa ni lati dan wa wo, eyi ni erongba ti Ọlọhun tori rẹ ran àwọn ojiṣẹ ti O si tun sọ àwọn tira kalẹ :

﴿وَلَقَدْ بَعَثْنَا فِي كُلِّ أُمَّةٍ رَّسُولًا أَنِ ٱعْبُدُوا۟ ٱللَّهَ وَٱجْتَنِبُوا۟ ٱلطَّٰغُوتَ ۖ فَمِنْهُم مَّنْ هَدَى ٱللَّهُ وَمِنْهُم مَّنْ حَقَّتْ عَلَيْهِ ٱلضَّلَٰلَةُ ۚ فَسِيرُوا۟ فِي ٱلْأَرْضِ فَٱنظُرُوا۟ كَيْفَ كَانَ عَٰقِبَةُ ٱلْمُكَذِّبِينَ ﴿٣٦﴾﴾ [النحل: 36]

{Dájúdájú A ti gbé Òjíṣẹ́ dìde nínú ìjọ kọ̀ọ̀kan (láti jíṣẹ́) pé : "Ẹ jọ́sìn fún Alla-hu. Kí ẹ sì jìnnà sí àwọn òrìṣà." {36} ". [Suuratun' Nah'l].

Lẹyin ti idanwo naa ba pari pẹ̀lú ikú, a maa ṣẹri pada lọ si ọdọ Ọlọhun,

﴿وَمَا لِيَ لَآ أَعْبُدُ ٱلَّذِي فَطَرَنِي وَإِلَيْهِ تُرْجَعُونَ ﴿٢٢﴾﴾ [يس: 22]

{Ọ̀dọ̀ Rẹ̀ sì ni wọn yóò da yín padà sí}: 22 Suuratu Yaasiin.

﴿وَأَنَّ إِلَىٰ رَبِّكَ ٱلْمُنتَهَىٰ ﴿٤٢﴾﴾ [النجم: 42]

{Àti pé dájúdájú ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ ni òpin (ìrìn-àjò ẹ̀dá). {42}} [Suuratun' Najm].

﴿إِنَّ إِلَىٰ رَبِّكَ ٱلرُّجْعَىٰٓ ﴿٨﴾﴾ [العلق: 8]

{{Dájúdájú ọ̀dọ̀ Olúwa rẹ ni àbọ̀ ẹ̀dá}} {8}. [Suuratul Halaq]

A maa pada si ọdọ Ọlọhun lati lọ ṣe ìṣirò ohun ti a ṣe.

﴿ثُمَّ يُجۡزَىٰهُ ٱلۡجَزَآءَ ٱلۡأَوۡفَىٰ﴾ [النجم: 41]

{Àti pé dájúdájú iṣẹ́ rẹ̀, láìpẹ́ wọ́n máa fi hàn án. {41} Lẹ́yìn náà, wọ́n máa san án ní ẹ̀san rẹ̀, ní ẹ̀san t'ó kún julọ. {42}.} [Suuratun' Najm].

Wọ́n maa fi ohun ti o ṣe hàn án, o si maa ṣe ìṣirò rẹ

﴿فَمَن يَعۡمَلۡ مِثۡقَالَ ذَرَّةٍ خَيۡرٗا يَرَهُۥ ۝٧ وَمَن يَعۡمَلۡ مِثۡقَالَ ذَرَّةٖ شَرّٗا يَرَهُۥ ۝٨﴾ [الزلزلة: 7-8]

{Nítorí náà, ẹni tí ó bá ṣe iṣẹ́ rere ní òdíwọ̀n ọmọ iná-igún, ó máa rí i. {7} Ẹni tí ó bá sì ṣe iṣẹ́ aburú ní òdíwọ̀n ọmọ iná-igún, ó máa rí i. {8}.} [8] [Suuratu Zalzalah].

27- Nje nini igbagbọ ninu Ọlọhun ati ṣiṣe keferi si awọn Anabi to?

Idahun: rara.

Nini igbagbọ si bibẹ Ọlọhun pẹlu aini igbagbọ si awọn Anabi, ko lee to titi ti ọmọniyan o fi ju gbogbo ara rẹ silẹ fun Ọlọhun. Ki ni itumọ pe ki o ni igbagbọ si Ọlọhun ti o si jẹ pe Oun naa ni Aṣẹ̀dá, Olupese, Olùdarí, lẹyin igba naa ti o tun wa n ṣe keferi si imisi Rẹ, ti o si tun n tako awọn ojiṣẹ Rẹ.

Ṣiṣe keferi ti o tobi ju ni èyí.

Ko si ọran kan ti o tobi to ẹniti ti n da imisi Ọlọhun padà fún Un, Ọlọhun ti O ga sọ pe:

﴿إِنَّ ٱلَّذِينَ يَكۡفُرُونَ بِٱللَّهِ وَرُسُلِهِۦ وَيُرِيدُونَ أَن يُفَرِّقُواْ بَيۡنَ ٱللَّهِ وَرُسُلِهِۦ وَيَقُولُونَ نُؤۡمِنُ بِبَعۡضٖ وَنَكۡفُرُ بِبَعۡضٖ وَيُرِيدُونَ أَن يَتَّخِذُواْ بَيۡنَ ذَٰلِكَ سَبِيلًا ۝١٥٠ أُوْلَٰٓئِكَ هُمُ ٱلۡكَٰفِرُونَ حَقّٗاۚ وَأَعۡتَدۡنَا لِلۡكَٰفِرِينَ عَذَابٗا مُّهِينٗا ۝١٥١﴾ [النساء: 150-151]

{Dájúdájú àwọn t'ó ń ṣàì gbàgbọ́ nínú Alla-hu àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀, tí wọ́n fẹ́ ṣòpínyà láààrin Alla-hu àti àwọn Òjíṣẹ́ Rẹ̀, tí wọ́n sì ń wí pé: "A gbàgbọ́ nínú apá kan, a sì ṣàì gbàgbọ́ nínú apá kan," wọ́n sì fẹ́ mú ọ̀nà kan tọ̀ (lẹ́sìn) láààrin ìyẹn. {150} Ní òdodo, àwọn wọ̀nyẹn, àwọn ni aláìgbàgbọ́. A sì ti pèsè Ìyà tí í yẹpẹrẹ ẹ̀dá sílẹ̀ de àwọn aláìgbàgbọ́. {151}]. [Suuratun- Nisaa'].

Ẹniti o ba ni igbagbọ si Ọlọhun, ti o si kọ ti awọn Anabi, Kèfèrí ni in tí kò rújú.

Gbogbo ẹniti o kọ ti anabi kan ninu awọn Anọbi, keferi ni onitọun si Ọlọhun; nitori pe o kọ imisi Ọlọhun, fun idi eleyii, awọn ti wọn fun ni tira lati sanmọ jẹ keferi nitori ṣíṣe keferi wọn pẹlu jijẹ Anabi Muhammad ọmọ Abdullah (ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a):

﴿إِنَّ ٱلَّذِينَ كَفَرُواْ مِنۡ أَهۡلِ ٱلۡكِتَٰبِ وَٱلۡمُشۡرِكِينَ فِي نَارِ جَهَنَّمَ خَٰلِدِينَ فِيهَآۚ أُوْلَٰٓئِكَ هُمۡ شَرُّ ٱلۡبَرِيَّةِ ٦﴾ [البينة: 6]

{Dájúdájú àwọn t'ó ṣàì gbàgbọ́ (wọ̀nyí) nínú àwọn ahlul-kita-b àti àwọn ọ̀ṣẹbọ, wọn yóò wà nínú Iná. Olùṣegbére ni wọ́n nínú rẹ̀. Àwọn wọ̀nyẹn, àwọn ni ẹ̀dá t'ó burú jùlọ. {6}] [Suuratul Bayyinah].

Iya Ọlọhun pẹlu mimu wọn wọ ina jẹ ootọ:

﴿وَرَبَطۡنَا عَلَىٰ قُلُوبِهِمۡ إِذۡ قَامُواْ فَقَالُواْ رَبُّنَا رَبُّ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِ لَن نَّدۡعُوَاْ مِن دُونِهِۦٓ إِلَٰهٗاۖ لَّقَدۡ قُلۡنَآ إِذٗا شَطَطًا ١٤﴾ [الكهف: 14]

{Nítorí náà, ìlérí Mi sì di ẹ̀tọ́ (lórí wọn} (14)} {Suuratu Qọọf.}

Kii ṣe Isilaamu ati ọla ni ki ọmọniyan o gba pe Ọlọhun ni Aṣẹ̀dá, Olupese, Ọba tii sọ ẹ̀dá di alààyè, Ọba tii sọ ẹ̀dá di òkú, ki o wa tan sibẹ, ṣugbọn o tun gbọdọ ni igbagbọ si awọn ojiṣẹ Rẹ.

Fun idi eleyii, nini igbagbọ pẹlu bibẹ Ọlọhun ati kikọ awọn Anabi, ko to, ko si nii ṣe anfani fun ẹru lọdọ Ọlọhun ni ọjọ igbende, nítorí pe eeyan gbọdọ maa jọsin fun Ọlọhun, o si gbọdọ ni igbagbọ nínú gbogbo awọn ojiṣẹ Rẹ.

Ti o ba jẹ nini igbagbọ si bibẹ Ọlọhun ba to ni, Ọlọhun ko nii ran awọn ojiṣẹ Rẹ abi sọ tira Rẹ kalẹ, nitori pe gbogbo ẹda ni yoo mọ Ọlọhun latara abínibí.

Ọlọhun ti O da ọ, ti O si tọ ọ sọna, ti O si pese jijẹ mimu fun ọ, Oun nikan ni ijọsin rẹ tọ si gẹgẹ bi O ṣe gbe ofin rẹ kalẹ nípasẹ̀ awọn ojiṣẹ Rẹ ati awọn Anabi Rẹ.

28- Njẹ keferi yoo gba ẹsan awọn iṣẹ rere rẹ lọdọ Ọlọhun?

Esi: Iṣẹ rere jẹ abinibi ti Ọlọhun da mọ awọn eeyan, fun idi yii, o maa ri i pe o rọrun fun ẹnikẹni lati maa ṣe iṣẹ rere koda ki o jẹ keferi abi ẹlẹbọ, gbogbo eeyan ni yoo ma ṣe iṣẹ rere latari abinibi ti wọn da wọn le lori

Ṣugbọn majẹmu ti yoo jẹ ki iṣẹ rere o jẹ itẹwọgba naa ni: ki eeyan fi wa ojurere Ọlọhun, itumọ ni pe: ki eeyan ṣe e lati fi gba ẹsan rẹ lọdọ Ọlọhun.

Fun idi eleyii, ẹniti o ba jẹ keferi si Ọlọhun ti n jọsin fun ọlọhun miran pẹlu Ọlọhun, a o maa sọ fun un pe: maa lọ si ọdọ awọn ti o n jọsin fun pẹlu Ọlọhun nibi iṣẹ rere rẹ ki wọn o fun ẹ ni ẹsan lọdọ wọn, iwọ ko fi awọn iṣẹ rere rẹ wa oju rere Ọlọhun.

Fi ojú inú wo o pe ọmọniyan kan ti awọn araale rẹ re e ti wọn si náwó le e lórí titi ti o fi dagba di ọdọ ti o lagbara, ti o wa pada lọ si ọdọ ẹlomiran lati lọ sin wọn, njẹ o tun ni ẹtọ fun un lati pada si ọdọ awọn araale rẹ lati maa sọ fun wọn pe: ẹ fun mi ni owo ọya mi ti mo fi sin ẹlomiran yatọ si yin?

Ki ẹniti o n si wọn maa lọ si ọdọ awọn ẹniti o n sin, ki o si gba ẹsan rẹ lọdọ wọn.

Ti Allāhu sì ni àkàwé t'ó ga jùlọ

Ọlọhun ni O da ọ, ni O si pèsè ijẹ-imu fun ọ, ni O si ṣe gbogbo idẹra fun ọ, o waa gbe ìjọsìn fun Un ju silẹ, o si fẹ gba ẹsan iṣẹ rẹ lọdọ Rẹ àbí? Bawo ni eyi ṣe fẹ́ rọrùn?

Nítorí náà, Ọlọhun sọ pé:

﴿وَقَدِمۡنَآ إِلَىٰ مَا عَمِلُواْ مِنۡ عَمَلٖ فَجَعَلۡنَٰهُ هَبَآءٗ مَّنثُورًا ٢٣﴾ [الفرقان: 23]

{Àti pé A máa wá ṣíbi ohun tí wọ́n ṣe níṣẹ́, A sì máa sọ ọ́ di eruku àfẹ́dànù. {23} "}. Suuratul Fur'qan.

Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe:

﴿إِنَّ ٱلَّذِينَ يَرۡمُونَ ٱلۡمُحۡصَنَٰتِ ٱلۡغَٰفِلَٰتِ ٱلۡمُؤۡمِنَٰتِ لُعِنُواْ فِي ٱلدُّنۡيَا وَٱلۡأٓخِرَةِ وَلَهُمۡ عَذَابٌ عَظِيمٞ ٢٣﴾ [النور: 23]

{Àwọn t'ó ṣàì gbàgbọ́, àwọn iṣẹ́ wọn dà bí ahúnpeéná t'ó wà ní pápá, tí ẹni tí òǹgbẹ ń gbẹ sì lérò pé omi ni títí di ìgbà tí ó dé síbẹ̀, kò sì bá kiní kan níbẹ̀. {39}} [Suratu An-Nur].

Awọn ti wọn ṣe aigbagbọ, wọn ko ni ẹtọ si ẹsan lórí iṣẹ wọn koda ki o jẹ iṣẹ rere; tori pé Kèfèrí ni wọ́n, wọn ko gbero ẹsan ọdọ Olúwa wọn pẹ̀lú iṣẹ rere naa, wọn ko si fi wa iyọnu Aṣẹ̀dá wọn.

Ọrọ naa kii ṣe ṣíṣe iṣẹ rere lasan, gbogbo wa pata ni wọn da wa mọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ ninu iṣẹ rere, ohun ti o kàn wa ni pe tori ki ni o fi n ṣe iṣẹ́ rere yii, ta ni o n ṣe e fun? Ṣé o n ṣe e fun anfaani ara rẹ ni, abi fun ṣekarimi, abi fun nnkan ti o yatọ si Ọlọhun?

Gbogbo eyi pata ko si ni oju ọna ti Ọlọhun, eeyan o si lee rankan ẹsan iṣẹ rere ti eeyan maa n rankan lọ́dọ̀ Ọlọhun ninu ẹ.

29- Ti Isilaamu ba jẹ ẹsin òdodo, ki ni o de ti ìríjú fi wa?

Esi: Iruju jẹ ọ̀rọ̀ kan ti ko ye Mùsùlùmí ninu ẹsin rẹ, o si le ru u loju titi tí yoo fi ri èsì fun un.

O wu Ọlọhun bẹẹ ni ki awọn iruju maa bẹ ninu awọn ọrọ ẹka ninu ẹsin, ki ẹni ti o ba n fẹ irọ le jìnà si itẹle Olúwa rẹ.

Ọlọhun ti O niyi ti O gbọnngbọn sọ pe:

﴿هُوَ ٱلَّذِيٓ أَنزَلَ عَلَيۡكَ ٱلۡكِتَٰبَ مِنۡهُ ءَايَٰتٞ مُّحۡكَمَٰتٌ هُنَّ أُمُّ ٱلۡكِتَٰبِ وَأُخَرُ مُتَشَٰبِهَٰتٞۖ فَأَمَّا ٱلَّذِينَ فِي قُلُوبِهِمۡ زَيۡغٞ فَيَتَّبِعُونَ مَا تَشَٰبَهَ مِنۡهُ ٱبۡتِغَآءَ ٱلۡفِتۡنَةِ وَٱبۡتِغَآءَ تَأۡوِيلِهِۦۖ وَمَا يَعۡلَمُ تَأۡوِيلَهُۥٓ إِلَّا ٱللَّهُۗ وَٱلرَّٰسِخُونَ فِي ٱلۡعِلۡمِ يَقُولُونَ ءَامَنَّا بِهِۦ كُلّٞ مِّنۡ عِندِ رَبِّنَاۗ وَمَا يَذَّكَّرُ إِلَّآ أُوْلُواْ ٱلۡأَلۡبَٰبِ٧﴾ [آل عمران: 7]

{" Òun ni Ẹni tí Ó sọ Tírà kalẹ̀ fún ọ; àwọn a-yah aláìnípọ́n-na wà nínú rẹ̀ - àwọn sì ni ìpìlẹ̀ Tírà -, onípọ́n-na sì ni ìyókù. Ní ti àwọn tí ìgbúnrí kúrò níbi òdodo wà nínú ọkàn wọn, wọn yóò máa tẹ̀lé èyí t'ó ní pọ́n-na nínú rẹ̀ láti fi wá wàhálà àti láti fi wá ìtúmọ̀ (òdì) fún un. Kò sì sí ẹni t'ó nímọ̀ ìtúmọ̀ rẹ̀ àfi Allahu. Àwọn àgbà nínú ìmọ̀ ẹ̀sìn, wọ́n ń sọ pé: "A gbà á gbọ́. Láti ọ̀dọ̀ Olúwa wa ni gbogbo rẹ̀ (ti sọ̀kalẹ̀)." Kò sí ẹni t'ó ń lo ìrántí àyàfi àwọn onílàákàyè. {7}.} [Suuratu Aal Imraan].

"Ní ti àwọn tí ìgbúnrí kúrò níbi òdodo wà nínú ọkàn wọn, wọn yóò máa tẹ̀lé èyí t'ó ní pọ́n-na nínú rẹ̀: Ẹni tí igbunri kuro nibi ododo wa ninu ọkan rẹ, yoo maa tẹle àwọn iruju yii lati fi wa wàhálà, ati lati fi wa jíjìnnà sí Ọlọhun.

O wu Ọlọhun nínú ọgbọ́n Rẹ ki ìgbàgbọ́ ati aigbagbọ maa bẹ.

﴿هُوَ ٱلَّذِي خَلَقَكُمۡ فَمِنكُمۡ كَافِرٞ وَمِنكُم مُّؤۡمِنٞۚ وَٱللَّهُ بِمَا تَعۡمَلُونَ بَصِيرٌ ٢﴾ [التغابن: 2]

[Aláìgbàgbọ́ wà nínú yín. Onígbàgbọ́ òdodo sì wà nínú yín. {2}} [ Suuratu Tagaabun.}

Ẹni ti o maa dìrọ̀ mọ́ àwọn iruju yii naa ni ẹni tí ó ba fẹ ṣe aigbagbọ ti o si fẹ ko airoju pẹ̀lú rẹ kuro nibi ẹsin rẹ ati irun rẹ ati ìgbàgbọ́ rẹ.

Àmọ́ mumini, oun maa tẹle àwọn ẹri ti ko ruju ti o fi ẹsẹ rinlẹ, òun naa ni ìyá tira (lórí ìní àlàáfíà ẹsin ati ijẹ ojiṣẹ), ti o ba ri nǹkan kan ti ko ba gbọye, o maa béèrè nípa rẹ, ṣùgbọ́n ko nii ko airoju pẹlu nǹkan ti ko gbọye kúrò nibi ẹsin rẹ tabi irun rẹ.

Ẹnikan ko nii ko airoju pẹ̀lú nǹkan ti ko gbọye kúrò nibi ẹsin rẹ ayafi ẹni ti àrùn n bẹ nínú ọkàn rẹ. :

﴿وَمَا جَعَلۡنَآ أَصۡحَٰبَ ٱلنَّارِ إِلَّا مَلَٰٓئِكَةٗۖ وَمَا جَعَلۡنَا عِدَّتَهُمۡ إِلَّا فِتۡنَةٗ لِّلَّذِينَ كَفَرُواْ لِيَسۡتَيۡقِنَ ٱلَّذِينَ أُوتُواْ ٱلۡكِتَٰبَ وَيَزۡدَادَ ٱلَّذِينَ ءَامَنُوٓاْ إِيمَٰنٗا وَلَا يَرۡتَابَ ٱلَّذِينَ أُوتُواْ ٱلۡكِتَٰبَ وَٱلۡمُؤۡمِنُونَ وَلِيَقُولَ ٱلَّذِينَ فِي قُلُوبِهِم مَّرَضٞ وَٱلۡكَٰفِرُونَ مَاذَآ أَرَادَ ٱللَّهُ بِهَٰذَا مَثَلٗاۚ كَذَٰلِكَ يُضِلُّ ٱللَّهُ مَن يَشَآءُ وَيَهۡدِي مَن يَشَآءُۚ وَمَا يَعۡلَمُ جُنُودَ رَبِّكَ إِلَّا هُوَۚ وَمَا هِيَ إِلَّا ذِكۡرَىٰ لِلۡبَشَرِ ٣١﴾ [المدثر: 31]

{" àti nítorí kí àwọn tí àrùn wà nínú ọkàn wọn àti àwọn aláìgbàgbọ́ lè wí pé : "Kí ni Alla-hu gbà lérò pẹ̀lú àpèjúwe yìí ?" Báyẹn ni Alla-hu ṣe ń ṣi ẹni tí Ó bá fẹ́ lọ́nà, Ó sì ń tọ́ ẹni tí Ó bá fẹ́ sọ́nà. {31} ".}. [Suuratul Muddathir}.

Lara ọgbọn to n bẹ ninu bibẹ ìríjú naa ni pe àwọn nǹkan ti o ruju yii ni àwọn onímímọ̀ fi maa n da yàtọ̀ ninu ẹsin Ọlọhun, waa ri onímímọ̀ ti o maa mọ idahun àwọn iruju naa, o si maa fi yatọ si eeyan ti ko ni ìmọ̀ ti ẹsin ko ye e lọ títí, ti ko si kọ́ ọ, Ọlọhun maa wa gbe àwọn onímímọ̀ ga ní ipò

Nǹkan ti o hàn ni òdodo, ṣùgbọ́n iruju naa gbọdọ̀ wa ki afọmọ le tara rẹ ṣelẹ̀

Ìlànà Ọlọhun ninu ẹ̀dá Rẹ ni líla iṣẹ́ bọ wọn lọrun lati ṣe, ìlànà Rẹ ninu iṣẹ ti O ba la bọ ni lọrun naa ni ki awọn ọgbọ́n kan o sapamọ, ẹni tí yoo jèrè ni ẹni ti o ba fi nǹkan ti ó mọ̀ ṣe ẹri fun nǹkan ti o pamọ, olófo ni ẹni tí o ba fi nǹkan ti kò mọ̀ ṣe gàgá ti ko nii jẹ ki o le fi nǹkan ti o ba mọ ṣe ẹri.

30- Torí ki ni Ọlọhun fi da aburu ? Tabi ki a sọ pe : Báwo ni Musulumi ṣe maa fèsì sí ìṣòro aburu[32]

Èsì : Fitina aburu ni o fẹẹ jẹ okùnfà aigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun ti o tobi jù ninu ìtàn :

﴿وَمِنَ ٱلنَّاسِ مَن يَعۡبُدُ ٱللَّهَ عَلَىٰ حَرۡفٖۖ فَإِنۡ أَصَابَهُۥ خَيۡرٌ ٱطۡمَأَنَّ بِهِۦۖ وَإِنۡ أَصَابَتۡهُ فِتۡنَةٌ ٱنقَلَبَ عَلَىٰ وَجۡهِهِۦ خَسِرَ ٱلدُّنۡيَا وَٱلۡأٓخِرَةَۚ ذَٰلِكَ هُوَ ٱلۡخُسۡرَانُ ٱلۡمُبِينُ ١١﴾ [الحج: 11]

{ ﴿{Ó tún wà nínú àwọn ènìyàn ẹni t'ó ń jọ́sìn fún Allāhu lórí ahọ́n. Tí rere bá ṣẹlẹ̀ sí I, ó máa fi ọkàn balẹ̀ (sínú ẹ̀sìn). Tí ìfòòró bá sì ṣẹlẹ̀ sí I, ó máa yíjú rẹ̀ padà kúrò nínú ẹ̀sìn. Ó ṣòfò láyé àti lọ́run. Ìyẹn ni òfò pọ́nńbélé.} {11}} [Suuratul Hajj].

Awọn kan wa ti wọn ko gba Ọlọhun gbọ nitori fituna, ajalu, tabi adanwo ti o de ba wọn.

Níbí, ẹni tí kò gbàgbọ́ nínú Ọlọhun lè béèrè pé : Kí ló dé tí ibi fi wà ni ipilẹ ?

Ìdáhùn ni ṣókí : Torí pe a jẹ ẹniti wọn la nnkan bọ lọrun.

---

32 "[32] C. S. Lewis"

Nitori pe a wa ninu aye adanwo.

Olúwa wa sọ pé :

﴿كُلُّ نَفْسٍ ذَآئِقَةُ ٱلْمَوْتِۗ وَنَبْلُوكُم بِٱلشَّرِّ وَٱلْخَيْرِ فِتْنَةًۖ وَإِلَيْنَا تُرْجَعُونَ ﴿٣٥﴾﴾ [الأنبياء: 35]

{A o si fi aburu ati rere dan yin wo {35}}. [Suuratul Anbiyaa].

Oore ati aburu n bẹ torí pé ẹni tí wọ́n la nǹkan bọ̀ lọrun ni ẹ, líla nǹkan bọ ni lọrun gan si ni ìdí tí o fi wa láyé

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿ٱلَّذِى خَلَقَ ٱلْمَوْتَ وَٱلْحَيَوٰةَ لِيَبْلُوَكُمْ أَيُّكُمْ أَحْسَنُ عَمَلًاۚ وَهُوَ ٱلْعَزِيزُ ٱلْغَفُورُ ﴿٢﴾﴾ [الملك: 2]

{Ẹni tí Ó dá ikú àti ìṣẹ̀mí nítorí kí ó lè dan yín wò; èwo nínú yín l'ó máa ṣe iṣẹ́ rere jùlọ. Òun sì ni Alágbára, Aláforíjìn. {2}}. [Suuratul Mulk].

Bíbẹ aburu ati àdánwò fúnra rẹ ni ẹ̀rí ti o tóbi julọ lórí ìní àlàáfíà àlámọ̀rí ẹsin, ati lórí àṣìṣe aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun.

Ti a ba jẹ ọmọ ayé ti ara ni, a o ba ti le ni agbọye oore tabi aburu

Ti gbogbo ayé pátá ba jẹ nǹkan ti ko ni itumọ ni, ì bá tí hàn si wa rárá pé kò ní itumọ; torí pé ni ìbámu si ìwòye aigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun, a n rin nínú ìfi-tipá-múni ti ara ti o le koko, ti àwọn ofin àdánidá si n lọ lórí wa, ni abẹ bẹẹ, a o le ni agbọye pàápàá aburu, a o si lè mọ itumọ gbólóhùn aburu

Ǹjẹ́ àwọn ẹranko ti wọn ni ìdàgbàsókè julọ le mọ ìṣòro aburu bí?

Ìní agbọye aburu n túmọ̀ si pe a o kii ṣe ọmọ ayé yii, a si n gba agbọye wa fun bibẹ aburu latara ọrọ itisiwaju mìíràn yatọ si ọrọ itisiwaju ti Darwin fun ayé ti o ni i ṣe pẹ̀lú ara.

Awa fara mọ́ ọ̀rọ̀ itisiwaju atọrunwa, a o si fara mọ ti aigbagbọ ti ilẹ̀ ti o jẹ mọ́ ara, eyi ni itumọ kan ṣoṣo fun bi a ṣe ni agbọye aburú

Nigba ti o ti jẹ pe ẹniti a la iwọ Ọlọhun bọ lọrun ni wa, a jẹ pe kò jọjú kí awọn fitina ati adanwo o maa bẹ, ko si tun jọjú ki a rọkirika aburu."

Aburu ati ìrora, ati ìkápá lati dá ẹ̀ṣẹ̀ jẹ nǹkan ti kii ṣe àjèjì, o si tun jẹ àbájáde ti o hàn kedere fún òmìnira erongba ati iṣẹ atọrunwa

Bibẹ aburu ati adanwo ati awọn ajalu ati awọn ìfẹ́-ọkàn, awọn yii maa mu nkan to dáa julọ jade ninu nkan to wa lara eeyan daadaa, ati nkan to buru julọ ninu nkan to wa lara eeyan obilẹjẹ. "

Ninu ìyàlẹ́nu iṣesi àwọn alaigbagbọ ninu Ọlọhun nígbà tí wọ́n ba n tako bibẹ Adẹdaa tori aburú ti n bẹ, nínú eemọ naa ni pe àwọn naa n lo àlàyé yìí.

1- Ti baba ba jẹ ẹni rere, ti o si fẹ́ oore fun ọmọ rẹ, èéṣe ti o fi yọnda ki wọn fun un ni abẹrẹ ti o maa n dunni láti kojú àwọn kòkòrò tíntìntín?

2- Ṣe irora kan ṣẹlẹ si ọmọ naa nitori abẹrẹ bi?"

Ti o ba ri bẹẹ, a jẹ wípé baba naa kò sí nìyẹn.[33] "

Ǹjẹ́ ìparí-èrò ti ó bọ́gbọ́n mu nìyí bí?

Lẹ́yìn náà, kò jọjú pé a ò ní òye kúlẹ̀kúlẹ̀ ọgbọ́n atọrunwa nibi oore àti aburú.

---

[33] Ninu iwe "Ususun Gaa'ibah", olukọwe ni Ahmad Hasan, Dalaa'il Center. Pẹ̀lú pé wọn tún ọ̀rọ̀ inú rẹ̀ sọ lọ́nà mìíràn.

Ọlọhun ti fi ọgbọn han ninu awọn isẹ Kidiru fun asiwaju wa Anọbi Musa- ki ikẹ Ọlọhun maa ba a- pẹlu pe dajudaju o jẹ awọn iṣe kan ti gbangba rẹ jẹ nkan ti a kọ̀ ti kò rọrun, sugbọn o ko oore ti o tobi sinu. Itan Musa ati Khidru ko wa ninu Kuraani láti kàn sọ ìtàn lásán, ṣùgbọ́n ó wá fun arojinlẹ ati fifi àìdójú-ìwọ̀n ọmọniyan ati yíyára dajọ rẹ rinlẹ

Ninu iyalẹnu nipa alamọri ọrọ aburu ni pe ka ni ko si aburu ni aye ni, mi o ba tí jade kúrò ninu aye ti wọn bi mi sinu ẹ! “

Kì bá tí sí ọlaju, wọn o ba tí kọ́ àwọn ìlú ati awọn ilé-iṣẹ́ àti àwọn ilé, àwọn èèyàn ò bá tí bukaata sí iṣẹ́, àwọn èèyàn o ba ti ronú nípa dídènà àìsàn ati wíwá ọ̀nà àbáyọ sí ìṣòro, tabi mímú ìròrí wá láti wọ́ ìsinmi wa.

Ọmọniyan ì bá wulẹ̀ tí bukaata si lati kúrò ni ààyè ti wọn ti bí i

Nígbà tí kò sí aburu kankan ati idaamu ati adanwo ati wàhálà ati awọn ìṣòro ti a maa ṣẹ̀ṣẹ̀ maa wa ọ̀nà àbáyọ sí! “

Kini o wa fa idaamu ati àìsùn ati ironu ati iṣẹ? “

Aburu jẹ nkan to jẹ dandan ti o si ibuyẹ fun ninu aye! “

Kí o yáa ronu! “

Ki o si paya Ọlọhun; tori pé ẹniti a fi àṣẹ fún ní iṣẹ́ ni ẹ. “

Ọpọlọpọ ninu awọn eeyan ni adanwo ati aburu máa n ṣẹlẹ̀ sí, ti wọn si maa pada si ọdọ Ọlọhun, wọn maa wa wà ninu awọn eeyan rere, mimọ ni fun Ọlọhun Ọba ti O tobi, ọpẹ si ni fun Un. “

Gbogbo awọn kadara Ọlọhun ni ọgbọn ati oore n bẹ nibẹ. “

Musulumi gbọdọ gba àwọn kádàrá Ọlọhun gbọ, Anọbi- ki ikẹ Ọlọhun ati ọla Rẹ maa ba a- sọ pe : *Tí o ba ni nǹkan ti o da bii òkè Uhud ti o kún fún wúrà, ti o wa na an si ojú ọ̀nà Ọlọhun, Ọlọhun ko nii gba a lọ́wọ́ rẹ titi ti waa fi gba kádàrá gbọ, ti waa si mọ̀ pe ohun ti o ba ṣẹlẹ̀ si ọ, ko si

ninu kádàrá pe yoo fò ẹ́ ru ni, ohun ti o ba si fo ẹ ru, ko si ninu kádàrá pe o maa ṣẹlẹ̀ si ẹ ni, ẹni tí ó ba ku lori nǹkan ti o yatọ si eleyii maa wọ iná[34].

Awọn kadara Ọlọhun ninu oore ati aburu, o jẹ dandan fún musulumi lati yọnu si i."

Gbogbo kádàrá Ọlọhun ni oore, koda ki aburu tabi ìnira hàn nibi awọn kan ninu ẹ, ṣùgbọ́n ni igbẹyin, o maa ko oore ńlá sínú ati ọgbọ́n atọrunwa ti o péye

31- Ǹjẹ́ ẹsin ni o fa àwọn ogun ẹ̀sìn ti o kárí ilẹ̀ ni ìgbà kan bi?

Esi: Ẹ̀dà abara ṣẹ̀mí pẹlu àwọn ofin imọ Ọlọhun lọkan fun ẹgbẹẹgbẹ̀rún ọdun, ati pẹlu awọn ofin ti Anọbi Ibrahim ńlá mẹtẹẹta fun ẹgbẹ̀rún ọdún mẹrin, ti ẹsin ko si ko ìpalára tàárà ba ẹ̀dá abara. Kódà o tun fun ọmọniyan ni àwọn àwọn ìlànà ìwà híhù ti o ga ti o ba onigbagbọ ati alaigbagbọ lara mu, o si fi ìpìlẹ̀ ojúlówó ọlaju lélẹ̀, kódà a tun le sọ pe gbogbo oore lórí ilẹ̀ pátá lara oripa ijẹ anọbi yẹn ni, ẹsin ti jẹ ki awọn iléẹjọ́ ni ìsinmi nibi àìmọye ọ̀ràn, pabanbari wa ni pe ẹsin tun fi ìpìlẹ̀ ìmọ̀ ati ìwà híhù lélẹ̀ torí ọmọniyan lórí ilẹ̀. Àwọn ìlú ti wọn tẹ́wọ́gbà àwọn ofin imọ Ọlọhun lọkan naa, titi di òní, wọn ṣi n ni oríṣiríṣi ọlaju ti awọn ti wọn yapa ko ni iru ẹ, ti o si tun pèsè òrùlé idaabobo fun wọn lábẹ́ àwọn ofin ìmọ̀ Ọlọhun lọkan fúnra rẹ. Nígbà tí àwọn ìlú kan fi wa nínú aigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun fun nǹkan bii ọgọ́rùn-ún ọdun, gbogbo èèyàn pátá ni wọn wa ni bèbè ìparun, ni àwọn alaigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun wa n sọ nsinyii nipa ewu ti ẹsin ko ba ọmọniyan, ninu ìtàn ọmọniyan ko i tii si ilana ti o léwu to aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun. Ìpakúpa ti ẹ̀wọ̀n Gulag ni Soviet Union àtijó lati ọwọ alaigbagbọ to n jẹ Lenin, ati pípa ti wọn pa àwọn ẹ̀yà tí ó kéré gan run ninu ìjọba Násì ti Jámánì, ati bi wọ́n ṣe jẹ ìdá mẹ́rin ninu awọn to n gbé ilu Kambodia run lati ọwọ́ Pol Pot, ati bi wọn ṣe pa mílíọ̀nù méjì lé ni àádọ́ta ọmọ Ṣáínà ninu ìyípadà àṣà ìbílẹ̀ ńlá lati ọwọ Mao Zedong, ati híhàn ẹgbẹ́ ọmọ ogun àwọn alaigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun ni Yúróòpù, ti wọn si ti ilé ìsìn ẹgbẹ̀rún méjì lé ni ogójì pa- Ṣọọṣi ati Mọṣalaaṣi- wọn si pa ẹgbẹẹgbẹ̀rún àwọn ẹlẹ́sìn,

---

[34] Sohiihu sunanu ti Abu Daud, H:4699."

gbogbo nnkan ti a sọ yii jẹ àbájáde aigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun. Ogun agbaye kìíní ati keji jẹ ogun aigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun, ti o ṣe pe ojú ti aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun fi wo ọmọniyan ni o n darí rẹ̀, ati ìròrí igbiyanju lati ṣe afọmọ ti ẹ̀yà, abajade rẹ naa ni pípa nǹkan bii 5% àwọn to n gbe ayé run, ogun agbaye naa si ko ifaseyin ba gbogbo eeyan ati ẹni ti o borí ati ẹni ti wọn borí pẹ̀lú nnkan bii ìdá mẹ́ta ọ̀rúndún. Àwọn onimọ filọsọfi gbe ibi tí a n tọ̀ sí si àárín ìlú Paris lati fi pé ọ̀rọ̀ sọ pé ọlaju ti parí. Àwọn ogun aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun fi àwọn ilé ohun ìjà runlérùnnà sẹ́yìn, ti o si to lati pa gbogbo ìran èèyàn run ni àìmọye ìgbà. Ti eeyan ba wo àwọn ogun ti o ṣẹlẹ̀ ni ọ̀rúndún ogún, o maa ṣe àfihàn bi ìnira aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun ṣe tó. Aigbagbọ ninu bibẹ Ọlọhun yii ti fa ìròrí piparẹ ìran èèyàn ninu èyíkéyìí ogun ti o n bọ, ti irori naa ṣi wà digbí, eyi si ni àbájáde ti a n reti látàrí aigbagbọ nínú bibẹ Ọlọhun. [35]

32- Ki lo de ti àwọn Mùsùlùmí fi fà sẹ́yìn ti àwọn ará ìwọ̀ oòrùn ayé ṣì n tẹsiwaju gan?

Esi: Eyi ni ìbéèrè ọlaju

Àìmọye nǹkan ni àwọn Anọbi fi ojú winá lati dojú kọ ìbéèrè yii

Àìmọye àwọn olùtẹ̀lé ni wọn ti bọ́ látàrí àlámọ̀rí yii

Ibeere ọlaju ni ìpìlẹ̀ aigbagbọ àwọn ìjọ látayébáyé

Ọlọhun Ọba ti ọla Rẹ ga sọ pe:

﴿وَإِذَا تُتۡلَىٰ عَلَيۡهِمۡ ءَايَٰتُنَا بَيِّنَٰتٖ قَالَ ٱلَّذِينَ كَفَرُواْ لِلَّذِينَ ءَامَنُوٓاْ أَيُّ ٱلۡفَرِيقَيۡنِ خَيۡرٞ مَّقَامٗا وَأَحۡسَنُ نَدِيّٗا ٧٣﴾ [مريم: 73]

[35] https://en.wikipedia.org/wiki/League_of_Militant_Atheists “

{Nígbà tí wọ́n bá ń ké àwọn a-yah Wa t'ó yanjú fún wọn, àwọn t'ó ṣàì gbàgbọ́ yóò sọ fún àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo pé: "Èwo nínú ìjọ méjèèjì (àwa tàbí ẹ̀yin) l'ó lóore jùlọ ní ibùgbé, l'ó sì dára jùlọ ní ìjókòó?" {73} [Suratu Maryam].

Èwo nínú ìjọ méjèèjì (àwa tàbí ẹ̀yin) l'ó lóore jùlọ ní ibùgbé, l'ó sì dára jùlọ ní ìjókòó?"

Oluwadii Ibrahim As-Sak'raan- ki Ọlọhun ṣọ ọ- n sọ pe: "Eyi ni òfin tipẹ́tipẹ́ ati ìlànà ayé ti o n pààrà, ti eemọ latara agbeyẹwo ibi ìkówèé-ìṣẹ̀ǹbáyé-pa-mọ́-sí rẹ ti o ti pẹ́ kò sì leè tán. Ọgọọrọ àwọn ti wọn n jiṣẹ Ọlọhun lati igba ti ijẹ anọbi ti bẹ̀rẹ̀ titi di àsìkò ti wa ni òde òní ni wọn ti maa n dojú kọ àwọn agbára ti o ṣeé fojú rí ti o ju agbára wọn lọ, ti wọn si maa n fòòró àwọn èèyàn kuro nibi itẹle imisi ti wọn mu wa

Woye si ìrírí àwọn anọbi, waa ri i pe nnkan ti o fẹ́ jọ naa ni ìjàkadì láàrin olupepe "imisi atọrunwa" ati ifooro "agbára ti a le fojú rí". Waa si ri pe ifooro dé bá àwọn èèyàn latara agbára ti a fojú rí, o maa n ko làákàyè wọn lọ, o si maa n ṣẹri wọn kúrò nibi imisi, waa si ri awọn ti wọn n ṣiṣẹ fun ẹsin ti wọn n fojú winá ìfẹ́ àwọn èèyàn si awọn ohun ọrọ̀ àlùmọ́ọ́nì. Ojiṣẹ àkọ́kọ́ tii ṣe Nuuh- ki ọla maa ba a- àwọn ìjọ rẹ̀ là á mọ́lẹ̀ fun un pé:

﴿فَقَالَ ٱلۡمَلَأُ ٱلَّذِينَ كَفَرُواْ مِن قَوۡمِهِۦ مَا نَرَىٰكَ إِلَّا بَشَرٗا مِّثۡلَنَا وَمَا نَرَىٰكَ ٱتَّبَعَكَ إِلَّا ٱلَّذِينَ هُمۡ أَرَاذِلُنَا بَادِيَ ٱلرَّأۡيِ وَمَا نَرَىٰ لَكُمۡ عَلَيۡنَا مِن فَضۡلِۭ بَلۡ نَظُنُّكُمۡ كَٰذِبِينَ ٢٧﴾ [هود: 27]

{Àwa kò sì mọ àwọn t'ó tẹ̀lé ọ sí ẹnì kan kan tayọ àwọn ẹni yẹpẹrẹ nínú wa. {27}.} [Suratu Huud].

Ni kété ti anọbi Musa naa dé ni àgbéré ati ẹtan àwọn alagbara bá tún bẹ̀rẹ̀ padà lọ́tun ni iwájú imisi.

﴿وَقَالَ مُوسَىٰ رَبَّنَآ إِنَّكَ ءَاتَيْتَ فِرْعَوْنَ وَمَلَأَهُۥ زِينَةً وَأَمْوَٰلًا فِى ٱلْحَيَوٰةِ ٱلدُّنْيَا رَبَّنَا لِيُضِلُّوا۟ عَن سَبِيلِكَ ۖ رَبَّنَا ٱطْمِسْ عَلَىٰٓ أَمْوَٰلِهِمْ وَٱشْدُدْ عَلَىٰ قُلُوبِهِمْ فَلَا يُؤْمِنُوا۟ حَتَّىٰ يَرَوُا۟ ٱلْعَذَابَ ٱلْأَلِيمَ ﴿٨٨﴾﴾ [يونس: 88]

{Ànábì) Mu-sa- sọ pé : "Olúwa wa, dájúdájú Ìwọ l'O fún Fir'aon àti àwọn ìjòyè rẹ̀ ní ọ̀ṣọ́ àti dúkìá nínú ìṣẹ̀mí ayé. Olúwa wa, (O fún wọn) nítorí kí wọ́n lè ṣẹ́ri àwọn ènìyàn kúrò lójú ọ̀nà (ẹ̀sìn) Rẹ. {88}}. [Suuratu Yuunus.].

Iṣesi naa ko jẹ tuntun fun anọbi wa Muhammad- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- àwọn alátakò rẹ maa n lo àìní ọrọ̀ àlùmọ́ọ́nì rẹ lati fi ṣeri kúrò lọ́dọ̀ rẹ̀

﴿وَقَالُوا۟ لَوْلَا نُزِّلَ هَٰذَا ٱلْقُرْءَانُ عَلَىٰ رَجُلٍ مِّنَ ٱلْقَرْيَتَيْنِ عَظِيمٍ ﴿٣١﴾﴾ [الزخرف: 31]

{Wọ́n tún wí pé : "Kí ni kò jẹ́ kí Wọ́n sọ al-Kur'a-n yìí kalẹ̀ fún ọkùnrin pàtàkì kan nínú àwọn ìlú méjèèjì ?"} [Suuratu Zukhruf [31].].

Ọrọ Ibrahim As-Sakraan ti parí

Wọn ko fi àdánwò kan kan ẹ̀dá abara nínú ìtàn ijẹ anọbi ti o tobi ju fitina ti wọn kan latara agbára ìfẹ́ ọrọ̀ àlùmọ́ọ́nì ti Kèfèrí lọ.

Pẹlu pe ko si asopọ kankan rárá laarin ilọsiwaju ati ododo

Ìdàgbàsókè ti ọrọ̀ àlùmọ́ọ́nì àti ifaseyin, wọn ko ni nnkan kan ṣe pẹ̀lú pe tani ododo n bẹ pẹ̀lú rẹ tabi irọ́.

Kii ṣe dandan ni ki eeyan ti o jẹ ẹni pataki ati ẹniire jẹ ẹniti o ni ìdàgbàsókè ninu ọlaju.

Eeyan le jẹ ẹniti o ni akolekan pẹlu kikọ imọ ẹsin Isilaamu ki onitọun si jẹ olọṣi, idakeji rẹ̀ naa si tun le ṣẹlẹ̀.

Mélòómélòó ninu awọn ijọ ti o ti ni ìdàgbàsókè ninu ọlaju ti wọn si jẹ ẹniti o jina si ofin Ọlọhun ati ẹsin Rẹ ati imisi Rẹ:

﴿أَوَلَمۡ يَسِيرُواْ فِي ٱلۡأَرۡضِ فَيَنظُرُواْ كَيۡفَ كَانَ عَٰقِبَةُ ٱلَّذِينَ مِن قَبۡلِهِمۡۚ كَانُوٓاْ أَشَدَّ مِنۡهُمۡ قُوَّةٗ وَأَثَارُواْ ٱلۡأَرۡضَ وَعَمَرُوهَآ أَكۡثَرَ مِمَّا عَمَرُوهَا وَجَآءَتۡهُمۡ رُسُلُهُم بِٱلۡبَيِّنَٰتِۖ فَمَا كَانَ ٱللَّهُ لِيَظۡلِمَهُمۡ وَلَٰكِن كَانُوٓاْ أَنفُسَهُمۡ يَظۡلِمُونَ ٩﴾ [الروم: 9]

{Ṣé wọn kò rìn kiri lórí ilẹ̀ kí wọ́n wo bí ìkángun àwọn t’ó ṣíwájú wọn ṣe rí ? Wọ́n ní agbára jù wọ́n lọ. Wọ́n fi ilẹ̀ dáko. Wọ́n sì lo ilẹ̀ fún ohun tí ó pọ̀ ju bí (àwọn ará Mọkkah) ṣe lò ó. (9).} [Suuratu Ruum].

Ìdàgbàsókè ti ọrọ̀ àlùmọ́ọ́nì àti ọrọ̀ ti owó, méjèèjì kii ṣe ọ̀pá ìdíwọ̀n lati mọ olódodo

﴿فَلَمَّا جَآءَتۡهُمۡ رُسُلُهُم بِٱلۡبَيِّنَٰتِ فَرِحُواْ بِمَا عِندَهُم مِّنَ ٱلۡعِلۡمِ وَحَاقَ بِهِم مَّا كَانُواْ بِهِۦ يَسۡتَهۡزِءُونَ ٨٣﴾ [غافر: 83]

{Nígbà tí àwọn Ọ̀jíṣẹ́ mú àwọn ẹ̀rí t’ó yanjú wá bá wọn, wọ́n yọ àyọ̀pọ̀rọ́ nítorí ohun t’ó wà lọ́dọ̀ wọn nínú ìmọ̀ (ayé). Ohun tí wọ́n sì ń fi ṣe yẹ̀yẹ́ sì dìyà t’ó yí wọn po. {83}.".} [Suratu Ghafir].

Ti o ba ri bẹ́ẹ̀, ìdàgbàsókè ti ọrọ̀ àlùmọ́ọ́nì kii ṣe oun gan-an ni a maa yìn tabi ti a maa bú, a maa yìn ín pẹ̀lú odiwọn afọmọ rẹ pẹ̀lú imisi atọrunwa, ati pẹ̀lú odiwọn lilo ẹsin nínú ẹ, ati pẹlu odiwọn bi o ba ṣe fi wúlò fun ẹsin, ati pẹ̀lú odiwọn bi o ba ṣe n fi i wúlò fun àwọn èèyàn nítorí Ọlọhun.

Eyi ni idagbasoke ti a n fẹ.

Ọpa ìdíwọ̀n ti a fi n wọn jiju ara ẹni lọ láàrin àwọn ènìyàn kii ṣe ìdàgbàsókè wọn nibi ọrọ àlùmọ́ọ́nì, ṣùgbọ́n jiju ara ẹni lọ maa n bẹ pẹ̀lú

ìpayà ati iṣẹ rere, ìdàgbàsókè ọrọ àlùmọ̀ọ̀nì maa jẹ àtẹ̀gùn, kii ṣe òpin, o maa jẹ atẹgun fun sísin ati ṣíṣe anfaani fun àwọn èèyàn.

O maa jẹ idagbasoke ti ọrọ̀ àlùmọ̀ọ̀nì ti a fọ̀mọ́ pẹ̀lú imisi atọrunwa, oun nikan ṣi ni ìdàgbàsókè ti a n fẹ.

Èyí ni fífi ṣe àrólé tòótọ́ lórí ilẹ̀ : Fífi ṣe àrólé nibi jijẹ ẹrusin Ọlọhun, ati fífi jẹ àrólé nibi ṣíṣe afọmọ ti ìgbàgbọ́ fun gbogbo agbegbe iṣẹmi :

﴿ٱلَّذِينَ إِن مَّكَّنَّٰهُمْ فِى ٱلْأَرْضِ أَقَامُوا۟ ٱلصَّلَوٰةَ وَءَاتَوُا۟ ٱلزَّكَوٰةَ وَأَمَرُوا۟ بِٱلْمَعْرُوفِ وَنَهَوْا۟ عَنِ ٱلْمُنكَرِ ۗ وَلِلَّهِ عَٰقِبَةُ ٱلْأُمُورِ ﴿٤١﴾﴾ [الحج: 41]

{(Àwọn náà ni) àwọn tí ó jẹ́ pé tí A bá fún wọn ní ipò lórí ilẹ̀, wọn yóò kírun, wọn yóò yọ Zaka-h, wọn yóò pàṣẹ ohun rere, wọn yó sì kọ ohun burúkú. Ti Alla-hu sì ni ìkángun àwọn ọ̀rọ̀ ẹ̀dá. {41}.} [Suuratul Hajj].

Lọ mọ pe ti musulumi ba ṣe ohun ti o jẹ dandan le e lori, Ọlọhun yoo ṣe awọn okunfa oore ati oriire, ilọsiwaju ninu aye, ọla ati agbega ni ọjọ ikẹyin ni irọrun fun un.

﴿وَعَدَ ٱللَّهُ ٱلَّذِينَ ءَامَنُوا۟ مِنكُمْ وَعَمِلُوا۟ ٱلصَّٰلِحَٰتِ لَيَسْتَخْلِفَنَّهُمْ فِى ٱلْأَرْضِ كَمَا ٱسْتَخْلَفَ ٱلَّذِينَ مِن قَبْلِهِمْ وَلَيُمَكِّنَنَّ لَهُمْ دِينَهُمُ ٱلَّذِى ٱرْتَضَىٰ لَهُمْ وَلَيُبَدِّلَنَّهُم مِّنۢ بَعْدِ خَوْفِهِمْ أَمْنًا ۚ يَعْبُدُونَنِى لَا يُشْرِكُونَ بِى شَيْـًٔا ۚ وَمَن كَفَرَ بَعْدَ ذَٰلِكَ فَأُو۟لَٰٓئِكَ هُمُ ٱلْفَٰسِقُونَ ﴿٥٥﴾﴾ [النور: 55]

{Alla-hu ṣàdéhùn fún àwọn t'ó gbàgbọ́ ní ọ̀dodo nínú yín, tí wọ́n sì ṣe àwọn iṣẹ́ rere pé dájúdájú Ó máa fi wọ́n ṣe àrólé lórí ilẹ̀ gẹ́gẹ́ bí Ó ṣe fi àwọn t'ó ṣíwájú wọn ṣe àrólé. Dájúdájú Ó máa fi àyè gba ẹ̀sìn wọn fún wọn, èyí tí Ó yọ́nú sí fún wọn. Lẹ́yìn ìbẹ̀rù wọn, dájúdájú Ó máa fi ìfàyàbalẹ̀ dípò rẹ̀ fún wọn. Wọ́n ń jọ́sìn fún Mi, wọn kò sì fi n-ǹkan kan ṣẹbọ sí Mi. (55)} [Suuratun Nuur

Ni igba ti awọn musulumi ṣe àmúlò ẹsin wọn, wọn wa di aṣáájú ninu ẹsin ati ile-aye.

Isilaamu si ti ọwọ́ wọn mu ọlaju ti o pẹ fun ẹgbẹrun le ni ọgọrun meji ọdún wá, òun si ni ọlaju ti o pé jù, o tẹ siwaju lai dúró fún asiko yii

Ọlaju ti Isilaamu wáyé latara Isilaamu ni.

Pẹ̀lú èyí, oun nikan ni ẹsin ti o mu ọlaju wáyé.

Awọn ọlaju gba àwọn ẹsin to ku mọ́ra

Wàá ri ọ̀làjú àwọn ará ìwọ̀ oòrùn ayé ti o gba ẹsin Kristẹni mọ́ra, ti ọ̀làjú àwọn ara ìlú India si gba ẹsin Hindu mọ́ra

Ẹsin kan ṣoṣo ti o da ọlaju silẹ ni Isilaamu.

Ti àwọn Mùsùlùmí ba ti mọ ojúṣe ti o jẹ dandan fun wọn si ẹsin wọn, wọn maa darí ayé ni ara ati ẹ̀mí

Nígbà tí Isilaamu wọ ìlú Kọnsitantinópù ni ọdun 1453 AD, ìgbà naa ni Sànmánì Agbedeméjì tí o ṣókùnkùn parí ni Yúróòpù

Déètì tí Sànmánì Agbedeméjì ti o ṣókùnkùn parí ni 1453 AD, oun naa ni ọdun ti Isilaamu wọ Yúróòpù

Bi Isilaamu ṣe wọ aarin Yúróòpù ni ìmọ́lẹ̀ imọ ti n tàn yòò níbẹ̀

Wọ́n kọ àwọn nǹkan róbótó kan sára àjà gbọ̀ngàn ńlá ti ibi ìkówèésí Congress, ti o n tọka si awọn orísun ìdàgbàsókè ọlaju ti awọn ara iwọ oòrùn ayé, Isilaamu nìkan ni ẹsin kan ṣoṣo ti wọn dárúkọ nínú àwọn róbótó méje naa.

Isilaamu ni ẹsin kan ṣoṣo ti wọn dárúkọ, o si ni i ṣe pẹ̀lú imọ ìjìnlẹ̀ nípa ìṣẹ̀dá

ISLAM: PHYSICS"

Awọn róbótó yòókù ni i ṣe pẹ̀lú orúkọ àwọn ìlú kan, ohun ti àwọn ìlú yii si ṣe ni ìdàgbàsókè ti ìmọ̀ litireṣọ, tabi ti iṣẹ́ ọnà, tabi ti èdè.

Isilaamu mu ìmọ̀ wá, ti èdè àgbáyé fun àwọn imọ ìjìnlẹ̀ fun ọgọ́rùn-ún méje ọdún si jẹ èdè Lárúbáwá[36].

Ti àwọn Mùsùlùmí ba ti tun ẹsin wọn ṣe, ayé wọn naa yoo dáa

33- Ki ni èso ìjọsìn fun Ọlọhun ti ọla Rẹ ga?

Esi: Ọmọniyan, pẹ̀lú adamọ rẹ, ko lee mọ pàápàá rẹ, ọkàn rẹ ko si lee balẹ̀ àyàfi pẹ̀lú ìjọsìn fun Ọlọhun:

﴿ٱلَّذِينَ ءَامَنُواْ وَتَطۡمَئِنُّ قُلُوبُهُم بِذِكۡرِ ٱللَّهِۗ أَلَا بِذِكۡرِ ٱللَّهِ تَطۡمَئِنُّ ٱلۡقُلُوبُ ٢٨﴾ [الرعد: 28]

{Àwọn t'ó gbàgbọ́ ní òdodo, tí ọkàn wọn sì balẹ̀ pẹ̀lú ìrántí Allāhu ; ẹ gbọ́, pẹ̀lú ìrántí Allāhu ni àwọn ọkàn máa fi balẹ̀. {28} Suratu Ar-Ra'd.

Pẹ̀lú ìjọsìn ni àyà fi maa balẹ̀

[36] https://www.telegraph.co.uk/news/science/science-news/3323462/Science-Islams-forgotten-geniuses.html"

﴿وَلَقَدْ نَعْلَمُ أَنَّكَ يَضِيقُ صَدْرُكَ بِمَا يَقُولُونَ ٩٧ فَسَبِّحْ بِحَمْدِ رَبِّكَ وَكُن مِّنَ ٱلسَّٰجِدِينَ ٩٨﴾ [الحجر: 97-98]

{Àwa kúkú ti mọ̀ pé dájúdájú ohun tí wọ́n ń wí ń kó ìnira bá ọ. {97} Nítorí náà, ṣe àfọ̀mọ́ pẹ̀lú ìdúpẹ́ fún Olúwa rẹ. Kí o sì wà nínú àwọn olùforíkanlẹ̀ (fún Un). {98} Jọ́sìn fún Olúwa rẹ títí àmọ̀dájú (ìyẹn, ikú) yóò fi dé bá ọ.}. [Suuratul Hijr].

Jọ́sìn fun Olúwa rẹ: Ki àyà rẹ le balẹ

Fun ìdí yẹn, rakaa méjì pẹ̀lú irẹlẹ ati ìrònú maa ṣe nǹkan ti ìjókòó ifọkanbalẹ fun ọpọ wákàtí ko lee ṣe sinu ẹ̀mí ọmọniyan.

Ifayabalẹ ẹmi ọmọniyan n bẹ nibi ìjọsìn, gbogbo ẹni tí o ba jìnnà si ijọsin ni aya rẹ maa fún pinpin, waa maa ri i ni gbogbo igba ni ẹni tí o ma maa banujẹ lórí ilé ayé, ko nii yó, ọkàn rẹ ko si tun nii balẹ̀:

﴿وَمَنْ أَعْرَضَ عَن ذِكْرِي فَإِنَّ لَهُۥ مَعِيشَةً ضَنكًا وَنَحْشُرُهُۥ يَوْمَ ٱلْقِيَٰمَةِ أَعْمَىٰ ١٢٤﴾ [طه: 124]

{ìnira máa wà fún un nílé ayé. {124}} [Suuratu Taahaa].

Bi ọmọniyan ti wu ki o wa nínú gbẹdẹmukẹ tó, ti ko ba ni igbagbọ, yoo maa ṣẹmi ninu inira ni, ati ìdíje ti o gbóná ti ko nii parí pẹ̀lú nǹkan ti a kò mọ̀, waa maa ri i ni gbogbo igba ni ẹni ti yoo maa dàámú

Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- sọ pé : Ẹni ti o ba kó ayé léyà, Ọlọhun yóò da àlámọ̀rí rẹ rú, yoo waa fi àìní rẹ si aarin oju rẹ méjèèjì, ko si nii ni ju ohun ti wọn ba kadara fun un ninu ayé, ẹni tí alukiyaamọ ba jẹ ẹ lógún, Ọlọhun yoo ba a to àlámọ̀rí rẹ, yoo waa fi ọrọ̀ rẹ sínú ọkàn rẹ, ayé yoo si waa ba a ni nnkan ti yoo yẹpẹrẹ. [37]

[37] Sọhiihu sunanu Tirmiziy, Haa: 2465

Ìjọsìn maa la Musulumi kúrò nibi iyẹpẹrẹ fun ayé, yoo waa sọ ọ di olómìnira

Fun idi yẹn, Musulumi ti o ba n sin Ọlọhun pẹlu ododo ni eniyan ti o ni agbọye itumọ iṣẹmi, ati agbọye pàtàkì ayé, ati agbọye ohun ti o tori rẹ wà ni ayé yìí, ati agbọye pe oun n bẹ ni ayé yii fun idanwo, ati lati jọ́sìn fun Olúwa rẹ bi o ti ṣe ye, kii ṣe ki o le maa ṣẹmi ninu idaamu ti ko ni àǹfààní kankan, Oluwa wa sọ pé :

﴿ٱلَّذِى خَلَقَ ٱلْمَوْتَ وَٱلْحَيَوٰةَ لِيَبْلُوَكُمْ أَيُّكُمْ أَحْسَنُ عَمَلًا ۚ وَهُوَ ٱلْعَزِيزُ ٱلْغَفُورُ ۝٢﴾ [الملك: 2]

{" Ẹni tí Ó dá ikú àti ìṣẹ̀mí nítorí kí ó lè dan yín wò ; èwo nínú yín l'ó máa ṣe iṣẹ́ rere jùlọ. ".} [Suuratul Mulk.].

34- Ki ni àwọn àmì gbigba fun Ọlọhun ? Tabi ki a sọ pé : Bawo ni waa ṣe mọ pé ẹni tí ó gbà fun Ọlọhun pátápátá ni ọ ?

Esi : Mẹẹrin ni àwọn àmì gbigba fun Ọlọhun, àwọn nìyí :

Àkọ́kọ́ : Ijẹ ẹrusin fun Ọlọhun nibi gbogbo nǹkan kekere ati nǹkan ńlá ninu iṣẹmi rẹ :

﴿قُلْ إِنَّ صَلَاتِى وَنُسُكِى وَمَحْيَاىَ وَمَمَاتِى لِلَّهِ رَبِّ ٱلْعَٰلَمِينَ ۝١٦٢ لَا شَرِيكَ لَهُۥ ۖ وَبِذَٰلِكَ أُمِرْتُ وَأَنَا۠ أَوَّلُ ٱلْمُسْلِمِينَ ۝١٦٣﴾ [الأنعام: 162-163]

{Sọ pé: "Dájúdájú ìrun mi, ẹran (pípa) mi, ìṣẹ̀mí ayé mi àti ikú mi ń jẹ́ ti Alla-hu, Olúwa gbogbo ẹ̀dá.{162} Kò sí akẹgbẹ́ fún Un. Ìyẹn ni Wọ́n pa láṣẹ fún mi. Èmi sì ni ẹni-àkọ́kọ́ àwọn mùsùlùmí (ní àsìkò tèmi)." ".} [163] [Suuratul An'aam].

Ìrun mi, ẹran (pípa) mi, ìṣẹ̀mí ayé mi àti ikú mi ń jẹ́ ti Allāhu: Gbogbo nǹkan tí mo n ṣe ti Allahu ni, mo n kirun fún Ọlọhun, mo n tẹle àṣẹ obi

mi méjèèjì fun Ọlọhun, mo n ṣe atunyẹwo ẹkọ, mo si n kọ ẹkọ lati ṣe àwọn èèyàn ni anfaani fun Ọlọhun, mo n sùn ki n le ni agbára síi ni ọjọ́ keji lati ṣe nǹkan ti Ọlọhun pa mi láṣẹ

Oun naa ni ijẹ ẹrusin fun Ọlọhun nibi gbogbo iṣẹ, eyi ni akọkọ ninu awọn ami gbígbà fun Ọlọhun

Àmì kejì ti waa fi jẹ ẹni tí ó gbà pátápátá fún Ọlọhun: Oun ni titẹle ohun ti Ọlọhun pàṣẹ rẹ, ati jíjìnnà si ohun ti Ọlọhun kọ̀, Olúwa wa, mimọ Rẹ, sọ pe:

﴿يَـٰٓأَيُّهَا ٱلَّذِينَ ءَامَنُوٓاْ أَطِيعُواْ ٱللَّهَ وَرَسُولَهُۥ وَلَا تَوَلَّوۡاْ عَنۡهُ وَأَنتُمۡ تَسۡمَعُونَ ٢٠﴾ [الأنفال: 20]

{Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ tẹ̀lé ti Alla-hu àti Òjíṣẹ́ Rẹ̀. Ẹ má ṣe gbúnrí kúrò ní ọ̀dọ̀ rẹ̀ nígbà tí ẹ bá ń gbọ́ (a-yah) lọ́wọ́. {20}.} Suuratul Anfaal

AnfaalỌlọhun ti O ni agbára ti O gbọnngbọn sọ pé:

﴿يَـٰٓأَيُّهَا ٱلَّذِينَ ءَامَنُواْ ٱدۡخُلُواْ فِي ٱلسِّلۡمِ كَآفَّةٗ وَلَا تَتَّبِعُواْ خُطُوَٰتِ ٱلشَّيۡطَٰنِۚ إِنَّهُۥ لَكُمۡ عَدُوّٞ مُّبِينٞ ٢٠٨﴾ [البقرة: 208]

{{Ẹ̀yin tí ẹ gbàgbọ́ ní òdodo, ẹ kó s'ínú ẹ̀sìn 'Isla-m pátápátá} {208}.}. [Suuratul Baqara].

Ìtumọ̀ "Fis'silmi"ni: Inú Isilaamu

Ẹ kó s'ínú ẹ̀sìn 'Islām pátápátá: Ẹ maa ṣe gbogbo nǹkan ti Ọlọhun pa yin láṣẹ, ki ẹ si jawọ kúrò nibi nǹkan ti O kọ̀.

Ọlọhun pa mi láṣẹ nǹkan, maa ṣe e... O kọ fun mi kúrò nibi nǹkan, maa jawọ, eleyii ni pípé ijupajusẹ silẹ fun Ọlọhun

Àmì kẹta lórí ijupajusẹ silẹ fun Ọlọhun ni ki a gba fun fifi ofin Ọlọhun ṣe ìdájọ́, ki a yọnu si ofin Rẹ ki a si tẹwọ gba a

A maa tẹ́wọ́gbà gbogbo ofin atọrunwa, a o si nii tako àwọn ìjìyà ti Ọlọhun ṣe ni ofin, a gbọdọ̀ yọ́nú si ofin Ọlọhun; tori pé Ọlọhun mọ nǹkan ti o le tún ẹ̀dá Rẹ ṣe. O si mọ pe mimọ àwùjọ n bẹ nibi awọn ìjìyà yii,

﴿أَلَا يَعۡلَمُ مَنۡ خَلَقَ وَهُوَ ٱللَّطِيفُ ٱلۡخَبِيرُ ١٤﴾ [الملك: 14]

{"Ṣé (Alla-hu) kò mọ ẹni t'Ó dá ni? Òun sì ni Aláàánú, Alámọ̀tán." " Suuratul Mulk: 14

Ọlọhun ti O mọ tun sọ pe :

﴿أَفَحُكۡمَ ٱلۡجَٰهِلِيَّةِ يَبۡغُونَۚ وَمَنۡ أَحۡسَنُ مِنَ ٱللَّهِ حُكۡمٗا لِّقَوۡمٖ يُوقِنُونَ ٥٠﴾ [المائدة: 50]

{Ta ni ẹni tí ó dára ju Alla-hu lọ níbi ìdájọ́. {50}} [Suuratul Maa'idah.].

Ọlọhun ni O mọ ohun ti o maa tun àwọn èèyàn ṣe ni ayé àti ọ̀run wọn

Lilo ofin Ọlọhun maa ṣe àfọ̀mọ́ àwọn èèyàn, o si maa jẹ ki wọn o maa ṣemi ninu ifayabalẹ

Arákùnrin kan ti o n lérò pe oun gba Ọlọhun gbọ ati ohun ti wọn sọkalẹ fun Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- o lọ ba Kah'b ọmọ Al-Ash'raf ti o jẹ Júù lati dajọ fun un nibi àlámọ̀rí kan, dípò ki o lọ ba ojiṣẹ Ọlọhun- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ni ibẹru pe ki Anọbi- ki ikẹ ati ọla Ọlọhun máa bá a- ma lọ dajọ ti ko nii tẹ ẹ lọrun, o wa lọ ba Júù naa ni irankan idajọ ti o maa tẹ ẹ lọrun, ni ọrọ Ọlọhun wa sọkalẹ pe:

﴿أَلَمۡ تَرَ إِلَى ٱلَّذِينَ يَزۡعُمُونَ أَنَّهُمۡ ءَامَنُواْ بِمَآ أُنزِلَ إِلَيۡكَ وَمَآ أُنزِلَ مِن قَبۡلِكَ يُرِيدُونَ أَن يَتَحَاكَمُوٓاْ
إِلَى ٱلطَّٰغُوتِ وَقَدۡ أُمِرُوٓاْ أَن يَكۡفُرُواْ بِهِۦۖ وَيُرِيدُ ٱلشَّيۡطَٰنُ أَن يُضِلَّهُمۡ ضَلَٰلَۢا بَعِيدٗا ٦٠﴾ [النساء: 60]

{Ṣé o ò rí àwọn t'ó ń sọ̀rọ̀ (tí kò sì rí bẹ́ẹ̀) pé dájúdájú àwọn gbàgbọ́ nínú ohun tí A sọ̀kalẹ̀ fún ọ àti ohun tí A sọ̀kalẹ̀ ṣíwájú rẹ, tí wọ́n sì ń gbèrò láti gbé ẹjọ́ lọ bá òrìṣà, A sì ti pa wọ́n láṣẹ pé kí wọ́n lòdì sí i. Èṣù sì fẹ́ ṣì wọ́n lọ́nà ní ìṣìnà t'ó jìnnà. ".} {60} Suuratun- Nisaa'

Ti o ba jẹ Musulumi ti o gba fun Ọlọhun, o gbọdọ̀ maa ṣe àmúlò ofin Ọlọhun, ki o si gba fun ìdájọ́ Ọlọhun koda ki o ma tẹ ọ lọrun, Kii ṣe pe waa fi ofin Ọlọhun sílẹ̀, waa wa lọ si ọdọ Júù láti dajọ fun ẹ tori ki o le yọ ẹ ninu.

Ọlọhun ti O lágbára ti O gbọnngbọn sọ ninu aaya ti o kàn pé:

﴿وَمَآ أَرۡسَلۡنَا مِن رَّسُولٍ إِلَّا لِيُطَاعَ بِإِذۡنِ ٱللَّهِۚ وَلَوۡ أَنَّهُمۡ إِذ ظَّلَمُوٓاْ أَنفُسَهُمۡ جَآءُوكَ فَٱسۡتَغۡفَرُواْ ٱللَّهَ وَٱسۡتَغۡفَرَ لَهُمُ ٱلرَّسُولُ لَوَجَدُواْ ٱللَّهَ تَوَّابٗا رَّحِيمٗا ٦٤﴾ [النساء: 64]

{A ò rán Òjíṣẹ́ kan níṣẹ́ àfi nítorí kí wọ́n lè tẹ̀lé e pẹ̀lú ìyọ̀nda Alla-hu",} Suuratun' Nisaa: 64".

Ọlọhun ko ran àwọn ojiṣẹ ki a le pa a ti ki a wa kó ẹjọ́ lọ ba ofin mìíràn

Lẹyin naa Ọlọhun wa pari ẹkọ nínú ìṣẹ̀lẹ̀ yii ati ohun ti o jọ ọ pẹ̀lú aaya pàtàkì kan tó n ṣàlàyé ijẹ dandan ìtẹríba fun kiko ẹjọ́ lọ ba ofin Ọlọhun, Oluwa wa sọ pe:

﴿فَلَا وَرَبِّكَ لَا يُؤۡمِنُونَ حَتَّىٰ يُحَكِّمُوكَ فِيمَا شَجَرَ بَيۡنَهُمۡ ثُمَّ لَا يَجِدُواْ فِيٓ أَنفُسِهِمۡ حَرَجٗا مِّمَّا قَضَيۡتَ وَيُسَلِّمُواْ تَسۡلِيمٗا ٦٥﴾ [النساء: 65]

{Rárá, Èmi fi Olúwa rẹ búra pé wọn kò tí ì gbàgbọ́ ní òdodo títí wọn yóò fi gbà ọ́ ní olùdájọ́ lórí ohun tí ó bá dá yánpọnyánrin sílẹ̀ láàárín wọn. Lẹ́yìn náà, wọn kò níí ní ẹ̀hónú kan sí ìdájọ́ tí o bá dá. Wọ́n sì máa gbà pátápátá. ".}.{65} Suuratun' Nisaa,

. Èèyàn gbọdọ̀ gbà pátápátá fun ofin Ọlọhun, gbigba fun ofin Ọlọhun wa nínú àwọn àmì ijupajusẹ silẹ fun Isilaamu.

Àmì kẹrin lori gbigba fun Ọlọhun ni: Gbigba fun kádàrá Ọlọhun, gbogbo nǹkan tí Ọlọhun kádàrá wa pẹ̀lú ọgbọ́n Rẹ ni, nítorí naa, Musulumi maa gbà fun Ọlọhun nibi gbogbo kádàrá Rẹ... nibi oore ati aburu.

Ti idẹra ba ṣẹlẹ̀ si Musulumi, o maa dúpẹ́, ti ìnira ba ṣẹlẹ̀ si i, yoo ṣe suuru

Ti Ọlọhun ba fun ẹ ni oúnjẹ tabi ijẹ-imu ti o dára, tabi ilé ti o rẹwà, tabi ìyege ninu ẹkọ, tabi àlàáfíà ni ara, tabi ẹbí ti o dara, o maa dúpẹ́ fun Ọlọhun

Ti ìnira ba ṣẹlẹ̀ si Musulumi, bii àìsàn, tabi òṣì, tabi ìpayà, tabi àdánwò, tabi ibanujẹ, o maa ṣe suuru lori ìnira yii, yoo si wa iranlọwọ Ọlọhun, eyi ni iṣesi Musulumi ti o gba fun Oluwa rẹ.

Gbogbo nnkan pẹ̀lú kádàrá Ọlọhun ni, àlàáfíà ati àìsàn, ọrọ̀ ati òṣì... gbogbo nǹkan pẹ̀lú kádàrá Ọlọhun ati ọgbọ́n Rẹ, Musulumi si gbọdọ yọnu si awọn kádàrá; torí pé Ọlọhun ni O pebubu wọn.

Oluwa wa, mimọ Rẹ, sọ pé:

﴿إِنَّا كُلَّ شَيۡءٍ خَلَقۡنَٰهُ بِقَدَرٖ ٤٩﴾ [القمر: 49]

{ ﴿Dájúdájú A ṣẹ̀dá gbogbo n-ǹkan pẹ̀lú kádàrá. {49}.} [Suuratul Qamar "].

Allah tun sọ pe:

﴿قُل لَّن يُصِيبَنَآ إِلَّا مَا كَتَبَ ٱللَّهُ لَنَا هُوَ مَوۡلَىٰنَاۚ وَعَلَى ٱللَّهِ فَلۡيَتَوَكَّلِ ٱلۡمُؤۡمِنُونَ ٥١﴾ [التوبة: 51]

{" Sọ pé: “Kò sí ohun kan t’ó máa ṣẹlẹ̀ sí wa àyàfi ohun tí Alla-hu kọ mọ́ wa. {51}."} [Suratu At-Tawbah].

Ko lee ṣẹlẹ̀ si wa ayafi ohun ti Ọlọhun ba kọ mọ́ wa

Ọlọhun tun sọ pé:

﴿وَمَا كَانَ لِنَفۡسٍ أَن تَمُوتَ إِلَّا بِإِذۡنِ ٱللَّهِ كِتَٰبٗا مُّؤَجَّلٗاۗ وَمَن يُرِدۡ ثَوَابَ ٱلدُّنۡيَا نُؤۡتِهِۦ مِنۡهَا وَمَن يُرِدۡ ثَوَابَ ٱلۡأٓخِرَةِ نُؤۡتِهِۦ مِنۡهَاۚ وَسَنَجۡزِي ٱلشَّٰكِرِينَ ١٤٥﴾ [آل عمران: 145]

{" Kò lẹ́tọ̀ọ́ fún ẹ̀mí kan láti kú àfi pẹ̀lú ìyọ̀ǹda Alla-hu. {145} ".} [[145] Suuratu Al Imran]

Ọlọhun ti kádàrá àwọn àsìkò ti ẹda maa lo

Gbogbo nǹkan ti o ba n ṣẹlẹ̀ ni ayé, ati gbogbo átọ̀mù bín-ín-tín ti o n rìn ni ayé, ati gbogbo nǹkan tí ó bá n ṣẹlẹ̀, yoo maa ṣẹlẹ̀ pẹ̀lú ìmọ̀ Ọlọhun ati fifẹ Rẹ ati kádàrá Rẹ ati ọgbọ́n Rẹ ati ìkápá Rẹ

Olúwa wa, mimọ ni fun Un, sọ pe:

﴿ٱلَّذِي لَهُۥ مُلۡكُ ٱلسَّمَٰوَٰتِ وَٱلۡأَرۡضِ وَلَمۡ يَتَّخِذۡ وَلَدٗا وَلَمۡ يَكُن لَّهُۥ شَرِيكٞ فِي ٱلۡمُلۡكِ وَخَلَقَ كُلَّ شَيۡءٖ فَقَدَّرَهُۥ تَقۡدِيرٗا ٢﴾ [الفرقان: 2]

{Ó dá gbogbo n-ǹkan. Ó sì yan òdíwọ̀n (ìrísí, ìṣẹ̀mí àti àyànmọ́) fún un níwọ̀n-níwọ̀n. {2}.}. [Suratu Al-Furqan].

Ọlọhun da gbogbo nǹkan, O si kádàrá gbogbo nǹkan, ohun ti O ba fẹ́ ni o maa bẹ, ohun ti ko ba fẹ́ ko nii bẹ

Emi, gẹ́gẹ́ bí Musulumi, mo nílò lati gba fun gbogbo kádàrá Ọlọhun ti O ni agbara ti O gbọnngbọn

Pẹ̀lú eyi, ọmọniyan maa di ẹni tí ó gbà fun Ọlọhun

Ni ìparí, bawo ni maa ṣe wọ inú Isilaamu?

Isilaamu ni ẹsin Ọlọhun fun gbogbo ẹ̀dá abara, Ọlọhun sọ pe:

﴿إِنَّ ٱلدِّينَ عِندَ ٱللَّهِ ٱلۡإِسۡلَٰمُۗ وَمَا ٱخۡتَلَفَ ٱلَّذِينَ أُوتُواْ ٱلۡكِتَٰبَ إِلَّا مِنۢ بَعۡدِ مَا جَآءَهُمُ ٱلۡعِلۡمُ بَغۡيَۢا بَيۡنَهُمۡۗ وَمَن يَكۡفُرۡ بِـَٔايَٰتِ ٱللَّهِ فَإِنَّ ٱللَّهَ سَرِيعُ ٱلۡحِسَابِ ١٩﴾ [آل عمران: 19]

{{Dájúdájú ẹ̀sìn t'ó wà lọ́dọ̀ Alla-hu ni 'Isla-m. {19}} [Suuratu Al Imran]

ImranIsilaamu ni ẹsin ti Ọlọhun ko nii gba ẹsin mìíràn yàtọ̀ sii:

﴿وَمَن يَبۡتَغِ غَيۡرَ ٱلۡإِسۡلَٰمِ دِينٗا فَلَن يُقۡبَلَ مِنۡهُ وَهُوَ فِي ٱلۡأٓخِرَةِ مِنَ ٱلۡخَٰسِرِينَ ٨٥﴾ [آل عمران: 85]

{Ẹnikẹ́ni tí ó bá wá ẹ̀sìn kan ṣe yàtọ̀ sí 'Isla-m, A ò níí gbà á lọ́wọ́ rẹ̀. Ní Ọjọ́ Ìkẹ́yìn, ó sì máa wà nínú àwọn ẹni òfò. {85}.}. [[85] Suuratu Al Imran].

Fun idi ìyẹn, o di dandan fun gbogbo Musulumi lati gba Isilaamu.Ninu Isilaamu ni lila kúrò ninu iná ati jijere pẹ̀lú iyọnu Ọlọhun ati alujanna wa.Wiwọ inu Isilaamu jẹ idẹra kan ninu awọn idẹra ti o tobi jù, koda oun ni nǹkan ti o tobi ju ti o si pàtàkì jù ninu ayé rẹ.Pàápàá Isilaamu ni ṣiṣẹri pada si adamọ ati làákàyè.Wiwọ inu Isilaamu jẹ nǹkan ti o rọrùn, ko bukata si àwọn ààtò ìsìn tabi awọn nnkan bi àṣà, ohun ti o kan maa ṣe ni ki o wí gbólóhùn ijẹrii meji, pẹ̀lú ki o sọ pe “ASH'HADU AN LAA ILAAHA ILLAL LOOHU WA ASH'HADU ANNA MUHAMMADAN RASUULUL LOOH”

Pẹ̀lú eyi, ó ti di Mùsùlùmí

Lẹyin naa ni yoo bẹ̀rẹ̀ si nii maa ṣe ẹsin Isilaamu

Maa gba a ni imọran lati maa tẹle ìkànnì IslamHouse, onikaluku ni ìbámu si èdè rẹ ni, títí tí Musulumi o fi kọ nǹkan tuntun nipa bi yoo ṣe maa ṣe ẹsin Isilaamu.Línǹkì ìkànnì naa: https://islamhouse.com/ar/ “

# Contents

**IBEERE ATI IDAHUN ........................................................................ 3**

**NI ÌPARÍ, BAWO NI MAA ṢE WỌ INÚ ISILAAMU? .....................95**

**CONTENTS ......................................................................................97**